**ÌWÉ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́**

**YOR 224**
**SYNTAX OF YORUBA I**

**YOR 224**
**SÍŃTÁÀSÌ YORÙBÁ KÌÍNÍ (I)**

**Ikọ̀ Abala-Ẹ̀kọ́** Ọ̀jọ̀gbọ́n Ọládiípọ̀ J. Ajiboye (Òǹkọ̀wé Kọ́ọ̀sì/Course Developer/Writer) – UNILAG

**NATIONAL OPEN UNIVERSITY OF NIGERIA**

© 2021 by NOUN Press
National Open University of Nigeria
Headquarters
University Village
Plot 91, Cadastral Zone
Nnamdi Azikiwe Expressway
Jabi, Abuja

Lagos Office
14/16 Ahmadu Bello Way
Victoria Island, Lagos

e-mail: centralinfo@nou.edu.ng
URL: www.nou.edu.ng

All rights reserved. No part of this book may be reproduced, in any form or by any means, without permission in writing from the publisher.

Published by:
National Open University of Nigeria

First Printed 2020

Re-Printed 2021, 2023

ISBN: 978-978-058-207-4

**ÀKÓÓNÚ** **OJÚ ÌWÉ**

Ìfáárà………………………………………………………... iv
Àníyàn Abala Ẹ̀kọ́…………………………………….... iv
Èròǹgbà Abala Ẹ̀kọ́……………………………………. iv
Atọ́nà Fún Àkóónú Abala Ẹ̀kọ́…………….…………… iv
Èròjà Abala Ẹ̀kọ́........................................................... v
Àwọn Ìpín Ẹ̀kọ́………………………………………… v
Kíkọsílẹ̀ Módù………………………………………… vi

## ÌFÁÁRÀ

YOR 224 jẹ́ abala-ẹ̀kọ́ gírámà tó jẹ mọ́ Síńtáàsì Yorùbá. Ìkọ́ni yìí jẹ́ oníkírẹ̀díìtì mẹ́ta fún akẹ́kọ̀ọ́ ọlọ́dún kejì. Ìkọ́ni. Módù mẹ́ta niì kọ́niyìí. A gé módù kọ̀ọ̀kansí ìpín márùn-ún. Ọ̀pọ̀ orí-ọ̀rọ̀ gírámà Yorùbá tó jẹ mọ́ síńtáàsì niìkọ́ni yìí dá lé. Níwọ̀n bó ti jẹ́ pé abala síńtáàsì àkọ́kọ́ ni kọ́ọ̀sì yìí jẹ́, kò sí ẹ̀kọ́ tó jẹ́ àtẹ̀gùn fun. A ti ṣe àkójọ èròjà ìkọ́ni yìí lọ́nà tó mú kí kíkọ abala gírámà tó rọ̀ mọ́ síńtáàsì rọrùn fún kíkọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tó jẹ́ elédè. Ìlànà ìkọ́ni yìí jẹ́ ká mọ ohun tí ìkọ́ni yìí da lé àti àwọn ìwé fún àmúlò. Nínú èròjà yìí, ẹ tún máa ṣe alábàpàdé ìlànà gbígbòòrò fún iye àkókò tó ṣeé ṣe kí ẹ lò fún ìpín kọ̀ọ̀kan. Àwọn iṣẹ́ àṣetiléwá tí olùkọ́ fọwọ́sí wà fún kí o lè tètè rí bí o ti ń ṣe sí kí o bà á lè tètè tẹ̀síwájú. Wíwá sí kíláàsì ìkọ́ni máa jẹ́ ìrànlọ́wọ́ láti lè jíròrò lórí àwọn ìṣòro tí ẹ bá ní pẹ̀lú olùkọ́ yín. Nítorí náà, ó pọn dandan láti máa lọ sí àwọn kíláàsì wọ̀nyẹn.

## ÀNÍYÀN ABALA Ẹ̀KỌ́

Àníyàn abala ẹ̀kọ́ yìí ni láti jẹ́ kí ẹ mọ:

- ohun tí ẹ̀ka ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè tí a mọ̀ sí síńtáàsì jẹ́
- oríṣiríṣi ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ tí a lè bá pàdé nínú gbólóhùn Yorùbá
- ìbáṣepọ̀ tó wà láàrín oríṣiríṣi ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ nínú gbólòhùn
- oríṣiríṣi gbólóhùnn ípa òdiwọ̀n ìhun
- ọ̀kanòjọ̀kan iṣẹ́ tí gbólóhùn lè ṣe nínú ìpèdè Yorùbá.

## ÈRÒŃGBÀ ABALA Ẹ̀KỌ́

Ní ìparí abala-ẹ̀kọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ ti gbọ́dọ̀ lè:

- sọ ní pàtó, ohun tí síńtáàsì jẹ́ nínú gírámà
- dá oríṣirísị ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ tó wà lédè Yorùbá mọ̀
- jíròrò lórí ọ̀kanòjọ̀kan ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀
- dá ìbáṣepọ̀ tó wà láàrín àwọn ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ nínú gbólòhùn mọ̀
- ṣe àlàyé orísịríṣi gbólóhùn nípa òdiwọ̀n ìhun
- sọ ọ̀kanòjọ̀kan iṣẹ́ tí gbólóhùn lè ṣe nínú ìpèdè Yorùbá

## ATỌ́NÀ FÚN ÀKÓÓNÚ ABALA Ẹ̀KỌ́

O gbọ́dọ̀ ka gbogbo ìpín ẹ̀kọ́; kí obàá lè parí abala-ẹ̀kọ́ yìí. O tún gbọ́dọ̀ ka àwọn àkànlò-ìwé àti àwọn èròjà tí NOUN fún yín. Ní ìpín kọ̀ọ̀kan, o máa rí àwọn (ìbéèrè) iṣẹ́-àyànṣe fún ìgbéléwọ̀n ara ẹni, o tún gbọ́dọ̀ máa fi iṣẹ́ àṣetiléwá sọwọ́ síwájú fún ìgbéléwọ̀n.

Dájúdájú, ogbọ́dọ̀ ni lọ́kàn pé o máa ṣe ìpínnwò ní ìparí abala-ẹ̀kọ́ yìí. Nǹkan bí ọ̀sẹ̀ mẹ́ẹ̀ẹ́dógún ni mo retí pé abala-ẹ̀kọ́ yìí a gbà ẹ́ láti kọ́. Ní ìsàlẹ̀ yìí, wà á rí àwọn ẹ̀yà abala-ẹ̀kọ́ lọ́kanòjọ̀kan. Pípín àkókò rẹbó ti tọ́ àti bó ti yẹ ṣe pàtàkì láti lè parí abala-ẹ̀kọ́ lásìkò.

## ÈRÒJÀ ABALA Ẹ̀KỌ́

Àwọn ẹ̀yà tó ṣe pàtàkì ní abala-ẹ̀kọ́ yìí nìwọ̀nyí:

1. Ìlànà fúnAbala-ẹ̀kọ́
2. Ìpín Ẹ̀kọ́
3. Ìwé-àkànlò
4. Fáìlì Iṣẹ́-àyànṣe
5. Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ Ètò-iṣẹ́

## ÀWỌN ÌPÍN Ẹ̀KỌ́

Ní abala-ẹ̀kọ́ yìí, módù mẹ́ta àti ìpín mẹ́ẹ̀ẹ́dógún (15) ló wà níbẹ̀. Ní módù àkọ́kọ́ ni a ti ṣe ìfáárà sí abala ìmọ̀-ẹ̀dá èdè tí a mọ̀ sí síǹtáàsì. Módù kìíní (1) jẹ́ ìfáárà sí ìmọ̀-ẹ̀dá èdè. Àmọ́ níwọ̀n bí ó ti yẹ kí ẹ ní òyè nípa ohun tí èdè jẹ́, ó pọn dandan kí a fi òye èdè yé yín àti ìwúlò rẹ̀.

Módù yìí máa fún yín ní òye ohun tí ìmọ̀-ẹ̀dá èdè jẹ́ àti àwọn ẹ̀ka rẹ̀ àti àwọn. Nínú Módù yìí kan náà ni ẹ ti máa ní ìmọ̀ tó kún nípa ìmọ̀-ẹ̀dá èdè tó níí ṣe pẹ̀lú kíkọ́ èdè. Ẹ ó tún ti kọ́ nípa, orísìríṣì ẹ̀ka ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè àti bí wọ́n ṣe wọnú ara wọn. Módù kejì lẹ ti máa ní òye nípa ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ àti ẹ̀ka gíŕmà tó jẹ mọ́ lìǹgúísíìkì àmúlò (applied linguistics). Níwọ̀n bó ti jẹ́ pé kíkọ́ èdè tayọ̀/kọjá àfiwe gírámà, ó di dandan kí ń̄ tún ṣíjú rẹ sí àfiwé ìmọ̀ ìsọwọ́lò-èdè pẹ̀lú. Ohun tí mo mojú tó ní Módù kẹ́ta nìyí.

**Módù 1**


Ìpín 1 Ọ̀rọ̀-Orúkọ
Ìpín 2 Arọ́pò-Orúkọ
Ìpín 3 Ọ̀rọ̀-Ẹ̀yán
Ìpín 4 Ọ̀rọ̀-Ìṣe
Ìpín 5 Ọ̀rọ̀-Àpọ́nlé


**Módù 2**


Ìpín 1 Wúnrẹ̀n Aṣegírámà
Ìpín 2 Ìhungbólohùn: Àwọn Àpólà
Ìpín 3 Gbólóhùn Abọ́dé
Ìpín 4 Gbólóhùn Alákànpọ̀
Ìpín 5 Gbólóhùn Oníbọ̀ I


**Módù 3**


Ìpín 1 Gbólóhùn Oníbọ̀ II
Ìpín 2 Iṣẹ́ tí gbólóhùn ń ṣe: Ìròyìn àti Ìpàṣẹ
Ìpín 3 Ìṣèbéèrè I: Onídáhùn Àlàyé

Ìpín 4 Ìṣèbéèrè II: Onídáhùn bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́
Ìpín 5 Ìṣètẹnumọ́

**YOR 224** SÍŃTÁÀSÌ YORÙBÁ KÌÍNÍ (I) (ÌPÍN KÍRẸ́DÍÌTÌ 3 C)
Ní kọ́ọ̀sì yìí, a ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ lédè Yorùbá, gbólóhùn àti àwọn fọnrán-ìhun rẹ̀, oríṣiríṣi ìhun gbólóhùn àti iṣẹ́ tí gbólóhùn ń ṣe.

**KÍKỌSÍLẸ̀ MÓDÙ**

**Módù 1: Ìfáárà gbogbogbò**
Gbólóhùn ni ààrín gùngùn ìpèdè ọmọ ẹ̀dá. Ó wà láààrín ẹyọ ọ̀rọ̀ àti afọ̀. Kí wá ni gbólóhùn fúnra rẹ̀? Gbólóhùn ni àtòpọ̀ ọ̀rọ̀ tó pé pérépéré nípa níní ìtumọ̀ kíkún kó sì bá òfin gírámà mu. Kí ni òdiwọn èyí? Irú àtòpọ̀ ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ gbọ́dọ̀ ni ọ̀rọ̀-ìṣe kan. Tó bá rí bẹ́ẹ̀, ó kéré tán gbólóhùn lè jẹ́ wóró ọ̀rọ̀ ìṣe. Ẹ jẹ́ kí a wo àpẹẹrẹ méjì fi ṣe àkàwé èrò nípa gbólóhùn.

(1) a. Olú wá sí ilé
b. Wá.

Àpẹẹrẹ àkọ́kọ́ jẹ́ ọ̀rọ̀ mẹ́rin, ti ó ní ìtumọ̀ kíkún, ó sì tẹ̀lé òfin gírámà èdè Yorùbá. Ẹ̀wẹ̀, bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé wóró ẹyọ ọ̀rọ̀ kanni ó wà ní (1b), síbẹ̀ ìpèdè kíkùn ni òun náà. Nítorí náà, ohun tó ṣe pàtàkì tó sì jẹ́ kòṣeémọ́nìí nínú ohun tí a mọ̀ sí ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ gbólóhùn ni ọ̀rọ̀-ìṣe. Kí wá ni àkóónú gbólóhùn? Ẹ jẹ́ kí a tún wo gbólóhùn ìsàlẹ̀ yìí.

(2) Olú gíga yóò lè lọ sí ọjà alẹ́ tí ó bá ti jí.

Kí a tó tẹ̀síwájú, ó yẹ kí a fìdí oríkì wa múlẹ̀ pẹ̀lú àpẹẹrẹ (3) tí kò bétí mu tàbí ní ìtumọ̀.

(3) a. *Ilé wá sí Olú
b. *Yìí

Tí a bá farabalẹ̀ wo (3a), ohun àkọ́kọ́ tí a máa ṣe àkíyèsí ni wí pé iyeàtiirú ọ̀rọ̀ kannáà ló wà níbẹ̀ pẹ̀lú èyí ti (1a), síbẹ̀ a sà á lámì pé ìpèdè náà kò bétí mu, bẹ́ẹ̀ ni kò ní ìtumọ̀. Ìdí ni wí pé ilé kò lè wá sí ọ̀dọ̀ Olú, Olú kì í sì í ṣe ibikan pàtó tí ò lè gba ọ̀rọ̀-atọ́kùn "sí" nínú irú gbólóhùn yìí. Kìkì ohun tó sọ gbólóhùn yẹn di akúrẹtẹ̀ ni pàsípààrọ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ méjì tó wà níbẹ̀, i.n.p., "Olú" nìkan ni ó lè jẹ́ "olùwà" fún ọ̀rọ̀ ìṣe "wà", bẹ́ẹ̀ náà ni ọ̀rọ̀-orúkọ ibi (ìdó) ni ó lè gba ọ̀rọ́-atọ́kùn "sí" nínú àpẹẹrẹ (1). Bákan lọ̀rọ̀ rí ní (3b). Bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé gẹ́gẹ́ bí ti (1b), ẹyọ ọ̀rọ̀ kan ló gbìyànjú láti dá dúró ní (3b), ìpèdè yẹn kò nítumọ̀ nítorí kìí ṣeirú ọ̀rọ̀ bí (1b), tí ó lè dá dúró tó máa fún wa ní ìtumọ̀ kíkún.

Ní àpẹẹrẹ (2), ọ̀rọ̀ mẹ́tàlá ni a tò pọ̀, tí a sọ di odindi gbólóhùn; onírúurú sì ni wọ́n. Ohun tí a ó yẹ̀wò ní módù (1) yìí ni oríṣiríṣi ìsọ̀rí tí a lè pín

àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyẹn sí. Kí a tó tẹ̀síwájú, a gbọ́dọ̀ mẹ́nu bà á wí pé, a kì í sàà dédé pín ọ̀rọ̀ inú èdè sí ìsọ̀rí (iye ọ̀nà) tí ó wù wá, òṣùwọ̀n wà tí a fi máa ń pínwọn. Òṣùwọ̀n méjì pàtàkì ló wọ́pọ̀ jù tí àwọn onígírámà èdè Yorùbá má ń lò; àwọn ni òṣùwọ̀n iye tí ọ̀wọ́ ọ̀rọ̀ kan bá tó. Ìkejì ni iṣẹ́ tí ọ̀rọ̀ bá ń ṣe nínú gbólóhùn. A sì lè lo méjèèjì papọ̀. Ní ti iye tí ọ̀rọ̀ bá tó, àwọn ọ̀rọ̀ tí àpẹ̀ẹrẹ wọn bá pọ̀ jáǹtìrẹrẹ máa ń wà ní ìsọ̀rí kan tí a mọ̀ sí "open class" nígbà tí àwọn tí iye wọn kò bá ju péréte lọ tí a mọ̀ sí "closed class máa ń wà ní ìsọ̀rí mìíràn. Pẹ̀lú òye iye tí ọ̀rọ̀ bá tó, ìsọ̀rí márùn-únni a ó pín àwọn ọ̀rọ̀ inú èdè Yorùbá sí. Àwọn ìsọ̀rí náà ni Ọ̀rọ̀-orúkọ, Ọ̀rọ̀-ìṣe, Ọ̀rọ̀-ẹ̀yán, Ọ̀rọ̀-ẹ̀pọ́n àti Wúnrẹ̀n aṣegírámà. Nínú ìsọ̀rí márààrún, mẹ́rin àkọ́kọ́ bá òṣùwọn àwọn ọ̀rọ̀ tí àpẹ̀ẹrẹ wọnbá pọ̀ jáǹtìrẹrẹ mu nígbà tí ìkarùn-ún bá ìsọ̀rí àwọn ọ̀rọ̀ tí iye wọn kò ju péréte lọ. Ẹ jẹ́ kí a mú wọn ní sísẹ̀n̄tẹ̀lé.

**MAIN COURSE**

| ÀKÓÓNÚ | | OJÚ-ÌWÉ |
|---|---|---|


| | | |
|---|---|---|
| **Módù 1** | **…………………………………………..** | **1** |
| Ìpín 1 | Ọ̀rọ̀-Orúkọ……………………………… | 1 |
| Ìpín 2 | Arọ́pò-Orúkọ…………………………… | 9 |
| Ìpín 3 | Ọ̀rọ̀-Ẹ̀yán……………………………….. | 16 |
| Ìpín 4 | Ọ̀rọ̀-Ìṣe………………………………….. | 21 |
| Ìpín 5 | Ọ̀rọ̀-Àpọ́nlé……………………………... | 29 |
| **Módù 2** | **……………………………………………...** | **33** |
| Ìpín 1 | Wúnrẹ̀n Aṣegírámà……………………… | 33 |
| Ìpín 2 | Ìhungbólohùn: Àwọn Àpólà…………….. | 39 |
| Ìpín 3 | Gbólóhùn Abọ́dé………………………… | 45 |
| Ìpín 4 | Gbólóhùn Alákànpọ̀……………………... | 48 |
| Ìpín 5 | Gbólóhùn Oníbọ̀ I……………………….. | 51 |
| **Módù 3** | **……………………………………………...** | **54** |
| Ìpín 1 | Gbólóhùn Oníbọ̀ II……………………… | 54 |
| Ìpín 2 | Iṣẹ́ tí gbólóhùn ń ṣe: Ìròyìn àti Ìpàṣẹ……... | 57 |
| Ìpín 3 | Ìṣèbéèrè I: Onídáhùn Àlàyé..................... | 61 |
| Ìpín 4 | Ìṣèbéèrè II: Onídáhùn bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́……. | 66 |
| Ìpín 5 | Ìṣètẹnumọ́……………………………….. | 69 |

# MÓDÙ 1

Ìpín 1 Ọ̀rọ̀-Orúkọ
Ìpín 2 Arọ́pò-Orúkọ
Ìpín 3 Ọ̀rọ̀-Ẹ̀yán
Ìpín 4 Ọ̀rọ̀-Ìṣe
Ìpín 5 Ọ̀rọ̀-Àpọ́nlé

## ÌPÍN 1 Ọ̀RỌ̀-ORÚKỌ

**Àkóónú**

1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ọ̀rọ̀-orúkọ
3.1 Oríkì
3.1.1 Oríkì ọ̀rọ̀-orúkọ ní ìlànà gírámà àtijọ́
3.1.2 Oríkì ọ̀rọ̀-orúkọ ní ìlànà gírámà òdeòní
3.2 Ìpínsísọ̀rí ọ̀rọ̀-orúkọ
3.2.1 Àbùdá ìhun
3.2.1.1 Ọ̀rọ̀-orúkọ onisílébù méjì
3.2.1.2 Onisílébù mẹ́ta
3.2.1.3 Onisílébù bẹẹrẹ
3.2.1.4 Gbólóhùn àsọdorúkọ
3.2.2 Àbùdá ìtumọ̀
3.2.2.1 Ọ̀rọ̀-orúkọ Aṣeékà àti Aláìṣeékà
3.2.2.2 Àrídìmú àti Àfòyemọ̀
3.2.2.3 Ọ̀rọ̀-orúkọ ènìyàn àti ẹranko
3.2.2.4 Ọ̀rọ̀-orúkọ Ibi àti Ohun
3.2.2.5 Ọ̀rọ̀-orúkọ àìṣẹ̀dá àti àṣẹ̀dá
3.2.2.6 Wúnrẹ̀n aṣegírámà aṣorúkọ ìbéèrè
4.0 Ìgúnlẹ̀
5.0 Isọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Àyànṣeonímáàkì Olùkọ́
7.0 Àwọnìwé Fúnkíkà

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ohun tí a pète láti ṣe ní ìpín (1) ni àgbéyẹ̀wò ọ̀rọ̀-orúkọ.

## 2.0 ÈRÒŃGBÀ

Èròǹgbà ìpín yìí ni kí a se àlàyé wẹ́lẹ́wẹ́lẹ́ lọ́nà tó máa yéni yéké yéké ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ tí a mọ̀ sí ọ̀rọ̀-orúkọ lọ́nà tí ó máa fi rọrùn fún akẹ́kọ̀ọ́ láti lè dá ọ̀rọ̀-orúkọ mọ̀ nínú gbólóhùn.

## 3.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́ Ọ̀RỌ̀-ORÚKỌ

Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìpín yìí ṣe àyẹ̀wò ọ̀rọ̀-orúkọ, oríkì tí a lè fun, ọ̀kanòjọ̀kan ọ̀nà tí a lè pín ọ̀rọ̀-orúkọ sí pẹ̀lú àbùdá tí ènìyàn lè lò pín sí ìsọ̀rí. A tẹ̀síwájú láti ṣe ìgúnlẹ̀ àti ìsọníṣókí ohun tí a ti gbé ṣe. Lẹ́yìn náà ni a ṣe àgbékalẹ̀ iṣẹ́ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ àti àfihàn ìwé ìtọ́kasí tó lè wúlò fún ọ láti fi kún ìmọ̀ rẹ.

Ìsọ̀rí pàtàkì kan ni ọ̀rọ̀-orúkọ jẹ́ lédè Yorùbá gẹ́gẹ́ bí ti àwọn èdè mìíràn lágbàáyé. A ó bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ lórí ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ yìí pẹ̀lú oríkì ọ̀rọ̀-orúkọ.

### 3.1 Oríkì

Oríṣiríṣi oríkì tí àwọn onímọ̀ gírámà èdè ti ṣe àgbékalẹ̀ ló ti wà tí a lè gbéyẹ̀wò.

#### 3.1.1 Oríkì ọ̀rọ̀-orúkọ ní ìlànà gírámà àtijọ́

Bí a kò bá tilẹ̀ tí ì mọ ibití a ń dorí kọ, ó yẹ kí a mọ ibití a ti ń bọ̀. Ìdí nìyí tó fi yẹ kí a bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú èrò tó ti wà látọjọ́ tó ti pẹ́ nípa oríkì ọ̀rọ̀-orúkọ. Ní ìlànà àtijọ́ yẹn, ọ̀rọ̀-orúkọ ni ọ̀rọ̀kọ́rọ̀ tó bá lè tọ́ka sí ènìyàn, ẹranko, ibi tàbí ohun.

(4) Òjó, ewúrẹ́, Ìbàdàn, ọkọ́, aṣọ, ìgbálẹ̀, àtùpà, ẹkùn, òkun,

Ọ̀nà mìíràn tí a lè fi fún ọ̀rọ̀-orúkọ ní oríkì ni ipò tí ó bá wà nínú gbólóhùn. Irú oríkì bẹ́ẹ̀ ni a mọ̀ sí ajẹmọ́lò.

#### 3.1.2 Oríkì ọ̀rọ̀-orúkọ ní ìlànà gírámà òdeòní

Ọ̀rọ̀-orúkọ ni ọ̀rọ̀kọ́rọ̀ tí ó bà lè ṣe iṣẹ́ tàbí wà ní ipò:

(i) olùwà
(ii) abọ̀ fún ọ̀rọ̀ ìṣe
(iii) àbọ̀ fún ọ̀rọ̀-atọ́kùn

(5) a. **Ọ̀ya** jẹ **àgbàdo** ní **oko**.
b. **Ọkọ̀** pa **èniyan** mẹ́fà sí **Títì** ní **Dùgbẹ̀**.

Kò sí àríyànjiyàn lórí wí pé oríkì yìí fàyè gba arọ́pò orúkọ àti àpólà orúkọ pẹ̀lú. Ohun tó fàá ni wí pé àti arọ́pò orúkọ àti àpólà orúkọ ni a lè rí ní ipò wọ̀nyẹn; síbẹ̀ ìpín ọ̀tọ̀ ni a ó ti wo arọ́pò-orùkọ

Àwọn ọ̀rọ̀ tí a kùn dú ní (5) jẹ́ àpẹẹrẹ ọ̀rọ̀-orúkọ bóyá gẹ́gẹ́ bí olùwà tàbí àbọ̀ nínú gbólóhùn.

Ó tún ṣeé ṣe kí a fi iṣẹ́ tí ọ̀rọ̀ bá ń ṣe nínú gbólóhùn pín wọn sí ìsọ̀rí ọ̀rọ̀-orúkọ.

(6) a. **Ìranù** ni iṣẹ́ aṣẹ́wó
b. **Pàtàkì** ni iṣẹ́ olùkọ́
d. "**d**" ni o kọ bá yẹn!

Kò sí àníàní wí pé ọ̀rọ̀-orúkọ ni "ìranu" ní (6a). Ipò ìtẹnumọ́ ni ó wà níbẹ̀. Kìkì ọ̀rọ̀-orúkọ tàbí ọ̀rọ̀ tí a ti sọ di ọ̀rọ̀-orúkọ ló máa ń wà nípò yìí. Ipò yìí kan náà ni **pàtàkì** wà ní (6b); ipò ọ̀hún kan náà nidwà ní (6d). Ó wá já sí pé, ọ̀rọ̀-orúkọ ni **ìranù**, **pàtàkì** àti "**d**" nínú àwọn àpẹẹrẹ wọ̀nyẹn bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé tí a bá yọ wọ́n kúrò nínú gbólóhùn tí wọ́n ti jẹ yọ, **pàtàkì** àti **d** kò ní àbùdá ọ̀rọ̀-orúkọ nípa ìtumọ̀; ìyẹn ni wí pé, ìlò àti iṣẹ́ ló sọ wọ́n di ọ̀rọ̀-orúkọ.

Ẹ jẹ́ ká tún wo oríkì mìíràn fún ọ̀rọ̀-orúkọ.

Ọ̀rọ̀-orúkọ ni ọ̀rọ̀kọ́rọ̀ tí ó bà lè gba ẹ̀yán

(7) Dúró ní **irungbọ̀n** funfun.

Ní àpẹẹrẹ òkè yìí, **irungbọ̀n** ní láti jẹ́ ọ̀rọ̀-orúkọ, ká ní a kò tilẹ̀ gbọ́ ọ̀rọ̀ náà rí ṣùgbọ́n nítorí pé o gba ọ̀rọ̀-ẹ̀yán **funfun**. Mo tún fẹ́ fi yé ẹ wí pé Arọ́pò orúkọ gígùn tí a mọ̀ sí afarajorúkọ náà lè gba ẹ̀yán o.

## 3.2 Ìpínsísọ̀rí ọ̀rọ̀-orúkọ

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé ọ̀rọ̀-orúkọ kò lóǹkà síbẹ̀, wọ́n ṣeé pínsí oríṣiríṣi ìsọ̀rí pẹ̀lú àwọn àbùdá àdámọ̀ kan. Ẹ jẹ́ ká ṣe àyẹ̀wò díẹ̀ nínú àwọn àbùdá náà.

### 3.2.1 Àbùdá ìhun

Àbùdá ìhunniìpín ọ̀rọ̀-orúkọ sí ìsọ̀rí nípa ìhun rẹ̀. Ìhun tó kéré jù tí ọ̀rọ̀-orúkọ lè ní ni sílébù méjì. Ibẹ̀ gan-an ni a ti máa bẹ̀rẹ̀.

#### 3.2.1.1 Ọ̀rọ̀-orúkọ onisílébù méjì

Àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ onísílébù méjì tún wá pín sí oríṣi méjì. Oríṣi kan ni èyí tí sílébù àkọ́kọ́ jẹ́ fáwẹ̀lì tí sílébù kejì jẹ́ àkànpọ̀ kọ́ńsónáǹtì àti fáwẹ̀lì bó ti hàn ní (8a). Oríṣi kejì ni èyí tí ọ̀kọ̀ọ̀kan sílébù méjì jẹ́ àkànpọ̀ kọ́ńsónáǹtì àti fáwẹ̀lì bó ti hàn ní (8b).

(8) a. òro, olè, ẹmu, ìjì (ò-ro, o-lè, ẹ-mu, ì-jì)
b. kòkó, pákó, pákò, fìlà (kò-kó, pá-kó, pá-kò, fì-là)

### 3.2.1.2 Onisílébù mẹ́ta

Ìsọ̀rí ọ̀rọ̀-orúkọ mìíràn nípa ìhun ni àwọn tí wọ́n jẹ́ sílébù mẹ́ta bó ti hàn ní (9).

(9) a. ọ̀gẹ̀dẹ̀, ewúrẹ́, agbádá, èkùrọ́ (ọ̀-gẹ̀-dẹ̀, e-wú-rẹ́, a-gbá-dá, è-kù-rọ́)
b. pátákó, kòkòrò, garawa (pá-tá-kó, kò-kò-rò, ga-ra-wa)

### 3.2.1.3 Onisílébù bẹ̀ẹ̀rẹ̀

Àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ tí sílébù wọn bá ju mẹ́ta lọ ni a pè ní onísílébù bẹ̀ẹ̀rẹ̀.

(10) a. àgádágodo arigidi àgàbàgebe,
b. à-gá-dá-go-do a-ri-gi-di à-gà-bà-ge-be
c. ọ̀bọsòkòtòtẹnurẹ̀mọ́lẹ̀
ọ̀-bọ-sò-kò-tò-tẹ-nu-rẹ̀-mọ́-lẹ̀
atúwọnkáníbiwọ́ngbéńdánáirọ́
a-tú-wọn-ká-ní-bi-wọ́n-gbé-ń-dá-ná-i-rọ́

### 3.2.1.4 Gbólóhùn àsọdorúkọ

Ìsọ̀rí ọ̀rọ̀-orúkọ kan tún wà tó jẹ́ pé odindi gbólóhùn tí a sọ di ọ̀rọ̀-orúkọ ni wọ́n. Ẹ wo àpẹ̀ẹrẹ ìsàlẹ̀ wọnyí.

(11) Ọládélé < Ọlá dé ilé
Májóyègbé < Má jẹ́ kí oyè gbé
Táyéwò < Tọ́ ayé wò
Málàólú < Mú àlà fún olú
Ajiboye < A jí bá oyè

Báyìí, a ti parí ọ̀rọ̀ lórí ìlò àbùdá ìhun láti ṣe àyẹ̀wò ìpínsísọ̀rí ọ̀rọ̀-orúkọ. Ohun tó kàn ni àbùdá ìtumọ̀.

### 3.2.2 Àbùdá ìtumọ̀

Àbùdá ìtumọ̀ gẹ́gẹ́ bí orúkọ rẹ̀ ni òṣùwọ̀n tí ó gùn lé ìtumọ̀ tí ọ̀rọ̀ ní láti pín àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ sí ẹ̀kajẹ̀ka. Ìlànà yìí ti wà láti ọjọ́ tó ti pẹ́, bí a pè é ní ìlànà àbáláyé, a kò jayò pa. Ẹ jẹ́ ká bẹ̀rẹ̀ sí wò wọ́n lẹ́sẹẹsẹ.

### 3.2.2.1 Ọ̀rọ̀-orúkọ Aṣeékà àti Aláìṣeékà

Ọ̀kan lára àbùdá ìtumọ̀ nièyí tí a lè fi pín ọ̀rọ̀-orúkọ sí ìsọ̀rí aṣeékà àti aláìṣeékà.

**Aṣeékà**
Ọ̀rọ̀-orúkọ aṣeékà ni àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ tí a lè kà ní méní, méjì, mẹ́ta abbl. Apẹẹrẹ irú wọn ni ó wà ní (12).

(12) ìwé, iṣu, ilé, òkúta, ọ̀bẹ abbl.
Àpẹẹrẹ wọn nínú gbólóhùn ló wà nísàlẹ̀

(13) a. Mo ka **ìwé mẹ́ta** tó jẹ mọ́ èdè Yorùbá.
b. Ìyá Àbíbá ra **iṣu mẹ́wàá** fún ìyá ìyàwó rẹ̀.
c. Abíọ́lá kọ́ **ilé mẹ́rin** sí Láfẹ́nwá.
d. **Òkúta méjìlá** dúró fún ẹ̀yà méjìlá ní Ísírẹ́lì.
e. wọ́n bá **ọ̀bẹ méjì** nínú àpò ọ̀daràn náà.

**Aláìṣeékà**
Ọ̀rọ̀-orúkọ aláìṣeékà ni àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ tí a kò lè kà ní méní, méjì, mẹ́ta abbl. Apẹẹrẹ irú wọn ni ó wà ní (14).

(14) yẹ̀pẹ̀, omi, epo

Ọ̀nà tí wọ́n lè gbà sọ wọ́n di kíkà ni kí a lò wọ́n mọ́ ọ̀rọ̀-orúkọ tí a lò bí òṣùwọ̀n b.a. “ìgò”, “garawa”. Wo: “ìgò omi”, “àgbá epo” abbl. Tún wo àwọn àpẹẹrẹ náà nínú gbólóhùn ìsàlẹ̀:

(15) a. **Yẹ̀pẹ̀ ọkọ̀ mẹ̀ta** ni mo fi kọ́ ilé mi.
b. Aláàárù pọn **omi garawa mẹ́fà** ní àárọ̀.

**3.2.2.2 Àrídìmú àti Àfòyemọ̀**

Òdiwọ̀n mìíràn ni èyí tí a lè lò pín ọ̀rọ̀-orúkọ sí ìsọ̀rí nípa bóyá irú ọ̀rọ̀-orúkọ bẹ́ẹ̀ ṣeé dì mú nípa pé à lè risójú àbí èyí tó jẹ́ pé òye nìkan ni a lè fi mọ ọ̀rọ̀-orúkọ bẹ́ẹ̀. Ẹ jẹ́ kí a wo àpẹẹrẹ díẹ̀ nínú irú ọ̀rọ̀-orúkọ ọ̀hún.

**Àrídìmú**
Gẹ́gẹ́ bí orúkọ rẹ̀, ọ̀rọ̀-orúkọ tí a lè pè ní àrídìmú gbọ́dọ̀ jẹ́ èyí tí ènìyàn lè gbá mú tàbí fọwọ́ kàn tí yóò sì lè sọ pé, háà, ohun táa ń sọ nípa rẹ̀ gan-an nìyí. Àbùdá mìíràn tí ọ̀rọ̀-orúkọ ìsọ̀rí yìí ní ni pé wọ́n tún ṣeé fi ojú rí. Àpẹẹrẹ díẹ̀ nínú ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ orúkọ bẹ́ẹ̀ nimo fi hàn nísàlẹ̀ yìí.
igi, ògiri, ọkọ́, owó, ìwé, àga, ọṣẹ, ẹ̀wù, ewúrẹ́, ajá, abbl.

Ẹ jẹ́ ká wáá lo díẹ̀ nínú wọn ní gbólóhùn.

(16) a. Badà gé **igi** náà lulẹ̀
b. Mo fi ara ti **ògiri**.
d. **Ọkọ̀** ń bọ̀!
e. **Owó** tóo fún mi ya.
ẹ Mo ra **ọṣẹ** ìfọṣọ.

Ọ̀kọ̀ọ̀kan ọ̀rọ̀-orúkọ inú gbólóhún wọ̀nyẹn ló ní àbùdá pé wọ́n ṣeé fọwọ́ kàn, wọ́n sì ṣeé fojú rí

**Àfòyemọ̀**:
Ní ìdàkejì ẹ̀wẹ̀, ọ̀rọ̀-orúkọ àfòyemọ̀ (à-fi-òye-mọ̀) jẹ́ irúfẹ́ ọ̀rọ̀-orúkọ tí a kò lè fi ọ́wọ́ kàn tàbí fi ojú warí. Òye tàbí ọgbọ́n inú nìkan ni a fi máa ń gbe láti mọ ohun tí a ń sọ nípa rẹ̀. Àpẹẹrẹ ọ̀rọ̀-orúkọ ìsọ̀rí yìí náà pọ̀ jáǹtìrẹrẹ. Díẹ̀ nínú wọn nìyí:

afẹ́fẹ́, ìfẹ́, ìnira, oró, ikú, ìyè, ọ̀rọ̀, ọ̀tẹ̀, òfófó, ọ̀lẹ

Ẹ wo ìlò wọn nínú gbólóhùn ìsàlẹ̀

(17) a. **Ìfẹ́** rẹ ń pa mí bí ọtí.
b. Ikú dá **oró**.
d. Afẹ́fẹ́ ń fẹ́.
e. Wọ́n di ọ̀tẹ̀ mọ́ ọkọ Ẹ̀bùn.
ẹ Olú ṣe **òfófó** fún olùkọ́ pé Ṣadé jí ìwé rẹ̀.

Bí obá wo gbólóhùn (17a), ó máa yé ẹ pé bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé a ṣe àfiwé **ìfẹ́** pẹ̀lú **ọtí**, tí ọtí sì ṣeé fojú rí, síbẹ̀ a kò lè sọ pàtó ìrísí **ìfẹ́** fúnra rẹ̀. Bí ọ̀rọ̀ ṣerí fún gbogbo ọ̀rọ̀-orúkọ ìsọ̀rí yìí.

**3.2.2.3 Ọ̀rọ̀-orúkọ ènìyàn àti ẹranko**

Ìpínrọ̀sísọ̀rí mìíràn ni èyí tó gùn lé bóyá ọ̀rọ̀-orúkọ jẹ́ tàbí tọ́ka sí ènìyàn tàbí ẹranko. Àpẹẹrẹ wọn ló wà nísàlẹ̀ yìí.

(18) a. **ènìyàn**: ọkùnrin, obìnrin, ọmọ,
b. **ẹranko**: ajá, ewúrẹ́, kìnìhún, erin,

**3.2.2.4 Ọ̀rọ̀-orúkọ Ibi àti Ohun**

Ìsọ̀rí mìíràn ni èyí tó pín ọ̀rọ̀-orúkọ sí ibìkan tàbí ohun kan pàtó. Àpẹẹrẹ wọn ló wà ní (19a & b).

(19) a. Ibi: Èkó, ọjà, aginjù, ààfin, Mọ́níyà
b. Ohun: ilé, àdá, ìkòkò, apẹ̀rẹ̀, ìbọn

Àpẹẹrẹ wọn nínú gbólóhùn nìyí:

(20) a. **Èkó** ni mo ń gbé.
Wọ́n gba àlejò náà sí **ààfin**.
**Ọjà** ọba jìnnà sí **Mọ́níyà**.

b. **Ìkòkò** ringindin kò gbọdọ̀ fọ́.

Ògúndélé fi **ìbọn** rẹ̀ pa òdù ọ̀yà
**Apẹ̀rẹ̀** ni Mo fi kó iṣu.

### 3.2.2.5 Ọ̀rọ̀-orúkọ àìṣẹ̀dá àti àṣẹ̀dá

Ìsọ̀rí mìíràn tí a tún lè pín ọ̀rọ̀-orúkọ sí ni ká wò ó bóyá irú ọ̀rọ̀-orúkọ bẹ́ẹ̀ jẹ́ ọ̀rọ̀ ìpìlẹ̀ (àìṣẹ̀dá) tàbi èyí tí aṣẹ̀dá. Àwọn ọ̀rọ̀ ìpìlẹ̀ ni ọ̀rọ̀-orúkọ tí a kò ṣẹ̀dá. Tí a bá gbìyànjú láti pín àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ bẹ́ẹ̀ sí wẹ́wẹ́, ó kéré tán, ọ̀kan nínú wọn kò lè dá ìtumọ̀ ní. Àpẹẹrẹ ọ̀rọ̀-orúkọ ìpìlẹ̀ ló wà ni (21a), nígbà tí àpẹẹrẹ ọ̀rọ̀-orúkọ tí a ṣẹ̀dá wà ni (21b).

(21) a. *ọ̀rọ̀-orúkọ ìpìlẹ̀*: owó, iṣẹ́, ewúrẹ́, òkúta, igi
b. *ọ̀rọ̀-orúkọ àṣẹ̀dá*: ọ̀bẹ, aṣẹ́, ìfẹ́, ewébẹ̀, oníṣu

Láti fi hàn pé a ṣẹ̀dá àpẹẹrẹ (21b), e wo ìtúpalẹ̀ wọn ní (22).

(22) *ìtúpalẹ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ àṣẹ̀dá*: ọ̀-bẹ, a-ṣẹ́, ì-fẹ́, ewé-(ọ)bẹ̀, o-ní-(i)ṣu

Lẹ́tà àkọ́kọ́ ni a ń pè ní mọ́fíìmù afarahẹ lábala ẹ̀ka ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè tí a mọ̀ sí mofọ́lọ́jì.

### 3.2.2.6 Wúnrẹ̀n aṣegírámà aṣorúkọ ìbéèrè

Ìsọ̀rí ọ̀rọ̀-orúkọ wúrẹ̀n aṣegírámà ni àwọn wúnrẹ̀n tí a fi ń dípò ọ̀rọ̀-orúkọ tàbí àpólà-orúkọ nígbà tí a bá fẹ́ ṣe ìbéèrè nípa wọn. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé a ti sọ ṣáájú lókè wí pé àbùdá ọ̀rọ̀-orúkọ tó kéré jù ni onísílébù méjì, kì í ṣe gbogbo ìgbà ni ọ̀rọ̀ rí báyìí. Kìkì ojúlówó ọ̀rọ̀-orúkọ tó lè dá dúró tó máa fún wa ní ìtumọ̀ kíkún ni àbúdá yẹn jẹ mọ́. Ẹ wo àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀.

(23) ta, kí, èwo, ibo,

Àrídájú ohuntí a sọ lókè ló wà ní (24) yìí.

(24) a. **Adé** ra **ọkọ̀ pupa** ni **Ojúẹlẹ́gba**.
b. (i) Ta ni o ra **ọkọ̀ pupa** ni **Ojúẹlẹ́gba**?
(ii) Kí ni **Adé** ra ni **Ojúẹlẹ́gba**?
(iii) **Ibo** ni **Adé** ti ra **ọkọ̀ pupa**?

"ta" ni ó ṣe ìbéèrè nípa "Adé", "kí" ni ó ṣe ìbéèrè nípa "ọkọ̀ pupa" nígbà tí "ibo" ṣe ìbéèrè nípa "ojúẹlẹ́gba" tí Adé ti ra ọkọ̀. Àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ bí "ta" àti "kí" kò dá ìtumọ̀ ní fúnra wọn.

## 4.0 ÌGÚNLẸ̀

A ti ṣe àyẹ̀wò kíkún lórí ọ̀rọ̀-orúkọ, oríkì rẹ̀ àti ọ̀kanòjọ̀kan ìsọ̀rí tí a lè pín in sí.

## 5.0 ISỌNÍSÓKÍ

Ní Modúù kìíní, Ìpín kìíní, a ṣe iṣẹ́ lórí ọ̀kan lára ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ tí a lè pín ọ̀rọ̀ Yorùbá sí. Èyí tí a gbé yẹ̀wò ni ọ̀rọ̀-orúkọ. A bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú oríṣiríṣi oríkì tí a lè fún ọ̀rọ̀-orúkọ. Lẹ́yìntí a ṣeèyí tánni a bọ́ sí abala ìpínsísọ̀rí àwọ̀n ọ̀rọ̀-orúkọ pẹ̀lú àwọn ọ̀kanòjọ̀kan àbùdá bíi ìhun onísílébù kan, onísílébù

méjiabbl., àbùdá ìtumọ̀ èyí tó fún wa ní ọ̀rọ̀-orúkọ to ṣeé kà àti èyí tí kò ṣeé kà,

## 6.0 IṢẸ́ ÀYÀNṢEONÍMÁÀKÌ OLÙKỌ́

1. Kí ni ọ̀rọ̀-orúkọ?
2. Darúkọ ìsọ̀rí méjì nínú ìsọ̀rí tí ọ̀rọ̀-orúkọ lè ní kí o sì fún wa ní àpẹẹrẹ márùn-ún márùn-ún lábẹ́ ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan.
3. Irú ìsọ̀rí wo niìkọ̀ọ̀kanọ̀rọ̀ orúkọ wọ̀nyí: epo, iyọ̀, àtùpà, àlàáfíà, Ìkẹjà wà?
4. Lo àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ wọ̀nyí nínú gbólóhùn ara rẹ: àdá, ìlera, ọ̀tẹ̀, ayé, òtútù.
5. Kí ni ìyàtọ̀ tó wà láàrín ọ̀rọ̀-ìṣe àfòyemọ̀ àti àrídìmú?

## 7.0 ÀWỌNÌWÉ FÚNKÍKÀ

Yàtọ̀ sí àkóonú abala-ẹ̀kọ́ yìí, mo rọ̀ ẹ́ láti ka àwọn ìwé-àkànlò tí a yàn fún yín pẹ̀lú àwọn èròjà tí a ti tọ́ka yínsí. Kíka àwọn ìwé miíràn máa ràn ẹ́ lọ́wọ́ láti lè ṣe iṣẹ́ àyànṣe. Pabanbarì rẹ̀ ni pé èyí máa jẹ́ kí ẹ lè yege nípa èròǹgbà abala-èkọ́ yìí.

Awobuluyi, Oladele (1978). *Essentials of Yoruba Grammar*. UPL. Oxford University Press, Ibadan.Orí 1.

Awobuluyi, Oladele (2013). *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá.* ATMAN Limited. Osogbo. Orí 1, o.i. 17-51.

Bámgbóṣé, Ayọ̀. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Orí 15, o.i. 95-117.

Yusuf, Ọre. (1995). *Gírámà Àkọ̀tun Yorùbá*. o.i. 10-11.

# ÌPÍN 2 ARỌ́PÒ-ORÚKỌ

## Àkóónú

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
  3.1 OríkìArọ́pò-orúkọ
  3.2 Ìpínsísọ̀rí Arọ́pò-orúkọ
    3.2.1 Arọ́pò-orúkọ kúkúrú
    3.2.2 Arọ́pò-orúkọ gígùn
    3.2.3 Arọ́pò-orúkọ ara ẹni
4.0 Ìgúnlẹ̀
5.0 Isọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Àyànṣe Onímáàkì Olùkọ́
7.0 Àwọn Ìwé Fún Kíkà

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ní ìpín (1), mo wo ọ̀rọ̀-orúkọ pọ́ńbélé. Ní ìpín yìí, ohuntí mo pète láti ṣe ni àgbéyẹ̀wò arọ́pò-orúkọ àti oríṣiríṣi ìsọ̀rí tí a lè pín wọn sí.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ

Èròǹgbà ìpín yìí ni kí a ṣe àlàyé wẹ́lẹ́wẹ́lẹ́ lọ́nà tó máa yéni yékéyéké ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ tí a mọ̀ sí arọ́pò-orúkọ lọ́nà tí ó máa fi rọrùn fún akẹ́kọ̀ọ́ láti lè dá arọ́pò-orúkọ mọ̀ nínú gbólóhùn kí ó sì lè ṣe ìpínsísọ̀rí wọn.

## 3.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Àkóónú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìpín yìí ṣe àyẹ̀wò arọ́pò-orúkọ, oríkì tí a lè fun, ọ̀kanòjọ̀kan ọ̀nà tí a lè pín arọ́pò-orúkọ sí pẹ̀lú àbùdá tí ènìyàn lè lò pín wọn sí ìsọ̀rí. A tẹ̀síwájú láti ṣe ìgúnlẹ̀ àti ìsọníṣókí ohun tí a ti gbé ṣe. Lẹ́yìn náà ni a ṣe àgbékalẹ̀ iṣẹ́ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ àti àfihàn ìwé ìtọ́kasí tó lè wúlò fún akẹ́kọ̀ọ́ láti fi kún ìmọ̀ wọn.

Ìsọ̀rí pàtàkì kan ni arọ́pò-orúkọ jẹ́ lédè Yorùbá gẹ́gẹ́ bí ti àwọ nèdè mìíràn lágbàáyé. Àsomọ́ tó gbópọn sì wà láàárin ọ̀rọ̀-orúkọ àti arọ́pò-orúkọ. A ó bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ lórí ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ yìí pẹ̀lú oríkì rẹ̀.

### 3.1 OríkìArọ́pò-orúkọ

Gẹ́gẹ́ bí orúkọ rẹ̀, arọ́pò-orúkọni a lè lò dípò ọ̀rọ̀-orúkọ tàbí àpólà-orúkọ. Ìyẹn ni wí pé, ibikíbi tí a bá ti lè rí ọ̀rọ̀-orúkọ, a lè rí arọ́pò-orúkọ níbẹ̀ pẹ̀lú. Jẹ́ kí n fún ẹ ní àpẹẹrẹ.

(1) a. **Adé** jẹ **iṣu**.
b. **Ó** jẹ iṣu.
d. Adé jẹ **ẹ́**.

Ní (1b.), "ó" ni ó rọ́pò "Adé" ṣùgbọ́n ní (2d), "ẹ́" ni ó rọ́pò "iṣu".

Gẹ́gẹ́ bí o ti máa ri ní ìsàlẹ̀, nípa ìhun, oríṣi arọ́pò-orúkọ méjì ló wà; àwọn ni arọ́pò-orúkọ kúkúrú àti arọ́pò-orúkọ gígùn fẹ́ẹ́. Mo ṣe àlàyé ṣókí lórí arọ́pò-orúkọ gígùn àti kúkurú lọ́tọ̀ọ̀tọ̀. Ṣùgbọ́n kí n̄ tó ṣe bẹ́ẹ̀, mo fẹ́ pe àkíyèsí rẹ sí ohun kan kí n̄ sì ṣe àfihàn rẹ̀ kí n̄ tó tẹ̀síwájú. Ohun náà niwí pé àwọn oríṣi arọ́pò-orúkọ méjì ní àwọn àbùdá kan tó pa wọ́n pọ̀ gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn nísàlẹ̀.

Àbùdá tí a fi lè dá arọ́pò-orúkọ lápapọ̀ mọ̀.

a. wọ́n lè jẹ́ gígùn tàbí kúkúrú
b. wọ́n lè tọ́ka sí ẹni: ẹnì kìíní, ẹnìkejì, ẹnìkẹ́ta
d. wọ́n lè tọ́ka sí ẹyọ tàbí ọ̀pọ̀
e. wọ́n lè wà ní ipò olùwà tàbí àbọ̀
ẹ wọ́n lè ṣeiṣẹ́ ìní

Màá tẹ̀síwájú nípa ṣíṣe àlàyé arọ́pò-orúkọ kúkúrú ní ẹ̀kún rẹ́rẹ́.

## 3.2 Ìpínsísọ̀rí Arọ́pò-orúkọ

Ìsọ̀rí mẹ́ta pàtàkì ni a lè pín arọ́pò-orúkọ sí. Ìsọ̀rí mẹ́ta náà ni: arọ́pò orúkọ kúkúrú, arọ́pò-orúkọ gígùn àti arọ́pò-orúkọ ara ẹni.

### 3.2.1 Arọ́pò-orúkọ kúkúrú

Arọ́pò-orúkọ kúkúrú ni àwọn arọ́pò-orúkọ tí ìhun wọn jẹ́ sílébù kan péré; b.a. **mo, o, ó, a, ẹ, wọ́n**. Ohun tí mo sọ yìí ṣe déédé pẹ̀lú àbùdá àkọ́kọ́, ìyẹn ni wí pé gbogbo arọ́pò-orúkọ kúkúrú ló jẹ́ pé sílébù kọ̀ọ̀kan ni wọ́n, bí ó ti hàn lókè.

Àbùdá mìíràn ni wí pé wọ́n lè tọ́ka sí ẹnìkíní, ìyẹn olùsọ̀rọ̀; wọ́n lè tọ́ka sí ẹnìkejì, ìyẹn olùgbọ́; wọ́n sì lè tọ́ka sí ẹni tàbí ohun tí kò sí ní sàkáni olùsọ̀rọ̀ tàbí olùgbọ́. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà ni arọ́pò-orúkọ bẹ́ẹ̀ máa ń jẹ́ ẹni tàbí ohun tí a ń sọ nípa rẹ̀. Yàtọ̀ sí èyí, wọ́n tún lè jẹ́ ẹyọ tàbí ọ̀pọ̀. Àbùdá méjì yìí nimo fi hàn nínú àtẹ ìsàlẹ̀.

Àtẹ I: *Arọ́pò-orúkọkúkúrú*

| *Ẹni* | *Olùwà* | | *Àbọ̀* | |
|---|---|---|---|---|
| | Eyọ | Ọ̀pọ̀ | Eyọ | Ọ̀pọ̀ |
| Ẹni Kìíní | mo | a | mo | mi |
| Ẹni Kejì | o | ẹ | o | ẹ/ẹ́ |
| Ẹni Kẹta | ó | wọ́n | ó | F |

Àfihàn àwọn arọ́pò-orúkọ kúkúrú ní ipò olùwà nínú gbólóhùn nìyí.

(2) a. **Mo** rí òkú olè náà ní ojú ọjà.
b. **O** rí òkú olè náà ní ojú ọjà.
d. **Ó** rí òkú olè náà ní ojú ọjà.
e. **A** rí òkú olè náà ní ojú ọjà.
ẹ. **Ẹ** rí òkú olè náà ní ojú ọjà.
f. **Wọ́n** rí òkú olè náà ní ojú ọjà.

Ohun tó kàn ni kí a wo àpẹẹrẹ arọ́pò orúkọ tó wà ní ipò àbọ̀.

(3) a. Adé rí **mi.**
b. Adé rí **ẹ/ọ.**
d. Adé rí **i.**
e. Adé rí **wa.**
ẹ. Adé rí **yín.**
f. Adé rí **wọn.**

Àbùdá mìíràn ni wí pé, arọ́pò-orúkọ kúkúrú lè ṣe iṣẹ́ ìní.

Àtẹ II: *Arọ́pò-arọ́pò kúkúrú gẹ́gẹ́ bí olóhun*

| *Ẹni* | *Ìní* | |
|---|---|---|
| | Eyọ | Ọ̀pọ̀ |
| Ẹnì Kìíní | ì-mi | i-wa |
| Ẹnì Kejì | ì-rẹ | i-yín |
| Ẹnì Kẹta | i-rẹ̀ | i-wọn |

Ẹ jẹ́ kí a wo ìjẹyọ wọn nínú àpólà orúkọ.

(4) a. igi ì-mi
b. igiì-rẹ
d. igi ì-rẹ
e. igi i-wa
ẹ igi i-yín
f. igi i-wọn

Ní ìparí, a fẹ́ wo ọ̀rọ̀-arọ̀pò orúkọ olóhun nínú gbólóhùn. Àpẹẹrẹ wọn ló wà ní (4).

(5) *Arọ́pò-orúkọ kúkúrú gẹ́gẹ́ bí mọ́fíìmù olóhun*
a. Adé rí aṣọ **ọ̀-mi**
b. Adé rí ilé **è-rẹ**
d. Adé rí owó **o-rẹ̀**
e. Adé rí ẹsẹ̀ **ẹ-wa**
ẹ. Adé rí ajá **a-yín**
f. Adé rí ẹ̀wù **u-wọn**

Ṣe àkíyèsí wí pé nínú àkọtọ́, a kì í ṣe àfihàn fáwẹ́lì ìní bí ó ti hàn nínú àpẹẹrẹ òkè wọ̀nyẹn.

### 3.2.2 Arọ́pò-orúkọ gígùn

Arọ́pò orúkọ gígùn gẹ́gẹ́ bí orúkọ rẹ̀, ni arọ́pò orúkọ tí ó ní sílébù méjì yàtọ̀ sí arọ́pò-orúkọ kúkúrú tó jẹ onísílébù kan. Ìyẹn ni wí pé, gígùn rẹ̀ní àwòmọ́ akẹgbẹ́ rẹ̀ tó jẹ́ onísílébù kan. A ó tún fi hàn nísàlẹ̀ wí pé àjọṣepọ̀ tó níí ṣe pẹ̀lú mofọ́lọ́jì wà láàárín oríṣi arọ́pò orúkọ méjì náà. Arọ́pò orúkọ gígùn yìí kan náà ni a mọ̀ sí afarajórúkọ.

**Àbùdá arọ́pò-orúkọ gígùn**

a. wọ́n lè tọ́ka sí ẹni bí: ẹnìkìíní, ẹnìkejì, ẹnìkẹ́ta
b. wọ́n lè tọ́ka sí ẹyọ tàbí ọ̀pọ̀
d. wọ́n lè wà ní ipò olùwà tàbí àbọ̀
e wọ́n lè gba ọ̀rọ̀-ẹ̀yán
ẹ wọ́n ṣeé so pọ̀ mọ́ arawọ̀ntàbí ọ̀rọ̀-orúkọ

Gẹ́gẹ́ bí ti arọ́pò-orúkọ kúkúrú, àfihàn arọ́pò-orúkọ gígùn lè wà nípò ẹni àti ipò olùwà tàbí àbọ̀.

Mo fẹ́ẹ́ wá fi wọ́n hàn lórí àtẹ̀ ìsàlẹ̀.

Àtẹ III: *Arọ́pò-orúkọ gígùn*

| *Ẹni* | *Olùwà* | |
|---|---|---|
| | Eyọ | Ọ̀pọ̀ |
| Ẹni Kìíní | èmi | àwa |
| Ẹni Kejì | ìwọ | ẹ̀yin |
| Ẹni Kẹta | òun | àwọn |

Lẹ́yìn tí mo ti fi wọ́n hàn lórí àtẹ, ohun tó kù ni kí n̄ fi wọ́n nínú ìlò bó ti wà ní (6).

(6) *Arọ́pò-orúkọ gígùn nípò Olùwà*
a. **Èmi** rí òkú olè náà ní ojú ọjà.
b. **Ìwọ** rí òkú olè náà ní ojú ọjà.
d. **Òun** rí òkú olè náà ní ojú ọjà.
e. **Àwa** rí òkú olè náà ní ojú ọjà.
ẹ. **Ẹ̀yin** rí òkú olè náà ní ojú ọjà.
f. **Àwọn** rí òkú olè náà ní ojú ọjà.

Arọ́pò-orúkọ gígùn ní ipò àbọ̀ kò fi bẹ́ẹ̀ wọ́pọ̀ nínú ìpèdè ojoojúmọ̀; síbẹ̀, ó ṣeé ṣe kó wáyé. Ẹ jẹ́ kí a wo àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí.

(7) Arọ́pò-orúkọ gígùn ní ipò àbọ̀
a. Adé na **èmi** (ó fi Olú sílẹ̀**).**

b. Adé na **ìwọ** (ó fi Olú sílẹ̀).
d. Adé na **òun** (ó fi Olú sílẹ̀).
e. Adé na **àwa** (ó fi Olú sílẹ̀).
ẹ. Adé na **ẹ̀yin** (ó fi Olú sílẹ̀).
f. Adé na **àwọn** (ó fi Olú sílẹ̀).

Àkíyèsí pàtàkì kan ni wí pé, a kì í sábà rí arọ́pò orúkọ ní ipò àbọ̀; kìkì ìgbà tí a bá fẹ́ẹ́ ṣe ìtẹnumọ́ ni a máa ń rí arọ́pò orúkọ gígùn ní ipò àbọ̀. Ìyẹn ni wí pé kò fẹ́rẹ̀ẹ́ sí ìyàtọ̀ ìtumọ̀ láàárín (7) àti (8) ìsàlẹ̀. Àkíyèsí mìíràn ni wí pé, arọ́pò-orúkọ gígùn ní ipò àbọ̀ kì í paradà bí ọ̀gà. Èyí dáa yà sọ́tọ̀ sí arọ́pò-orúkọ kúkúrú tó jẹ́ wí pé ìrísí rẹ̀ ní ipò olùwà àti àbọ̀ kì í ṣe bákan náà.

Arọ́pò-orúkọ gígùn ní ipò ìtẹnumọ́.
(8) a. **Èmi** niAdé na… (ó fi Olú sílẹ̀).
b. **Ìwọ** ni Adé na…
d. **Òun** ni Adé na…
e. **Àwa** ni Adé na…
ẹ. **Ẹ̀yin** ni Adé na…
f. **Àwọn** ni Adé na…

Yàtọ̀ sí ohun tí a ti mẹ́nu bà lókè, arọ́pò-orúkọ gígùn náà lè wà ní ipò olóhun. Nígbàkúgbà tí arọ́pò-orúkọ gígùn bá wà ní ipò yìí, mọ́fìmù ìní kìí ṣú yọ.

(9) *Arọ́pò-orúkọ gígùn gẹ́gẹ́ bí olóhun*
a. Adé rí aṣọ **èmi**
b. Adé rí ilé **ìwọ**
d. Adé rí owó **orẹ̀**
e. Adé rí ẹsẹ̀ **àwa**
ẹ. Adé rí ajá **ẹ̀yín**
f. Adé rí ẹ̀wù **àwọn**

Ní ìparí, àbùdá kan pàtàkì tí arọ́pò gígùn tí a tún mọ̀ sí arọ́pò afarajorúkọ fi gba orúkọ yìí ni wí pé ìṣe àti ìwà rẹ̀ fara jọ ọ̀rọ̀-orúkọ nípa pé, gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀-orúkọ, ó lè gba ẹ̀yán (10).

(10) a. Èmi **Ọládiipọ̀** mọ̀ pé olè ni ẹ́.
b. Ìwọ **radaràda yìí** kò mọyì mi.
d. Òun **oníwàtútù bí àdàbà** rí àànú gbà.
e. Àwa **tí a jẹ́ akọni** jẹ́ méje.
ẹ. Ẹ̀yin **àgbà ìyà** jẹ àjẹjù níbi ìnáwó àbúrò yín.
f. Àwọn **ọmọ Ìlálẹ̀** mọ ẹ̀tọ́ púpọ̀.

Àkíyèsí wa ni wí pé oríṣiríṣi ẹ̀yán ni arọ́pò-orúkọ gígùn lè gbà, gẹ́gẹ́ bí a ti fi hàn nínú àwọn àpẹẹrẹ òkè.

Ní ìparí, àbùdá kan pàtàkì tó tún mú kí arọ́pò-orúkọ gígùn gba orúkọ yìí ni wí pé a lè fi ọ̀rọ̀-asopọ̀ so ó pọ̀ mọ́ ọ̀rọ̀-orúkọ mìíràn (11).

(11) a. **Ọládiipọ̀** àti **èmi** mọ̀ pé olè ni ẹ́.
b. **Ìwọ** àti **ọmọ radaràda yìí** kò mọyì mi.
d. **Òun**àti**Bọ́lá oníwàtútù bí àwàdà**rí àánú gbà.
e. **Ọkùnrin** náà **àwa** àti fi ìjà pẹ́ẹ̀ta.
ẹ. **Ẹ̀yin** àti **àgbà ìyà yẹn** jẹ àjẹjù níbi ìnáwó àbúrò yín.
f. **Àwọn** àti **ọmọ ìlú Àjọwá** parí ìjà.

Àjọni ni arọ́pò-orúkọ gígùn fi àbùdá yìí ṣe pẹ̀lú ọ̀rọ̀-orúkọ. Ṣe àkíyèsí wí pé a lè so arọ́pò-orúkọ wọ̀nyí pọ̀ pẹ̀lú ọ̀rọ̀-orúkọ pọ́ńbélé tàbí àpólà orúkọ. Ó tún ṣeé ṣe kí a so arọ́pò afarajorúkọ méjì nìkan pọ̀ (12).

(12) a. **Èmi** àti **òun** mọ̀ pé olè ni ẹ́.
b. **Ìwọ** àti **àwa** kò mọyì aìníyàá.
d. **Òun** àti **ìwọ** rí àánú gbà.
e. **Àwa** pẹ̀lú **ẹyin** ni wọ́n ní kó wá ni àgọ́ ọlọ́pàá.
ẹ. **Ẹ̀yin** àti **èmi** ni Kúnlé bú bí ẹní láyin.
f. **Àwọn** àti **ẹ̀yin** kò mọ ẹ̀tọ́.

### 3.2.3 Arọ́pò-orúkọ ara ẹni

Ìsọ̀rí arọ́pò-orúkọ kan tún wà tí a mọ̀ sí arọ́pò-orúkọ ara ẹni. Gẹ́gẹ́ bí ti arọ́pò-orúkọ tí a ti wò ṣáájú, mẹ́fà ni àwọn náà, wọ́n ní àbùdá ẹni, wọ́n sì ní àbùdá iye, bóyá ẹyọ tàbí ọ̀pọ̀. Àfihàn wọn ló wà nínú àtẹ IV.

Àtẹ IV: *Arọ́pò-orúkọ ara ẹni*

| *Ẹni* | *Olùwà* | |
|---|---|---|
| | Eyọ | Ọ̀pọ̀ |
| Ẹni Kìíní | ara à mi | ara a wa |
| Ẹni Kejì | ara à rẹ | ara a yín |
| Ẹni Kẹta | ara à rẹ̀ | ara a wọn |

Gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn nínú àtẹ òkè, mọ́fíìmù mẹ́ta ló ń parapọ̀ ṣe arọ́pò-orúkọ ara ẹni ṣùgbọ́n nínú àkọtọ́, a máa ń kọ wọ́n pọ̀ ni.
Àbùdá kan pàtàkì tí arọ́pò-orúkọ ẹni dá ní ni wí pé kìkì ipò àbọ̀ ló máa ń wà, ìyẹn ni wí pé a kò lè lo èyíkéyìí wọn ní ipò olùwà rárá.

(13) a. Mo rí **araàmi** nínú díńgí.
b. Yéèpà ọmọ yìí pa **araàrẹ**.
d. Ènìyàn ṣe **araarẹ̀**, ó ní ayé ń ṣe òun.
e. A kó **araawa** sínú ìyọnu nípa ìwà òmùgọ̀ tí a hù.
ẹ. Ìwọ àti ìyá rẹ wulẹ̀ ń bínú **araayín** lásán.
f. Táyé àti Kẹ́hìndé fẹ́ràn **araawọn** dé góńgó.

Ó tún ku ohun kan pàtàkì tí a lè sọ nípa arọ́pò-orúkọ ara ẹni. Ohun náà ni wí pé, gẹ́gẹ́ bí ti arọ́pò-orúkọ tó kù, àwọn náà lè ṣe iṣẹ́ ẹ̀yán.

(14) a. Aṣọ **araàmi** ni mo fà ya.
b. Ọmọ **araàrẹ** ló kó bá ẹ.
d. Iṣẹ́ ọwọ́ **araarẹ̀** ló ṣe ikú pa á.
e. Wọ́n wó ilé tí a fi ọwọ́ **araawa** kọ́.
ẹ Ẹ kọ ìlú **araayín** sílẹ̀, ẹ lọ ń tún ìlú onílùú ṣe.
f. Wọ́n fi ọwọ́ **araawọn** ṣe araawọn.

## 4.0 ÌGÚNLẸ̀

Mo ti ṣe àyẹ̀wò fínnífínní nípa ọkọ̀ọ̀jọ̀kan arọ́pò-orúkọ lédè Yorùbá.

## 5.0 ISỌNÍSÓKÍ

Mo bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ ìpín yìí pẹ̀lú èròǹgbà mi nípaiṣẹ́ náà, mosì taraṣàṣà fúnarọ́pò-orúkọ ní oríkì. Lẹ́yìnnáà ni mow á wo arọ́pò-orúkọ lábẹ́ ìsọ̀rí mẹ́ta pàtàkì: arọ́pò orúkọ kúkúrú, arọ́pò-orúkọ gígùnàtiarọ́pò-orúkọ araẹni. motẹ̀síwájú láti fi yé ẹ orísìrísìàbùdá àdániarọ́pò-orúkọ lápapọ̀, kí n tó wá máa wò wọ́n ní ọ̀kọ̀ọ̀kan pẹ̀lú àlàyé ṣókí ṣókí pẹ̀lú àpẹẹrẹ tó pójú owó.

## 6.0 IṢẸ́ ÀYÀNṢE ONÍMÁÀKÌ OLÙKỌ́

1 a. Kí ni arọ́pò-orúkọ?
b. Kí ni àbùdá arọ́pò-orúkọ?
2. Kí ni àbùdá ọ̀pọ̀ ń sọ fún wa nípa arọ́pò-orúkọ?
3. Ìjọra àti ìyàtọ̀ wo láàárín arọ́pò-orúkọ olóhun àti arọ́pò-orúkọ ara ẹni?
4. Ṣe àlàyé àwọn arọ́pò-orúkọ wọ̀nyí pẹ̀lú àwọn àbùdá àdáni wọn: àwa, a, mi, òun.
5. Ya àtẹ̀ arọ́pò-orúkọ kúkúrú to fi wọ́n hàn ní ipò olùwà àti àbọ̀.

## 7.0 ÀWỌN ÌWÉ FÚN KÍKÀ

Awobuluyi, Oladele (1978). *Essentials of Yoruba Grammar*. UPL. Oxford University Press, Ibadan. Orí 1.

Awobuluyi, Oladele (2013). *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá.* ATMAN Limited. Osogbo. Orí 1, o.i. 17-51, o.i. 26-37.

Bámgbóṣé, Ayọ̀. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Orí 15, o.i. 113-117.

Yusuf, Ọre. (1995). *Gírámà Àkọ̀tun Yorùbá*. o.i. 10-11.

# ÌPÍN 3 ỌRỌ̀-ẸYÁN

## Àkóónú

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́: Ọ̀rọ̀-ẹ̀yán
3.1 Oríkì ẹ̀yán
3.2 Ìpińsísọ̀rí ọ̀rọ̀-ẹ̀yán
3.2.1 Ẹ̀yán Aṣàpèjúwe
3.2.2 Ẹ̀yán Ajórúkọ
3.2.3 Ajẹmáwọ̀
3.2.4 Ẹ̀yán Ajẹmọ́ṣe
3.2.5 ẸyánAsọye
3.2.6 ẸyánAṣàfihàn
3.2.7 Ẹ̀yán Awẹ́ gbólóhùn
4.0 Ìgúnlẹ̀
5.0 Isọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Àyànṣe Onímáàkì Olùkọ́
7.0 Àwọn Ìwé fún Kíkà

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìpín yìí máa bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú oríkì tí a lè fún ọ̀rọ̀-èyán, lẹ́yìn náà ni mo tẹ̀síwájú pẹ̀lú àwọn ìsọ̀rí tí a lè pín ọ̀rọ̀-ẹ̀yán sí. Lẹ́yìn náà ni màá ṣe ìgúnlẹ̀ àti ìsọnísókí ohun tí iṣẹ́ ìsọ̀rí náà dálé.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ

Èròǹgbà iṣẹ́ ìpín yìí nikí a lè jẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ ní òye kíkún àti ìmọ̀ tó gbòòrò nípa ohun tí a ń pè ní ọ̀rọ̀-ẹ̀yán nínú gbólóhùn.

## 3.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́: Ọ̀RỌ̀-Ẹ̀YÁN

Ohun àkọ́kọ́ ni kí n̄ fún ọ̀rọ̀-ẹ̀yánní oríkì tó péye lẹ́yìn náà ni mà á tẹ̀síwájú láti pín ẹ̀yán sí ìsọ̀rí ìsọ̀rí.

### 3.1 Oríkì ẹ̀yán

Ọ̀rọ̀-ẹ̀yán ni ọ̀rọ̀kọ́rọ̀ tí ó wà ní sàkání ọ̀rọ̀-orúkọ tó lè jẹ́ kí a túbọ̀ ní òye kíkún nípa irú ọ̀rọ̀-orúkọ bẹ́ẹ̀; kódà, ó máa ń dín ìtùmọ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ bẹ́ẹ̀ kù nípa títúbọ̀ tan ìmọ́lẹ̀ sí àwọn àbùdá kan pàtó tí ó ní; b.a. **funfun** bí ò ti hàn nínú àpólà orúkọ: **ajá funfun**.

## 3.2 Ìpińsísọ̀rí ọ̀rọ̀-ẹ̀yán

Gẹ́gẹ́ bí ti ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ tó kù, ọ̀rọ̀-ẹ̀yán náà ṣeé pín sí ọ̀kan-ò-jọ̀kan ìsọ̀rí bí a ó ti fi hàn ní sísẹ̀ntẹ̀lé nísàlẹ̀ yìí. Àmọ́ sáá, ó ṣeé ṣe kí ọ̀rọ̀-ẹ̀yán kan wà ní ìsọ̀rí méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ.

### 3.2.1 Ẹ̀yán Aṣàpèjúwe

Ìsọ̀rí kan pàtàkì ni ọ̀rọ̀-ẹ̀yán aṣàpèjúwe jẹ́. Ẹ̀yán aṣàpèjúwe ló lè jẹ́ ká mọ ìrísí ọ̀rọ̀-orúkọ kan bóyá nínú àpólà orúkọ tàbí gbólóhùn b.a. dúdú, gíga, ńlá.

(1) a. Ọdẹ ra ajá **dúdú**.
    b. Mo kọ́ ilé **gíga**.
    d. Aláàárù ruẹrù **ńlá**.

### 3.2.2 Ẹ̀yán Ajórúkọ

Ọ̀rọ̀-ẹ̀yán ajórúkọ ni àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ tí a lò láti ṣe iṣẹ́ ẹ̀yán. Ohun tí èyí túmọ̀ sí ni wí pé kò sí ọ̀rọ̀-orúkọ tí kò lè ṣe iṣẹ́ ẹ̀yán. Ẹ jẹ́ ká wo àwọn àpẹẹrẹ wọ̀nyí.

(2) a. Mo mọ Súlú **ọba**.
    b. Ọba wọ agbádá **ẹtù**.
    d. Bádé ń waọkọ̀ **agbégi**.
    e. Ìlù **dùndún** dùn jó.

Tí a bá wo (1a), ẹnití a pè ní **Súlú**, òun kan náà ni **ọba**. Bákan náà, ní (1b) oríṣi **agbádá** kan tí a fi aṣọ **ẹtù** rán ní a mọ̀ sí **agbádá ẹtù**. Ẹ̀wẹ̀, oríṣi ọkọ kan ni ó ń jẹ́ **agbégi** nigbà tí **dùndún** jẹ́ ọ̀kan lára ìlù ilẹ̀ Yorùbá.

### 3.2.3 Ajẹmáwọ̀

Ọ̀rọ̀-ẹ̀yán ajẹmáwọ̀ ni kìkì ẹ̀yán tó jẹ́ pé àwọ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ ni wọ́n máa ń fi hàn. Mẹ́ta ni ojúlówó àwọ̀ lédè Yorùbá. Àwọn àwọ̀ náà ni dúdú, pupa, funfun.

(3) a. Kọ́lá ra ọkọ **pupa**.
    b. Bádé ní ajá **dúdú**.
    c. Ẹ̀wù **funfun** nìyẹn.

Gẹ́gẹ́ bí ti àwọn ẹ̀yán tókù, ẹ̀yìn ọ̀rọ̀-orúkọ tí wọ́n bá yán ni àwọn náà máa ń wà.

### 3.2.4 Ẹ̀yán Ajẹmọ́ṣe

Ìsọ̀rí ọ̀rọ̀-ẹ̀yán tí a mọ̀ sí ajẹmọ́ṣe ni àwọn ọ̀rọ̀-ẹ̀yán tí a ṣẹ̀dá láti inú ọ̀rọ̀-ìṣe. Àpẹẹrẹ ni gíga, kúkúrú, títóbi gẹ́gẹ́ bí wọ́n ti jẹyọ nísàlẹ̀.

(4) a. Túndé gé igi **gíga**.
b. Mo fẹ́ ìyàwó **kúkúrú**.
d. Iṣu **títóbi** nimo rà.

Mo pe àwọn ẹ̀yán òkè ni ajẹmọ́ṣe nítorí a lè lo àgékúrú wọn gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀-ìṣe bí ó ti hàn ní (5).

(5) a. Igi **ga**.
b. Ìyàwó **kúrú**.
d. Iṣu **tóbi**.

Tí o bá fi àwọn àpẹẹrẹ (4) wé ti (5) wà á rí ìbáṣepọ̀ èrò àti ìtumọ̀ láàárín wọn. Bí àpẹẹrẹ, ọ̀kan náà ni **igi gíga** àti **igí ga** ní ti èrò àti ìtumọ̀, bẹ́ẹ̀ náà ni ọ̀rọ̀ rí fún àwọn àpẹẹrẹ tó kù.

### 3.2.5 Ẹ̀yánAsọye

Ọ̀rọ̀-ẹ̀yán asọye pín sí méjì: aṣòùnkà àti aláìṣòùnkà: Ọ̀rọ̀-ẹ̀yán aṣòùnkà máa ń fi iye ti ọ̀rọ̀-orúkọ bẹ́ẹ̀ jẹ́ ní pàtó nínú àpólà tàbí gbólóhùn hàn. Àpẹẹrẹ wọn ni méjì, méje, mẹ́wàá, ogún.

(6) a. Iṣu **méjì** ni mo rà.
b. Mo ra ìwé **méje**.
d. Ọmọ **mẹ́wàá** ló yege ìdánwò!
e. Bánkọ́lé kọ ilé **ogún**.

Ọ̀rọ̀-ẹ̀yán asọye aláìṣòùnkà ni ọ̀wọ́ asọye aláìnígbèdéke. Àwọn náà jẹ́ mẹ́ta: díẹ̀, púpọ̀, gbogbo.

(7) a. Ilé **díẹ̀** ni mo rà.
b. Ilé **púpọ̀** ni olówó náà kọ́
d. **Gbogbo** ilé yẹn, ti Dáńgótè ni.

Nígbà tí **díẹ̀** àti **púpọ̀** jẹyọ tẹ̀lé ọ̀rọ̀-orúkọ, **gbogbo** máa ń jẹyọ ṣáájú ọ̀rọ̀-orúkọ tí ó yán ni.

### 3.2.6 Ẹ̀yánAṣàfihàn

Ìsọ̀rí ọ̀rọ̀-ẹ̀yántí a mọ̀ sí aṣàfihàn ni àwọn ẹ̀yán tó tún jẹ́ wúnrẹ̀n aṣegírámà. Àwọn ẹ̀yán náà nì a fàlà sí nínú gbólóhù nìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

(7) a. Aṣọ **yìí** dára.
b. Ilé **yẹn** ti wó.
d. Àwọn **wọ̀nyí** ti bàjẹ́.
e. Ọkọ̀ **wọ̀nyẹn** kò dára.
ẹ. Ọlọ́pàá mú ọ̀daràn **náà**.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé a ka àwọn wúnrẹ̀n yẹn sí ẹ̀yán tó jẹ́ pé nípa síṣe bẹ́ẹ̀, ó yẹ kí wọ́n jẹ́ ọ̀rọ̀ pọ́nńbélé, síbẹ̀, wọn kò dá ìtumọ̀ ní fúnra wọn.

### 3.2.7 Ẹ̀yán Awẹ́ gbólóhùn

Ìsọ̀rí ọ̀rọ̀-ẹ̀yán tó kẹ́yìn ni awẹ́ gbólóhùn aṣàpèjúwe. Ẹ̀yán yìí gba orúkọ rẹ̀ nítorí pé odindi awẹ́ gbọ́lóhùn yàtọ̀ sí ẹyọ ọ̀rọ̀ ló ń para pọ̀ ṣe iṣẹ́ ẹ̀yán yẹn. Ẹ̀yìn ọ̀rọ̀-orúkọ tí wọ́n bá yán ni àwọn máa ń wà gẹ́gẹ́ bí ti ẹyọ ọ̀rọ̀-ẹ̀yán.

(8) a. Ilé **ti mo kọ́** jẹ́ mẹ́ta.
**Ilé** jẹ́ mẹ́ta

b. Bàbá bí ọmọ **tí ẹnu kò ká**.
Bàbá bí **ọmọ**

d. Ìwá **tí Olú hù** ni ó ṣe ikú pa á
**Ìwá**ni ó ṣe ikú pa á

e. Owó **tí ọlọ́pàá gbà** di wàhálà
**Owó** di wàhálà

ẹ Mo fẹ́ẹ̀ rí ọmọ **tí ó mọ́ ìyá rẹ̀ lójú**
Mo fẹ́ẹ̀ rí **ọmọ**.

Ibití ọ̀rọ̀-orúkọ tí ẹ̀yán awẹ́ gbólóhùn bá ń yán, bóyá ipò olùwà tàbí ipò àbọ̀ náà ló máa sọ ibi tí ẹ̀yán awẹ́ gbólóhùn ti máa jẹyọ.
Ní ìparí, ó yẹ kí n sọ fún yín wí pé ó ṣeé kí ẹ̀yán méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ jẹyọ tẹ̀lé ọ̀rọ̀-orúkọ. Fún ìjẹyọ tẹ̀léra ẹ̀yán, wo abẹ́ àpólà orúkọ nísàlẹ̀.

## 4.0 ÌGÚNLẸ̀

Ní ìpín yìí, a ti ṣe àyẹ̀wò fínnífínní nípa ìsọ̀rí ọ̀rọ̀-èyán ní sísẹ̀ǹtẹ̀lé pẹ̀lú àwọn àpẹẹrẹ tó jọjú.

## 5.0 ISỌNÍṢÓKÍ

A ti ṣe ọ̀kan-ò-jọ̀kan àyẹ̀wò tó jẹ mọ́ ọ̀rọ̀ ẹ̀yán. A bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú oríkì tí a lè fún ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ yìí bẹ̀rẹ̀ láti oríkì rẹ̀. Lẹ́yìn èyí ni a ṣe àgbékalẹ̀ oríṣiríṣi ìsọ̀rí

tí a lè pín in sí. Fún ọ̀kọ̀ọ̀kan ìsọ̀rí, ọ̀rọ̀-ẹ̀yán, a ṣe àgbékalẹ̀ ọ̀pọ̀ àpẹẹrẹ, a sì lò wọ́n nínú onírúurú gbólóhùn.

## 6.0 IṢẸ́ ÀYÀNṢE ONÍMÁÀKÌ OLÙKỌ́

1. Kí ni ẹ̀yán awẹ́ gbólóhùn aṣàpèjúwe?
2. Ìsọ̀rí ẹ̀yán wo ni a lè pí àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí sí: púpọ̀, díẹ̀, méjì?
3. Fún ẹ̀yán ní oríkì, kí o sì fi àpẹẹrẹ gbe ìdáhùn rẹ.
4. Ṣe àlàyé pẹ̀lú àpẹẹrẹ ọ̀rọ̀-ẹ̀yán ajẹmọ́ṣe kí o sì sọ ìdí tí wọ́n fi gba orúkọ náà.
5. Ṣe àfiwé ọ̀rọ̀-ẹ̀yán aṣeékà asọye àti aláìsọye.

## 7.0 ÀWỌN ÌWÉ FÚN KÍKÀ

Awobuluyi, Oladele (1978). *Essentials of Yoruba Grammar*. UPL. Oxford University Press, Ibadan. Chapter 3

Awobuluyi, Oladele. (2013). *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá.* ATMAN Limited. Osogbo. Orí 2, o.i. 53-86.

Bámgbóṣé, Ayọ̀. (1990). *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. o.i.119-130.

Yusuf, Ọrẹ. (1995). *Gírámà Yorùbá Àkọ̀tun.*o.i. 24-28.

## ÌPÍN 4 ỌRỌ̀-ÌṢE

**Àkóónú**

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
    3.1 Ọ̀rọ̀-ìṣe: Oríkì
    3.2 Ìpínsísọ̀rí ọ̀rọ̀-ìṣe
        3.2.1 Ọ̀rọ̀-ìṣe abáṣelọ àti aláìbáṣelọ
        3.2.2 Ọ̀rọ̀-ìṣe agbàbọ̀ àti aláìgbàbọ
        3.2.3 Ọ̀rọ̀-ìṣe ajẹmọ́pò-ìgbà-díẹ̀ àti ajẹmọ́pò-ìgbà-pípẹ́
            3.2.3.1 Ọ̀rọ̀-ìṣe ajẹmọ́pò-ìgbà-díẹ̀
            3.2.3.2 Ọ̀rọ̀-ìṣe ajẹmọ́pò-ìgbà-pípẹ́
        3.2.4 Ọ̀rọ̀-ìṣe alápèpadà
        3.2.5 Ọ̀rọ̀-ìṣe asolùwàdàbọ̀
        3.2.6 Ọ̀rọ̀-ìṣe ẹlẹ́là
        3.2.7 Ọ̀rọ̀-ìṣe àsínpọ̀
        3.2.8 Ọ̀rọ̀-ìṣe aṣèbéèrè
        3.2.9 Ọ̀rọ̀-ìṣe afarahẹ
4.0 Ìgúnlẹ̀
5.0 Isọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Àyànṣe Onímáàkì Olùkọ́
7.0 Àwọn Ìwé fún Kíkà

### 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ìsọ̀rí kan pàtàkì ni ọ̀rọ̀-ìṣe jẹ́ nínú èdè àgbáyè. Kò sì yọ èdè Yorùbá sílẹ̀. Kí wáá ni ọ̀rọ̀-ìṣe? Ní ṣókí, ọ̀rọ̀-ìṣe ni kòṣeémánìí inú gbólóhùn. Kò sí ní ìjọ, ìjọ kò kún ni. Òun ni ẹ̀mí tàbí ọkàn inú gbólóhùn.

### 2.0 ÈRÒǸGBÀ

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ó yẹ kí akẹ́kọ̀ọ́ lè dá ọ̀rọ̀-ìṣe mọ̀ nínú gbólóhùn kí wọ́n sì lè lò wọ́n nínú gbólóhùn fúnra wọn. Ìyẹn nìkan kọ́, wọ́n tún gbọ́dọ̀ lè mọ ọ̀kanòjọ̀kan ìsọ̀rí tí a lè pín ọ̀rọ̀-ìṣe sí.

### 3.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ iṣẹ́ yìí yóò bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú oríkì ọ̀rọ̀-ìṣe ká tó tẹ̀síwájú pẹ̀lú ìsọ̀rí tí ọ̀rọ̀-ìṣe lè ní. Lẹ́yìn náà ni a ó ṣe ìgúnlẹ̀ àti ìsọnísókí ohun tí orí yìí dálé.

### 3.1 Ọ̀rọ̀-ìṣe: Oríkì

Ọ̀rọ̀-ìṣe ló máa ń:

a. sọ nípa ohun tí ẹnìkan ṣe sí ohun tàbí ẹnìkan,
b. sọ nípa ipò tí ènìyàn, ẹranko tàbí ohunkan wà.
d. sábà jẹ yọ tẹ̀lé àpólà-orúkọ (APOR) tàbí wà ní àárín àpólà orúkọ méjì nínú gbólóhùn.

Mo fẹ́ẹ́ fi àpẹẹrẹ ṣe ègbè lẹ́yìn oríkì yìí.

(1) a. Olú **gé** igi:
b. Ìyá àgbà **kú**.
d. #APORẸrankobúburú#**pa**#APORajá ọdẹ#.

Ní (1a), Olú ló ṣe ohunkan. Ohun náà ni gígé igi, ìyẹn ni wí pé ohun tí a ṣe nǹkan sí ni igi tí a gé. Ní (1b) ipò tí ìyá àgbà wà ni pé ó kú. Wàyí o, ní (1d), **pa** ni ó wà ní àárín #ẹranko búburú# àti #ajá ọdẹ# tí wọ́n jẹ́ APOR.

### 3.2 Ìpínsísọ̀rí ọ̀rọ̀-ìṣe

Oríṣiríṣi ọ̀ṣùwọn ni a lè fi pín ọ̀rọ̀-ìṣesí ìsọ̀rí. Bí àpẹẹrẹ, a lè fi ìhùwàsí, ìjẹyọpọ̀/ìkọ́wọ̀ọ́rìn, ìtumọ̀ abbl. pín ọ̀rọ̀-ìṣesí ìsọ̀rí. Èyí tó wù kó jẹ́, ó ṣeé ṣe kí àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe kan wà ní ìsọ̀rí tó ju ẹyọ kan lọ. Ẹ jẹ́ ká bẹ̀rẹ̀ síí wò wọ́n ní ọ̀kọ̀ọ̀kan.

#### 3.2.1 Ọ̀rọ̀-ìṣe abáṣelọ àti aláìbáṣelọ

Ọ̀rọ̀-ìṣe abáṣelọ gẹ́gẹ́ bí orúkọ rẹ̀ jẹ́ ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó fi ohun tí ẹnìkan tàbí ohun kan ṣe sí ẹni tàbí ohun kan hàn. Àpẹẹrẹ irú ọ̀rọ̀-ìṣe bẹ́ẹ̀ ni: jẹ, mu, rìn, lù, nà, gbé, fọ́, pa, tà, kọ́ abbl.

(2) a. Bánirẹ́ **jẹ** iṣu.
b. Bánirẹ́ **mu** omi.
c. Bánirẹ́ **rìn**.
d. Bánirẹ́ **lu** ìlù.
e. Bánirẹ́ **na** ọmọ.

Ìbéèrè kan ṣoṣo lè dúró fún àwọn àpẹẹrẹ (2). A lè béèrè wí pé: **Kí ni Bánirẹ́ ṣe?** Ìdáhùn sí ìbéèrè yẹn lè jẹ́ èyíkéyìí gbólóhùn wọ̀nyẹn.

Ọ̀rọ̀-ìṣe aláìbáṣelọ ni ọ̀rọ̀-ìṣe tó jẹ́ wí pé wọn kò bá iṣe kan pàtó lọ. Irú ọ̀rọ̀-ìṣe bẹ́ẹ̀ lè fi ipò tí ẹni tàbí ohun kan wà hàn. Irú ọ̀rọ̀-ìṣe bẹ́ẹ̀ niwà, jẹ (gbèsè), ta (òsì), ní abbl. Ejẹ́ ká fi díẹ̀ nínú wọn hàn nínú gbólóhùn ìsàlẹ̀.

(3) a. Adé **wà** nínú ọgbà.
b. Adé **sùn**.

d. Adé **ta** òṣì.
e. Adé **jẹ** gbèsè.
ẹ Adé **ní** owó.

Ọ̀kọ̀ọ̀kan àpẹẹrẹ gbólóhùn òkè kò jẹ mọ́ ìṣe tàbí bá ìṣe kan pàtó lọ bí kò ṣe ipò tí ọ̀rọ̀-orúkọ wà. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, ní (3b), ipò ìsùn/orun ni Adé wà. Kò sì lágbára lórí ipò yẹn. Ẹ tùn wo (3d) tó jẹ́ ipò àìlówó tí Adé wà. Bí ọ̀rọ̀ ti rí fún gbogbo ọ̀rọ̀-ìṣe ìsọ̀rí yìí nìyẹn.

### 3.2.2 Ọ̀rọ̀-ìṣe agbàbọ̀ àti aláìgbàbọ

**Ọ̀rọ̀-ìṣe agbàbọ̀** jẹ́ ọ̀rọ̀-ìṣetí ó di dandan láti ní ọ̀rọ̀-orúkọ àbọ̀, ó ṣeé ṣe kí ó ní ọ̀rọ̀-orúkọ olùṣe tàbí olùwà, pàápàá tí gbólóhùn tó ti jẹ yọ kì í bá ṣe fún pípàṣẹ. Àpẹẹrẹ irú ọ̀rọ̀-ìṣe bẹ́ẹ̀ ni: dé, rà, kọ, fẹ́ràn, ní, kàn, gbà. Ẹ wò wọ́n nínú gbólóhùn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀.

(4) a. Ọba **dé** adé
b. Bọ́lá **ra** ọkọ̀
d. Bọ́lá **fẹ́ràn** iṣu
e. Olè **kan** ilẹ̀kùn
ẹ. Dáńgótè **ní** owó

Àlàyé àwọn àpẹẹrẹ gbólóhùn òkè kò rújú rárá. **Adé** ni àbọ̀ fún **dé**, **ọkọ̀** ni àbọ̀ fún **rà**, **iṣu** ni àbọ̀ fún **fẹ́ràn** abbl.

**Ọ̀rọ̀-ìṣe aláìgbàbọ̀** ni ọ̀rọ̀-ìṣe tó jẹ́ pé kìkì ọ̀rọ̀-orúkọ olùwà tàbí olùṣe ni wọ́n máa ń ní nínú gbólóhùn. Ìyẹn ni wí pé wọn kí í gba ọ̀rọ̀-orúkọ́ tó jẹ́ àbọ̀ tààrà àfi àrótì (adjunct). Àpẹẹrẹ irúfẹ́ ọ̀rọ̀-ìṣe aláìgbàbọ̀ ni: kú, wà, sùn, dìde, jòkó. Ìlò wọn ló wà ní àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀.

(5) a. Abíọ́lá **kú** (ní ọdún 1993)
b. Òjó **wà** (nínú ọgbà)
d. Ajá **sùn** (sí ojú títì)
e. Ọ̀bọ **jòkó** (sí orí ága)
ẹ. Gbogbo ènìyàn **dìde** (fún Bùhárí).

Ẹ̀wẹ̀, kò sí èyíkéyìí gbólóhùn tó wà ní (5) tí ọ̀rọ̀-ìṣe rẹ̀ tó ní ọ̀rọ̀-orúkọ àbọ̀ tààrà. Bí a bá fi (5a) ṣe àkàwé, a ó ri wí pé **ọdún 1993** kì í ṣe àbọ̀ fún **kú**. Àbọ̀ fún ọ̀rọ̀-atọ́kùn **ní** ni; tí àpólà-atọ́kùn **ní ọdún 1993** wá jẹ́ àrótì. Bí ọ̀rọ̀ ṣerí fún àwọn àpẹẹrẹ tó kù nìyí.

### 3.2.3 Ọ̀rọ̀-ìṣe ajẹmọ́pò-ìgbà-díẹ̀ àti ajẹmọ́pò-ìgbà-pípẹ́

Ọ̀wọ́ ọ̀rọ̀-ìṣe méjì mìíràn tí ọ̀rọ̀ tún kàn ni ajẹmọ́pò-ìgbà-díẹ̀ àti ajẹmọ́pò-ìgbà-pípẹ́. Kí wá ni àbùdá wọn?

### 3.2.3.1 Ọ̀rọ̀-ìṣe ajẹmọ́pò-ìgbà-díẹ̀

Ọ̀rọ̀-ìṣe ajẹmọ́pò-ìgbà-díẹ̀ ni àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe tó máa ń fi ipò tí ẹni tàbí ohun kan wà tàbí ohun tí ẹni tàbí ohun kan ṣe ní sáà kan. Irú ọ̀rọ̀-ìṣe yìí fara pẹ́ ọ̀rọ̀-ìṣe abáṣelọ, b.a. rìn, sáré, sùn, lálàá, tọ̀.

(6) a. Bọ́lá **rìn** fún wákàtí mẹ́wàá
b. Ẹṣin **sáré** ìje
c. Bọ́lá **sùn** ní yàrá ìkẹ́kọ̀ọ́
d. Adììtú **lálàá** ìyanu
e. Kòkúmọ́ **tọ̀** sí sòkòtò.

Ọ̀kọ̀ọ̀kan ọ̀rọ̀-ìṣe àpẹẹrẹ òkè ló fi ipò tàbí ìṣẹ̀lẹ̀ sáà kan hàn. Ẹ wo (6b), ìsáré ẹṣin kò lè ju ọjọ́ kan lọ tó fi máa parí. Bí Bọ́lá ti lè sùn tó, kò lè fi ọjọ́ mẹ́ta sùn! Bí àlá Àdììtú ti lè pẹ́ tó kò lè ju àkókò tó fi wà lójú orun nìkan lọ. Ìyẹn ni wí pé ọ̀kọ̀ọ̀kan ọ̀rọ̀-ìṣe wọ̀nyẹn ló jẹ́ pé ipò tàbí ìṣe wọn wà fún ìgbà díẹ̀ ni.

### 3.2.3.2 Ọ̀rọ̀-ìṣe ajẹmọ́pò-ìgbà-pípẹ́

Ní ìdà kejì ọ̀rọ̀-ìṣe ajẹmọ́pò ìgbà díẹ̀ ni àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe ajẹmọ́pò ìgbà pípẹ́. Àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe bẹ́ẹ̀ ni ó máa ń fi ìṣe, ìṣẹ̀lẹ̀ tàbí ipò tí òpin rẹ̀ kì í ṣeé dédé sọ tàbi kì í dédé ṣeé fi hàn. Àpẹẹrẹ wọn ni fẹ́ràn, kórìíra, gọ̀, gbọ́n, gbádùn. Ẹ jẹ́ ká wo ìlò wọ́n nínú gbólóhùn.

(7) a. Àgùtàn **gọ̀**.
b. Ajá **fẹ́ràn** Egungun.
d. Ìjàpá **gbọ́n**.
e. Òyìnbó **gbádùn** sìgá.
ẹ. Aṣièrè **kóòríra** ìbáwí

Ìtumọ̀ tí ọ̀rọ̀-ìṣe gbogbo (7) ní nièyí tí a kò lè sọ pàtó òpin rẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, láti ọjọ́ táláyé ti dáyé ni a ti ń sọ pé "àgùtàn **gọ̀**", gbogbo àgùtàn ni a sì ń bá wí. Ẹ̀wẹ̀ ìran ajá ló máa ń **fẹ́ràn** Egungun, ìyẹn ni wí pé gbogbo ajá àbí ká sọ pé ajákájá, ìbáà ṣe ajá òyìnbó, ajá, ọdẹ, ajá kẹ́keré, abbl. ló máa ń **fẹ́ràn** egungunkégungun, ìbáà ṣe Egungun ẹja, egungun màlúù abbl. Nínú èrò tó gùn lé àkíyèsí Yorùbá nípa àwọn òyìnbó, gbogbo wọn ló fẹ́ràn àtimáamusìgá. Ìdí nìyí tí fi ń pe irú ọ̀rọ̀ ìṣe wọ̀nyí ní ajẹmọ́pò tàbí ajẹmọ́ṣẹ̀lẹ̀ ìgbà pípẹ́.

### 3.2.4 Ọ̀rọ̀-ìṣe alápèpadà

Ìsọ̀rí ọ̀rọ̀-ìṣe alápèpadà ni àwọn ọrọ̀-ìṣe tó máa n jẹyọ lẹ́ẹ̀méjì nínú gbólóhùn láti ṣe àkànmọ́lẹ̀ èrò olùsọ̀rọ̀. Àpẹẹrẹ wọn ni ṣe, kù, mọ̀, dá, abbl.

(8) a. Má jẹ́ kó **ṣe** mí **ṣe** ẹ́.
b. Ó **ku** Adé **ku** ìwà rẹ̀.
d. Wọn kò **mọ̀** ọ́n **mọ̀** mí.
e. Ọkọ Bọ́lá **dá** mi **dá** wàhálà mi.
ẹ. Ayé kò **fẹ́** ẹni **fẹ́** ọrọ̀.

Wo àpẹẹrẹ (8e), ọkọ Bọ́lá ló dá Bọ́lá dá wàhálà rẹ; ìyẹn ni wí pé ọkọ kò ba gbọ́ bùkátà rẹ̀. Ẹ̀wẹ̀, kò sí ẹni tí ayé fẹ́ kó ṣe rere ni **fẹ́ ẹni fẹ́ ọrọ̀** túmọ̀ sí; bẹ́ẹ̀ ni ọ̀rọ̀ rí fún àwọn àpẹẹrẹ tó kù.

### 3.2.5 Ọ̀rọ̀-ìṣe asolùwàdàbọ̀

Gẹ́gẹ́ bí orúkọ rẹ̀, ọ̀rọ̀-ìṣe aṣolùwàdàbọ̀ ló lè mú kí ó ṣeé ṣe kí ọ̀rọ̀-orúkọ olùwà ṣípò padà lọ sí ipò ọ̀rọ̀-orúkọ àbọ̀ tí ọ̀rọ̀-orúkọ àbọ̀ náà á lọ sí ipò olùwà láìyí ìtùmọ̀ àti èrò ọkàn olùsọ̀rọ̀ padà. Àpẹẹrẹ irú ọ̀rọ̀-ìṣe bẹ́ẹ̀ ni ta, jẹ, bà, fò.

(9) a. Mo **jẹ** ìyà. Ìyà **jẹ** mí.
b. Adé **ta** òṣì. Òṣì **ta** Adé.
d. Àyà **fo** Adé. Adé **fò**yà.
e. Bọ́lá **ba** ẹ̀rù Ẹ̀ru **ba** Bọ́lá.

Mo fẹ́ẹ́ fi (9b) ṣe àpẹẹrẹ. Mo fẹ́ bi ẹ́ ní ìbéèrè kan: Kí ni ìyàtọ̀ tó wà láàárín **Adé ta ọ̀ṣì** àti **Ọ̀ṣì ta Adé**? Ìdáhùn sí ìbéèrè yẹn ni “Kò sí”

### 3.2.6 Ọ̀rọ̀-ìṣe ẹlẹ́là

Ní ti àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe ẹlẹ́là, wọ́n máa ń fi àyè gba ọ̀rọ̀-orúkọ àbọ̀ láti pín wọn níyà. Àpẹẹrẹ wọn ni: bà…jẹ́, dì…mú, gbà…gbọ́, bẹ̀…wò, tàn…jẹ, yí…po, kàn…pọ̀ abbl. Ẹ jẹ́ ká wò ìjẹyọ wọ́n nínú gbólóhùn.

(10) a. Ọmọ ẹ̀kọ́ṣẹ́ **ba** aga **jẹ́**.
b. Ìyàwó **gba** Jésù **gbọ́**.
d. Dókítà **bẹ̀** mi **wò**.
e. Ó **yí** ayé **po**.
ẹ. Làtí **di** ẹran iléyá **mú**.
f. Wèrè Ojú ẹlẹ́gba **kan** ẹ̀wù mẹ́fà **pọ̀**.

Bí a bá wo (10a), “àga” ló pín **bajẹ́** níyà. “Ọkọ” ló pín **gbagbọ́** níyà ní (10b), abbl. Ó wá ṣeé ṣe kí àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe yẹn jẹyọ láìsí àbọ̀ láàárín wọn bí ó ti hàn ní àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀.

(11) a. Àga **bajẹ́**.
b. Ìyàwó **gbagbọ́**.
d. Dókítà kò **bẹwò** kó tó lọlé.
e. Ayé **yípo**.

ẹ. Làtí **dimú** dáadáa.
f. Mo **kànpọ̀**.

### 3.2.7 Ọ̀rọ̀-ìṣe àsínpọ̀

Àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe àsínpọ̀ ni wọ́n máa ń tò tẹ̀lé ara wọn nínú gbólóhùn. Ọ̀pọ̀ ìgbà ni wọ́n máa ń ní olùwà kan ṣoṣo b.a. pa tà, rìn lọ,

(12) a Bàbá mi ń **pa** ẹran **tà**.
b. Bọ́lá **rìn lọ** oko
d. Bàbá **gún** iyán **jẹ** lóko
e. Ẹ̀bùn **fọ** aṣọ **sá**.
ẹ. Fúlàní **da** ẹran **wọ** inú oko Fálayé
f. Ìyá **jí sáré lọ gbọ́mọ kúnlẹ̀ kí** ọba.

Tí a bá fi (12ẹ) ṣe àpẹẹrẹ, Fúlàní tí ó **da** ẹran, náà ni ó **wọ** oko Fálayé.

### 3.2.8 Ọ̀rọ̀-ìṣe aṣèbéèrè

Àrà ọ̀tọ̀ ni ọ̀rọ̀-ìṣeì sọ̀rí yìí nítorí iṣẹ́ méjì ni wọ́n ń ṣe papọ̀: wọ́n jẹ́ ọ̀rọ̀-ìṣe, wọ́n sì tún ń ṣe iṣẹ́ ìbéèrè. Méjì péré sì tún ni àwọn ọ̀rọ̀ náà, àwọn ni: dà àti ńkọ́ gẹ́gẹ́ bí wọ́n ti hàn nínú gbólóhùn ìsàlẹ̀.

(13) a. Ẹ̀bùnayọ̀ dà?
b. Ẹ̀bùnayọ̀ ńkọ́?

Mo fẹ́ẹ̀ fi yé ẹ wí pé ohun tí ó mú kí àwọn ọ̀rọ̀ méjì yẹn gba àbùdá ọ̀rọ̀-ìṣe ni wí pé ọ̀kọ̀ọ̀kan gbólóhùn tí wọ́n ti jẹ yọ ló dá ìtumọ̀ ní, bẹ́ẹ̀ sì ni ọ̀rọ̀-orúkọ Ẹ̀bùnayọ̀ ni wọ́n jẹyọ tẹ̀lé; bẹ́ẹ̀ àbùdá gbólóhùn kíkún ni wí pé ó gbọ́dọ̀ ní ọ̀rọ̀-ìṣekan, ó kéré tán. Lẹ́yìn ọ̀rọ̀-orúkọ, Ẹ̀bùnayọ̀, kò tún sí ọ̀rọ̀ mìíràn mọ́ yàtọ̀ sí “dà” tàbí “ńkọ́”.

### 3.2.9 Ọ̀rọ̀-ìṣe afarahẹ

Ọ̀rọ̀-ìṣe tí mo fẹ́ wò kẹ́yìn ni ọ̀rọ̀-ìṣe afarahẹ. Ohun tó máa jẹ́ kàyéfì ni kí a sọ pé ọ̀rọ̀-ìṣe afarahẹ wà nínú èdè Yorùbá níwọ̀n ìgbà tí a ti sọ pé òun ni òpómúléró fún gbólóhùn. Àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe ìsọ̀rí yìí gba orúkọ náà láti ara wí pé ìbejì ni wọ́n; wọn kì í yara wọn sílẹ̀. Bí a bá sì fẹ́ẹ́ fi ipá yà wọ́n nípa lílo ẹyọ kan, gbólóhùn yẹn kò ní ní ìtumọ̀ tàbí kíkú tàbí bétí mu. Ìyẹn ni pé, ọ̀kan nínú wọn ló dá ìtumọ̀ kíkún ní tí ìkejì kò dá ìtumọ̀ ní bí ti mọ́fíìmù afarahẹ nínú ẹ̀kọ́ mofọ́lọ́jì. Àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe afarahẹ yìí fara jọ ọ̀rọ̀-atọ́kùn ní ipò àti ìrísí.

Àpẹẹrẹ díẹ̀ nínú wọn ni: **fi, sí, bá, fẹ́rẹ̀ẹ́**. Ṣe ni wọn máa wá jẹyọ pẹ̀lú ọ̀rọ̀-ìṣe tó ní ìtumọ̀ kíkún.

(14) a. Ọ̀jọ̀ **fẹ́rẹ̀ẹ́** rọ̀
b. Adé **bá** Bọ́lá jà
d. Wọ́n **fi** ọṣẹ fọ aṣọ
e. Ọmọ **fi** ata **sí** ojú

Ní àpẹẹrẹ (a-d), àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe àkọ́kọ́ (fẹ́rẹ̀ẹ́, bá, fi) ni ó jẹ́ afarahẹ nígbà tí ọ̀rọ̀-ìṣe kejì (rọ̀, jà, fọ̀) lè dá dúró ṣùgbọ́n ní àpẹẹrẹ (e), kò sí èyíkéyìí ọ̀rọ̀ ìṣe tó wà níbẹ̀ (fi, sí) tó lè dá dúró. Tí a bá gbìyànjú láti yà wọ́n nípa bí ó ti hàn ní (15), ìpèdè tí kò ní ìtumọ̀ ló máa jáde, síbẹ̀ ní (14e), ìtumọ̀ kíkún ló wà níbẹ̀.

(15) a *Ọmọ **fi** ata ojú
b. *Ọmọ ata **sí** ojú

Mo fẹ́ kí o mọ̀ wí pé àwọn kan kò gbà pé ọ̀rọ̀-ìṣe ni àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe afarahẹ tí a ń sọ̀rọ̀ bá níbí. Ní ipele ẹ̀kọ́ mìíràn, wà á rí àlàyé tó ṣègbè lẹ́yìn èrò tèmi yìí.

## 4.0 ÌGÚNLẸ̀

A ti ṣe àgbéyèwò ìsọ̀rí ọ̀rọ̀-ìṣe wò fínní fínní pẹ̀lú oríṣiríṣi òdiwọ̀n tí a lè fi pín wọn sí ìsọ̀rí ìsọ̀rí.

## 5.0 ISỌNÍSÓKÍ

Ní ìpín yìí, mo ti sọ̀rọ̀ nípa ọ̀rọ̀-ìṣe, ìsọ̀rí méjọ ni mo ṣe àkíyèsí wí pé a lè pín ọ̀rọ̀-ìṣe inú èdè Yorùbá sí. Àwọn ni ọ̀rọ̀-ìṣe abáṣelọ àti aláìbáṣelọ, ọ̀rọ̀-ìṣe agbàbọ̀ àti aláìgbàbọ, ọ̀rọ̀-ìṣe ajẹmọ́pò ìgbà díẹ̀ àti ajẹmọ́pò ìgbà pípẹ́, ọ̀rọ̀-ìṣe alápèpadà, ọ̀rọ̀-ìṣe asolùwàdàbọ̀, ọ̀rọ̀-ìṣe ẹlẹ́là, ọ̀rọ̀-ìṣe àsínpọ̀ àti ọ̀rọ̀-ìṣe aṣèbéèrè. A rì nínú àwọn ìsọ̀rí náà tí wọ́n ṣeé tún pín sí ìsọ̀rí gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn lókè yìí. Fún ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan, a ṣe àgbékalẹ̀ àwọn àpẹẹrẹ, a sì lò wọ́n nínú gbólóhùn.

## 6.0 IṢẸ́ ÀYÀNṢE ONÍMÁÀKÌ OLÙKỌ́

1. Fún ọ̀rọ̀-ìṣe ní oríkì kan tó pójú owó.
2. Kí ni ìyàtọ̀ láàárín ọ̀rọ̀-ìṣe abáṣelọ àti aláìbáṣe lọ?
3. Dárúkọ ọ̀rọ̀-ìṣe aṣèbéèrè ní èdè Yorùbá, kí o sì ló wọ́n nínú gbólóhùn.
4. Kí ni ìdí rẹ̀ tí a fi ń pe àwọn ọ̀rọ-ìṣe kan ní alápèpadà?

## 7.0 ÀWỌN ÌWÉ FÚN KÍKÀ

Awobuluyi, Oladele (1978). *Essentials of Yoruba Grammar*. UPL. Oxford University Press, Ibadan. Orí 2.

Awobuluyi, Oladele (2013). *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá.* ATMAN Limited. Osogbo. Orí 3, o.i 88-136.

Bámgbóṣé, Ayọ̀. 1990. Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá. Orí 19, o.i. 131-152.

Yusuf, Ọrẹ. 1995. *Gírámà Yorùbá Àkọtun.*o.i. 40-45.

# ÌPÍN 5 Ọ̀RỌ̀-ÀPỌ́NLÉ

## Àkóónú

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
3.1 Oríkì
3.2 Ìpińsísọ̀rí Ọ̀rọ̀-àpọ́nlé
3.2.1 Ọ̀rọ̀-àpọ́nlé Aṣáájú Ọ̀rọ̀-ìṣe
3.2.2 Ọ̀rọ̀-àpọ́nlé Agbẹ̀yìn-ìṣe
3.2.3 Awẹ́ gbólóhùn aṣàpọ́nlé
3.2.3.1 Awẹ́ gbólóhùn aṣàpọ́nlé àsìkò
3.2.3.2 Awẹ́ gbólóhùn aṣàpọ́nlé ibi
3.2.3.3 Awẹ́ gbólóhùn aṣàpọ́nlé ibá
4.0 Ìgúnlẹ̀
5.0 Isọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Àyànṣe Onímáàkì Olùkọ́
7.0 Àwọn Ìwé Fún Kíkà

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ohun tó jẹ wá lógún ni kí a lè ṣe àlàyé tó yéni yéké yéké nípa ohun tí a ń pè ní ọ̀rọ̀-àpọ́nlé àti bí a ti ṣe lè dá wọn mọ̀ nínú gbólóhùn.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ

Èrò wa ni pé ní ìparí ìpín yìí, o máa lè fúnra wọn dá ọ̀rọ̀-àpọ́nlé mọ̀, wọ́n á sì lè mọ oríṣiríṣi wọn nínú gbólóhùn àti ìlò wọn.

## 3.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Mo bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ ìpín yìí pẹ̀lú oríkì ọ̀rọ̀-àpọ́nlé, iṣẹ́ tí wọ́n ń ṣe àti oríṣiríṣi ìsọ̀rí tí a lè pín wọn sí.

### 3.1 Oríkì

Ọ̀rọ̀-àpọ́nlé ni ọ̀rọ̀kọ́rọ̀ lédè Yorùbá tó máa ń wà ní agbègbè ọ̀rọ̀-ìṣe. Òunni ó máa ń túbọ̀ fi kún ìtumọ̀ tí ọ̀rọ̀-ìṣení láti jẹ́ kí olùgbọ́ ní òye kíkún nípa ọ̀rọ̀-ìṣe, wọn a sì tiipa bẹ́ẹ̀ dín pọ́nna tí ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe bẹ́ẹ̀ lè ní kù.

### 3.2 Ìpińsísọ̀rí Ọ̀rọ̀-àpọ́nlé

Gẹ́gẹ́ bí ti àwọn ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ tí a ti wò ṣáájú, ọ̀rọ̀-àpọ́nlé ṣeé pín sí oríṣríṣi gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn nísàlẹ̀.

### 3.2.1 Ọ̀rọ̀-àpọ́nlé Aṣáájú Ọ̀rọ̀-ìṣe

Ọ̀rọ̀-àpọ́nlé aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe ni ọ̀wọ́ ọ̀rọ̀-àpọ́nlé tí wọ́n máa ń kọ́kọ́ jẹyọ kí ọ̀rọ̀-ìṣe tí wọ́n ń pọ́nlé tó jẹyọ, ìyẹn ni wí pé irú ọ̀rọ̀-àpọ́nlé bẹ́ẹ̀ ni a máa kọ́kọ́ rí, kí a tó rí ọ̀rọ̀-ìṣe. Àpẹẹrẹ irú ọ̀rọ̀-àpọ́nlé náà ni tètè, pàpà, kúkú, wulẹ̀, abbl. gẹ́gẹ́ bí mo ti fi wọ́n hàn nínú gbólóhùn tó wà ní (1).

(1) a. Àlùfáà tètè **parí** ìwàásù.
b. Àlùfáà kúkú **parí** ìwàásù.
d. Àlùfáà pàpà **parí** ìwàásù.
e. Àlùfáà wulẹ̀ **parí** ìwàásù.

### 3.2.2 Ọ̀rọ̀-àpọ́nlé Agbẹ̀yìn-ìṣe

Ọ̀rọ̀-àpọ́nlé agbẹ̀yìn ọ̀rọ̀-ìṣe ni ọ̀wọ́ ọ̀rọ̀-àpọ́nlé tí wọ́n máa ń tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe tí wọ́n ń pọ́nlé. Àtẹ̀lé yìí lè jẹ́ tààrà, ìyẹn ni wí pé, ó lè wáyé lẹ́yìn ọ̀rọ̀-ìṣe bẹ́ẹ̀, ó sì ṣeé ṣe kí ọ̀rọ̀-orúkọ pín wọn níyà. Díẹ̀ nínú ọ̀wọ́ ọ̀rò-àpọ́nlé bẹ́ẹ̀ ni: mọ́, gbì, dì, yakata, jàùjàù, rogodo, kíá, wéré, gbàù, rí abbl.

(2) a. Adédùnmọ̀lá fèsì **kíá**.
b. Ó **lulẹ̀** gbì.
d. Ìbọnnáà **dáhùn** gbàù.
e. Ọmọ náà **ṣubú** yakata.
ẹ. Ọdẹ náà **rìn** jàùjàù.
f. Ọdẹ kò tún **rí** ẹran abàmì náà mọ́.
g. Ẹgbẹ APC kò ṣe òjóóró **rárá**.
gb. Ó wà ní jìnnà **réré**.

Gbogbo àpẹẹrẹ márùn-ún àkọ́kọ́ ni ọ̀rọ̀-àpọ́nlé jẹyọ tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe wọn tààrà, ṣùgbọ́n ní ti àpẹẹrẹ tó kẹ́yìn, (2f), ṣẹ ni "ẹran abàmì náà" tó jẹ́ àpólà-orúkọ wà láàárín **rí** àti mọ́. Ohun mìíràn tí mo ní láti tọ́ka sí niti ìjọra ọ̀rọ̀ àpọ́nlé: rí àti mọ́ pẹ̀lú ọ̀rọ̀-ìṣe méjì: rí àti mọ́ tí wọ́n ní ìrísí kan náà bí wọ́n ti hàn ní (3a) and (3c).

(3) a. N kò **rí** ẹ rí.
b. N kò **mọ̀** ẹ́ mọ́.
d. Aṣọ tí oje igi kán sí kò **mọ́** mọ́.

### 3.2.3 Awẹ́ gbólóhùn aṣàpọ́nlé

Àwọn ọ̀rọ̀-àpọ́nlé tí a ti ń wò bọ̀, jẹ́ kìkì ẹyọ ọ̀rọ̀. Àmọ́ sáá, ó tún ṣeé ṣekí àpọ́nlé ọ̀rọ̀-ìṣe jẹ́ awẹ́ gbólóhùn. Oríṣiríṣi sì ni awẹ́ gbólóhùn tó ń ṣiṣẹ́ àpọ́nlé. Ẹ jẹ́ ká fi wọ́n hàn ní sísẹ̀ntẹ̀lé.

### 3.2.3.1 Awẹ́ gbólóhùn aṣàpọ́nlé àsìkò

Ọ̀kan lára awẹ́ gbólóhùn aṣàpọ́nlé ni èyí tó máa ń fi àsìkò ìṣẹ̀lẹ̀ hàn. Àpẹẹrẹ irú awẹ́ gbólóhùn bẹ́ẹ̀ ni ó wà nísàlẹ̀.

(4) a. Aláìsàn lo oògùn ní **ìgbà tí ó jẹun tán**.
b. Aláìsàn sùn ní **ìgbà tí Dókítà ń ṣeiṣẹ́ abẹ**.
d. Mo kígbe ní **ìgbà tí mo gbọ́ ikú ẹ̀gbọ́n mi**.
e. **Àsìkò tí mo ń gbádùn ìwé kíkà** ni o pè mí.
ẹ. Bàbá ọdẹ tají **nígbà ti olè dé ojú fèrèsé**.

### 3.2.3.2 Awẹ́ gbólóhùn aṣàpọ́nlé ibi

Awẹ́ gbólóhùn aṣàpọ́nlé ibi ni ó máa ń sọ nípa ibùdó kan pàtó tí ìṣẹ̀lẹ̀ ti wáyé.

(5) a. Mo sùn ní **ibi tí a ti ń gbàdúrà.**
b. Oníròyìn wà ní **ibi tí wọ́n ti dáná sun ọ̀daràn náà**.
d. Ọkọ Bọ́lá kò lọ sí **ibi tí wọ́n ti fẹ́ẹ̀ parí ìjà òun àti ìyàwó rẹ̀**.
e. Èrò pọ̀ ní **ibi tí mo ti fẹ́ẹ̀ repo sí mótò mi**.

### 3.2.3.3 Awẹ́ gbólóhùn aṣàpọ́nlé ibá

Ìsọ̀rí awẹ́ gbólóhùn aṣàpọ́nlé ló ń ṣe àfihàn bí ìṣẹ̀lẹ̀ ṣe wáyé.

(6) a. Bọ́lá ń rìn **bí ẹni tí ẹ̀gbẹ́ ń dùn**.
b. Bùhárí ṣe**bí ẹni tí kò gbọ́ ohun tí alátako ń sọ**.
d. Ọkùnrin náà hùwà **bí ẹni pé òun nìkan ni ólówó**.
e Ó wo ọ̀run yànyàn **bí ẹni tí kò níí kú**.

## 4.0 ÌGÚNLẸ̀

A ti fara balẹ̀ láti ṣe àyẹ̀wò fínnífínní nípa ìsọ̀rí ọ̀rọ̀-àpọ́nlé nínú èdè Yorùbá.

## 5.0 ISỌNÍSÓKÍ

Ní ìpín yìí, ohun tí a yẹ̀wò ni ọ̀rọ̀-àpọ́nlé. Lẹ́yìn tí a fún ọ̀rọ̀-àpọ́nlé ní oríkì ni a wo ìjẹyọ wọ́n lọ́kanòjọ̀kan. Ní pàtàkì, a ṣe àfihàn ìjẹyọ ọ̀rọ̀-àpọ́nlé níbi tí a ti fi hàn wí pé, ó ṣeé ṣekí wọ́n ṣáájú tàbí kí wọ́n gbẹ̀yìn ọ̀rọ̀-ìṣe. Ẹ̀wẹ̀, a tún fi hàn pẹ̀lú àpẹẹrẹ pé, ọ̀rọ̀-àpọ́nlé lè jé ẹyọ ọ̀rọ̀ tàbí kí ó jẹ́ awẹ́ gbólóhùn.

## 6.0 IṢẸ́ ÀYÀNṢE ONÍMÁÀKÌ OLÙKỌ́

1. Lo àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí láti fi wọ́n hàn bí ọ̀rọ̀-àpọ́nlé nínú gbólóhùn: rí, mọ́, tètè, pàpà.
2. Oríṣi ìsọ̀rí mélòó ni a lè pín ọ̀rọ̀-àpọ́nlé sí tí a bá wo ipò ìjẹyọ wọn? Darúkọ wọn.
3. Kí ni àwọn ọ̀rọ̀-àpọ́nlé aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe?
4. Irú àpólà wo ni ó lè ṣe iṣẹ́ àpónlé?
5. Kọ gbólóhùn márùn-ún tó ní awẹ́ gbólóhùn aṣàpọ́nlé, fàlà sí awẹ́ gbólóhùn kọ̀ọ̀kan kí o sì sọ irú iṣẹ́ àpọ́nlé tó ṣe.

## 7.0 ÀWỌN ÌWÉ FÚN KÍKÀ

Awobuluyi, Oladele (1978). *Essentials of Yoruba Grammar*. UPL. Oxford University Press, Ibadan. Chapter 3

Awobuluyi, Oladele (2013). *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá.* ATMAN Limited. Osogbo. o.i 138-166.

Bámgbóṣé, Ayọ̀. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*.o.i. 153-158

Yusuf, Ọrẹ. (1995). *Gírámà Yorùbá Àkọ̀tun.*o.i. 26-27.

# MÓDÙ 2

Ìpín 1 Wúnrẹ̀n Aṣegírámà
Ìpín 2 Ìhungbólohùn: Àwọn Àpólà
Ìpín 3 Gbólóhùn Abọ́dé
Ìpín 4 Gbólóhùn Alákànpọ̀
Ìpín 5 Gbólóhùn Oníbọ̀ I

## ÌPÍN 1 WÚNRẸ̀N AṢEGÍRÁMÀ

**Àkóónú**

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
3.1 Oríkì
3.2 Ìpińsísọ̀rí Wúnrẹ̀n Aṣegírámà
3.2.1 Wúnrẹ̀n AṣegírámàAtọ́kaàsìkò
3.2.2 Wúnrẹ̀n Aṣegírámà ibá ìṣẹ̀lẹ̀
3.2.3 Wúnrẹ̀n Aṣegírámà ìyísódì
3.2.4 Wúnrẹ̀n Aṣegírámà aṣàfihàn
3.2.5 Wúnrẹ̀n Aṣegírámà Ìtẹnumọ́
3.2.6 Wúnrẹ̀n Aṣegírámà amúpé
4.0 Ìgúnlẹ̀
5.0 Isọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Àyànṣe Onímáàkì Olùkọ́
7.0 Àwọn Ìwé fún Kíkà

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ní ìpín kììní múdù yìí ni a ti máa ṣe àyèwò àwọn ọ̀rọ̀ tí a mọ̀ sí wúnrẹ̀n aṣegírámà lédè Yorùbá.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ

Èròǹgbà mi ni kí ǹ lè jẹ́ kí o mọ ọ̀kanòjọ̀kan àwọn ọ̀rọ̀ lédè Yorùbá tí a kà sí wúnrẹ̀n aṣegírámà, ìlò àti ìjẹyọ wọn.

## 3.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Àwọn ohun tí a máa gbé ṣe ni kí n kọ́kọ́ fún wúnrẹ̀n aṣegírámà ní oríkì, kí n̄ wáá tẹ̀síwájú láti pín wọn sí ìsọ̀rí ìsọ̀rí pẹ̀lu àpẹẹrẹ àti ìlò wọn nínú gbólóhùn. Ní ìparí mo gbèrò láti ṣe àgbékalẹ̀ ìbéèrè fún ìgbéléwọ̀n àwọn akẹ́kọ̀ọ́.

## 3.1 Oríkì

Wúnrẹ̀n Aṣegírámà ni àwọn ọ̀rọ̀ Yorùbá tí wọn kò dá ìtumọ̀ ní fúnra wọ ntí wọn bá dúró ní wóró tàbí ẹyọ ọ̀rọ̀. Kìkì ìgbà tí a bá lò wọ́n pọ̀ mọ́ ọ̀rọ̀ mìíràn nínú àpólà tàbí gbólóhùn ni ìtumọ̀ wọn tó máa ń fara hàn tẹ jáde.

## 3.2 Ìpińsísọ̀rí Wúnrẹ̀n Aṣegírámà

Oríṣiríṣi ìsọ̀rí ni wúnrẹ̀n aṣegírámà ti lè jẹ yọ nínú èdè Yorùbá. Mẹ́fà irú ìsọ̀rí bẹ́ẹ̀ ni a máa mẹ́nubà ní sísẹ̀ǹtẹ̀lé nísàlẹ̀.

### 3.2.1 Wúnrẹ̀n AṣegírámàAtọ́kaàsìkò

Wúnrẹ̀n atọ́ka àsìkò ni àwon ọ̀rọ̀ tàbí wúnrẹ̀n tí wọ́n ń tọ́ka sí àkókò tí ìṣẹ̀lẹ̀ kan wáyé tàbí àkókò tí olùsọ̀rọ̀ ń sọ̀rọ̀ nípa ìṣẹ̀lẹ̀ kan. Nínú èdè Yorùbá, oríṣi àsìkò méjì ni àwọn onímọ̀ ti tọ́ka sí. Àwọn àsìkò méjì náà ni: àsìkò ọjọ́ iwájú àti àsìkò afànámónìí (ìyẹn, àsìkò tó pa àná pọ̀ mọ́ òní).

Àsìkò ọjọ́ iwájú niàsìkò tó ń fi ìṣẹ̀lẹ̀ tí kò tíì wáyé ní àsìkò tí olùsọ̀rọ̀ ń sọ nípa ìṣẹ̀lẹ̀ kan pàtó. Àwọn wúnrẹ̀n àsìkò ọjọ́ iwájú ni: **yóò** tàbí ẹ̀dà rẹ̀ **óò/ó**, **á** àti **máa**, gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn nínú gbólóhùn ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

(1) a. Bùhárí **yóò** yan olùbánidámọ̀ràn tuntun.
b. Bùhárí **óò** yan yan olùbánidámọ̀ràn tuntun.
d. Bùhárí **ó** yan olùbánidámọ̀ràn tuntun.
e. Bùhárí **á** yan olùbánidámọ̀ràn tuntun
ẹ. Bùhárí **máa** yan olùbánidámọ̀ràn tuntun.

Àsìkò afànámónìí ni àsìkò tó pa ìṣẹ̀lẹ̀ tó ti ṣẹ̀ tàbí àsìkò ìṣẹ̀lẹ̀ èyí tó ń ṣẹ̀ lọ́wọ́lọ́wọ́ pọ̀. Ohun mẹ́ta ló ṣe pàtàkì láti tọ́ka sí níbí. Èkíní ni wí pé irú ọ̀rọ̀-ìṣe ló máa fi hàn bóyá ìṣẹ̀lẹ̀ tó ti sẹ̀ tàbí èyí tó ń ṣẹ̀ ní àkókò tí olùsọ̀rọ̀ ń sọ̀rọ̀ lọ́wọ́lọ́wọ́ ni (2).

(2) a. Ẹ̀bùn **ún** dé.
b. Ẹ̀bùn **ún** sùn.
d. Ẹ̀bùn **ún** lọ.
e. Ẹ̀bùn **ún** jẹ ẹ̀bà.
ẹ. Ẹ̀bùn **ún** fọ aṣọ.

Bí a bá wo (2a), ó ṣeé ṣe kí ìtumọ̀ rẹ̀ jẹ́ ti ìṣẹ̀lè tó ti wáyé ṣáájú àkókò tí olùsọ̀rọ̀ ń sọ̀rọ̀, b.a. **Ẹ̀bùn ún dé ní àná**. Ó sì ṣeé ṣe kó jẹ́ wí pé bí olùsọ̀rọ̀ ti ń sọ̀rọ lọ́wọ́ ló ń wo Ẹ̀bùn ní ọ̀ọ́kán tó wá sọ pé, **Ẹ̀bùn ún dé**, ìyẹn nìṣẹ̀lẹ̀ tòní tàbí ìṣẹ̀lẹ̀ tó ń ṣẹlẹ̀ lọ́wọ́ lọ́wọ́ ní àkókò tí olùsọ̀rọ̀ ń sọ̀rọ̀. Ṣùgbọ́n ní àpẹẹrẹ (2d) àti (2e), ìtùmọ̀ àsìkò tí gbólóhùn wọ̀nyẹn gbé jáde ni ti àkókò ìṣẹ̀lẹ̀ tó ti ṣẹ̀ tí a pè ní ìṣẹ̀lẹ̀ àná.

Èkejì ni wí pé wúnrẹ̀n àsìkò afànámónìí kò ní ìrísí kan fúnra rẹ̀. Ìrísí fáwẹ̀lì ọ̀rọ̀-orúkọ tàbí ti ọ̀rọ̀-ẹ̀yán tó tẹ̀lé ọ̀rọ̀-orúkọ ni wúnrẹn àsìkò náà máa ń ní.

(3) a. Ẹ̀b**ùn ún** dé.
b. Ẹ̀b**à á** sú ẹ.
d. Ig**i í** dá.
e. Òj**ò ó** rọ̀.
ẹ. Tẹ̀t**ẹ̀ ẹ́** tẹ́.
f. Àkàr**à á** tú sépo.

Ẹ̀kẹta ni wí pé ohùn òkè ni wúnrẹ̀n náà máa ń ní. Ẹ wo àpẹẹrẹ (2) àti (3). Mo fẹ́ kí o mọ̀ pé, nínú àkọtọ́ Yorùbá a kì í fi wúnrẹ̀n náà hàn.

### 3.2.2 Wúnrẹ̀n Aṣegírámà ibá ìṣẹ̀lẹ̀

Wúnrẹ̀n Aṣegírámà ibá ìṣẹ̀lẹ̀ ni ó máa ń sọ nípa ọ̀nà tí ìṣẹ̀lẹ̀ gbà wáyé. Oríṣi ibá ìṣẹ̀lẹ̀ mẹ́ta ló wà:

(3) a. Ibá ìṣẹ̀lẹ̀ àṣetán
b. Ibá ìṣẹ̀lẹ̀ lọ́wọ́lọ́wọ
d. Ibá ìṣẹ̀lẹ̀ bárakú

Ibá ìṣẹ̀lẹ̀ àṣetán ni ó máa ń jẹ́ kí a mọ̀ pé ní àkókò tí olùsọ̀rọ̀ ń sọ̀rọ̀, ìṣẹ̀lẹ̀ tó ń sọ nípa rẹ̀ ti parí. Wúnrẹ̀n aṣegírámà ibá ìṣẹ̀lẹ̀ àṣetán ni **ti**.

(4) a. Ẹ̀bùn ún **ti** dé.
b. Ọ̀daràn **ti** wà ní ẹ̀wọ̀n.
d. Owó **ti** tán.

Ibá ìṣẹ̀lẹ̀ lọ́wọ́ lọ́wọ́, gẹ́gẹ́ bí orúkọ rẹ̀ ni ó máa ń sọ nípa ìṣẹ̀lẹ̀ tó wáyé ní àkókò tí olùsọ̀rọ̀ kan ń sọ̀rọ̀. Wúnrẹ̀n aṣegírámà ibá ìṣẹ̀lẹ̀ lọ́wọ́ lọ́wọ́ ni **ń**. Àpẹẹrẹ ìjẹyọ rẹ̀ ló wà ní (5).

(5) a. Ẹ̀bùn **ń** bọ̀.
b. Ẹ̀bùn **ń** lọ sí ọjà.
d. Ẹ̀bùn**ń**sùn.

Ibá ìṣẹ̀lẹ̀ bárakú ni ìṣẹ̀lẹ̀ gbogbo ìgbà. Ìyẹn ni pé ìṣẹ̀lẹ̀ tó ṣeé ṣe kó ṣẹ̀ lánàá, lónìí tó tún ṣeé ṣe kó ṣẹlẹ̀ lọ́la. Wùnrẹ̀n **máa** àti **ń** ló para pọ̀ ṣe àfihàn ibá ìṣẹ̀lẹ̀ bárakú. Ẹ wo àpẹẹrẹ díẹ̀ ní (6).

(6) a. Lọ́yà **máa ń** lọ sílé ẹjọ́.
b. Olùkọ́ **máa ń**dúró ní yàrá ìkẹ́kọ̀ọ́.
d. Àgbẹ̀ **máa ń**fẹ́ kí òjò rọ̀.
e. Ọmọdé **máa ń**sọkún.

### 3.2.3 Wúnrẹ̀n Aṣegírámà ìyísódì

Wúnrẹ̀n Aṣegírámà ìyísódì ni ó máa ń yí gbólóhùn tàbí ọ̀rọ̀-orúkọ sí òdì. Àwọnwúnrẹ̀n Aṣegírámà ìyísódì ni **kò**, **kọ́**, **kì**, **má**. Ẹ jẹ́ ká fi wọ́n hàn nínú àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀.

(7) a. Bùkọ́lá **kò** wọlé ìbò.
b. Bàbá **kọ́** ni ó fú ọmọ rẹ̀ lóyún.
d. Ìyàwó mi **kì** í gba ìgbàkúgbà.
e. **Má** dá mi dá bùkátà mi.

Gẹ́gẹ́ bí ó ti ṣe hàn ní àpẹẹrẹ òkè, mẹ́rin ni wúnrẹ̀n ìyísódì. Èyí tó gba àlàyé díẹ̀ ni ti (7d) tí ó jẹ́ àpapọ̀ wúnrẹ̀n arọ́pò-orúkọ ẹnikejì àti ìyísódì ṣùgbọ́n tí kò ṣeé tú palẹ̀.

### 3.2.4 Wúnrẹ̀n Aṣegírámà aṣàfihàn

Wúnrẹ̀n Aṣegírámà aṣàfihàn ni a máa ń bá pàdé ní sàkání ọ̀rọ̀-orúkọ. Iṣẹ́ wọn jọ mọ́ ẹ̀yán. Àwọn ọrọ tí a kà sí wúnrẹ̀n aṣegírámà aṣàfihàǹ ni náà, yìí, yẹn, wọ̀nyí, wọ̀nyẹn. Ìjẹyọ wọn ló wà nínú àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀.

(8) a Aṣọ **náà** dára
b. Aṣọ **yìí** dára
d. Aṣọ **yẹn** dára
e. Aṣọ **wọ̀nyí** dára
ẹ. Aṣọ **wọ̀nyẹn** dára

Àwọn wúnrẹ̀n yẹn ṣeé pín sí méjì nípa ìrísí àti ìtumọ̀: **náà** dá dúró nígbà tí àwọn mẹ́rin tó kù wà nísọ̀rí mìíràn. Ní ti àwọn mẹ́rin tó kù, àwọn náà tún pín sí ọ̀wọ́ méjì bó ṣe hàn ní ìsàlẹ̀.

(9) **Ẹyọ** **Ọ̀pọ̀**
yìí wọ̀n-yìí
yẹn wọ̀n-yẹn

Àpẹẹrẹ ìjẹyọ wọn ló ti wà ní (8) òkè.

### 3.2.5 Wúnrẹ̀n Aṣegírámà Ìtẹnumọ́

Wúnrẹ̀n Aṣegírámà ìtẹnumọ́ ni ó máa ń tẹ̀lé ọ̀rọ̀-orúkọ, àpólà orúkọ tàbí odindi gbólóhùn tí a bá ṣe ìtẹnumọ́. Wúnrẹ̀n Aṣegírámà kan ṣoṣo ló ń ṣe iṣẹ́ ìtẹnumọ́ nínú èdè Yorùbá. Òun náà ni **ni** gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn nínú àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀.

(10) a. Táyé **ni** ó jẹ ẹ̀bà.
b. Táyé Ajíbóyè **ni** Bọ́lá fẹ́ràn.

d. Jíjẹ **ni** Táyé Ajíbóyè jẹ ẹ̀bà.

(11) a. Táyé jẹ ẹ̀bà.
b. Bọ́lá fẹ́ràn Táyé Ajíbóyè
d. Táyé Ajíbóyè jẹ ẹ̀bà.

Ó ṣe pàtàkì kí o mọ̀ pé a ṣẹ̀dá àwọn gbólóhùn (10) láti ara gbólóhùn tó wà ní (11) nísàlẹ̀ yìí ni.
Àmọ́ sáá, àwọn onímọ̀ gírámà kan máa ń dígbà pe wúnrẹ̀n yìí ní ọ̀rọ̀-ìṣe ṣùgbọ́n jíjọ ló jọ, kò rí bẹ́ẹ̀. Ẹ fi àwọn àpẹẹrẹ (12) wé (10).

(12) a. Adé kò ni ara rẹ̀.
b. Adé kọ́ ni ó niara rẹ̀.

Ohun tí mo fẹ́ẹ́ kí ó yé ẹ ni wí pé **ni** tó wà ní (10) yàtọ̀ sí èyí tó wà ní (12). Mo tún fẹ́ẹ́ tọ́ka sí irúfẹ́ **ni** kan tí àwọn onímọ̀ Gírámà kan tún máa ń pè ní ọ̀rọ̀-ìṣe. Ẹ wo àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀.

(13) a. Àgbẹ̀ jẹ́ ọba.
b. Ọba **ni** àgbẹ̀.

Lójú àwọn onímọ̀ tí a mẹ́nubà lóke, ọ̀rọ̀-ìṣe ni **ni** tó wà ní (13b). Ṣùgbọ́n tí o bá fara balẹ̀ wò ó dáadáa, wà á ri wí pé ọ̀rọ̀ kò rí bẹ́ẹ̀ rárá. Lójú tèmi, ìgékúrú ni (13b). Ẹkún rẹ́rẹ́ gbólóhùn náà ni ó wà ní (14).

(14) Ọba **ni** àgbẹ̀ jẹ́.

Ìdí ni wí pé láti ara (13a) ni a ti ṣẹ̀dá (14) kí ọ̀rọ̀-ìṣe **jẹ́**, tó di pípajẹ.

### 3.2.6 Wúnrẹ̀n Aṣegírámà amúpé

Wúnrẹ̀n aṣegírámà amúpé ni wúnrẹ̀n tí ó máa ń jẹ́ orí fún awẹ́ gbólóhùn. Àpẹẹrẹ wọnni **pé, kí, tí,** abbl.

(15) a. Láyí sọ **pé** epó wọ́n ní ọjà.
**Pé** ìjọba fi kún owó epo, kò bójú mu
Bọ́lá gbà **pé** òun rẹwà.

b. Adé dábàá **kí** a lọ sí ìrìnà jò náà.
**Kí** ajá yẹn má bàá jáde, ẹ só mọ́lẹ̀.
Ó dára **kí** a pàgọ́ mẹ́ta.

d. Ìyá **tí** ọmọ rẹ̀ kò gbọ́ràn
Olùkọ́ na ọmọ **tí** ó bú bàbá rẹ̀.
Pé ẹ dìbò fún wa àbí ẹ kò dìbò fún wa, kò fàjà

## 4.0 ÌGÚNLẸ̀

Iṣẹ́ ìpín yìí ti mú mi ṣe àyẹ̀wò oríṣiríṣi wúnrẹ̀n aṣegírámà lédè Yorùbá àti ìjẹyọ wọn.

## 5.0 ISỌNÍSÓKÍ

Ní ìpín yìí ni a ti ṣe àgbéyẹ̀wò oríṣiríṣi wúnrẹ̀n aṣegírámà tó wà lédè Yorùbá, ibi tí wọ́n ti lè jẹ yọ àti ìtumọ̀ tí wọ́n ní. Ní pàtàkì, a wo sàkání mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tí wúnrẹ̀n aṣegírámà timáa ń wáyé, ìyẹn sàkání àpólà-orúkọ, àpólà-ìṣe àti àpólà amúpé.

## 6.0 IṢẸ́ ÀYÀNṢE ONÍMÁÀKÌ OLÙKỌ́

1. Kí ni a ń pè ní wúnrẹ̀n aṣegírámà?
2. Irú wúnrẹ̀n aṣegírámà wo ni àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí: **ti**, **máa**, **pé**, **kò**?
3. Kí ni wúnrẹ̀n aṣegírámà ibá ìṣẹ̀lẹ̀ bárakú?
4. Oríṣi **ni** mélòó ló wà lédè Yorùbá?
5. a. Irú wúnrẹ̀n wo nìwọ̀nyí: **yìí**, **náà**, **yẹn**?
   b. Kí ni ìjọra àti ìyàtọ̀ tó wà láààrín wọn?

## 7.0 ÀWỌN ÌWÉ FÚN KÍKÀ

Awobuluyi, Oladele (1978). *Essentials of Yoruba Grammar*. UPL. Oxford University Press, Ibadan. Chapter 3

Awobuluyi, Oladele (2013). *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá.* ATMAN Limited. Osogbo.

Bámgbóṣé, Ayọ̀. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*.

# ÌPÍN 2 ÌHUN GBÓLOHÙN I: ÀWỌN ÀPÓLÀ

**Àkóónú**

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
3.1 Oríkì
3.2 Ìpińsísọ̀rí àwọn àpólà
3.2.1 Àpólà-orúkọ
3.2.2 Àpólà-ìṣe
3.2.3 Àpólà-atọ́kùn
3.2.4 Àpòlà-ìyísódì
3.2.5 Àpólà-àpọ́nlé
4.0 Ìgúnlẹ̀
5.0 Isọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Àyànṣe Onímáàkì Olùkọ́
7.0 ÀwọnÌwé FúnKíkà

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Gbólóhùn ni ìpèdè tó jẹ́ àtòpọ̀ ọ̀rọ̀ ní ìlànà tó bá òfin gírámà mu, tó sì ní ìtumọ̀ kíkún. Àwọn ọ̀rọ̀ inú gbólóhùn máa n wà lábẹ́ àkóso oríṣiríṣi àpólà.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ

Ní ìparí ìpín ẹ̀kọ́ yìí, ó yẹ kí akẹ́kọ̀ọ́ lè dá oríṣiríṣi àpólà mọ̀ kí wọ́n sì lè mọ àkóónú ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn.

## 3.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

A gbèrò láti ṣe iṣẹ́ lórí oríṣiríṣi àpólà lédè Yorùbá.

### 3.1 Oríkì

Àpólà ni àtòpọ̀ ọ̀rọ̀ tí a mọ̀ sí fọ́nrán tí wọ́n ní ohun àjọni tó pa àwọn ọ̀rọ̀ inú fọ́nrán náà pọ̀.

### 3.2 Ìpińsísọ̀rí àwọn àpólà

Ohun àkọ́kọ́ ni kí ǹ ṣe àyẹ̀wò àkóónú gbólóhùn nípa irú àpólà tí a lè bá níbẹ̀. Márùn-ún nínú àpólà èdè Yorùbá ni màá yẹ̀wò níbí.

### 3.2.1 Àpólà-orúkọ

Ọ̀kan pàtàkì ni àpólà orúkọ jẹ́ nínú ìhun gbólóhùn. Ohun tí ó ṣe pàtàkì nínú àpólà yìí ni ọ̀rọ̀-orúkọ. Ó tilẹ̀ ṣeé ṣe kí àpólà orúkọ má ní ju ọ̀rọ̀-orúkọ nìkan lọ. Nítorí náà, àpólà orúkọ ni fọ́nrán tí ó ní ọ̀rọ̀-orúkọ, tí ó sì ṣeé ṣekí ó ní ẹ̀yán kan tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ. Àpólà orúkọ tí mo fẹ́ẹ́ kọ́kọ́ fi hàn ni àpólà orúkọ ọ̀bọ̀rọ́. Irú àpólà orúkọ yìí jẹ́ ọ̀bọrọ́ nípa wí pé ọ̀rọ̀-orúkó nìkan ló máa ń wà nínú àpólà bẹ́ẹ̀, kì í sí ọ̀rọ̀-ẹ̀yán kankan.

(1) a. ewúrẹ́
b. igi

Apólà-orúkọ lè jẹ́ àpapọ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ àti ẹ̀yán rẹ̀.

(2) a. **ewúrẹ́** dúdú
b. **igi** gíga

Níwọ̀n bí ó ti jẹ́ wí pé orísìrísì ẹ̀yán ló wà, màá wo àpólà orúkọ lábẹ́ ìsọ̀rí ẹ̀yán tí a ti mẹ́nubà ṣáájú.

(3) a. Apólà orúkọ pẹ̀lú ẹ̀yán aṣàpèjúwe
**Ajá** ńlá
**Ọkọ** gbọ̀lọ̀kù

b. Apólà orúkọ pẹ̀lú ẹ̀yán olóhun
**Ajá** Òjó
**Ilé** ọba

d. Apólà orúkọ pẹ̀lú ẹ̀yán ajẹmáwọ̀
**Ọkọ̀** funfun
**Ìwé** pupa

e. Apólà orúkọ pẹ̀lú ẹ̀yán ajórúkọ
**Ará** Èkó
**Ọmo** oko

ẹ Apólà orúkọ pẹ̀lú ẹ̀yán ajẹmóṣe
**Igi** gíga
**Ajá** burúkú

f. Apólà orúkọ pẹ̀lú ẹ̀yánaṣòùnkà
**Ajá** púpọ̀
**Ilé** méjọ

g. Apólà orúkọ pẹ̀lú ẹ̀yán aṣàfihàn
**Aṣọ** yẹn

**Ọmọ** náà

gb. Apólà orúkọ pẹ̀lú ẹ̀yán awẹ́ gbólóhùn
**Ìwé** tí mo rà
**Ọmọ** tí mo bí

Yàtọ̀ sí àpólà-orúkọ tí ó jẹ́ pé ọ̀rọ̀-orúkọ kan àti ẹ̀yán kan péré ló jẹyọ nínú rẹ̀, ó ṣeé ṣe kí àpólà orúkọ ní ju ẹ̀yán kan lọ.

(4) a. ilé **ńlá kan**
b. ọkọ **pupa méje wọ̀nyẹn**
d. ajá **dúdú tí mo rà yìí**
e. ògbóǹtagi **oníròyìn náà**
ẹ. aṣọ **pupa kan ṣoṣo náà tí mo fún ẹ yẹn**

Ohun kan kù tí mo fẹ́ ṣe kí n tó gúnlẹ̀ ní ìpín yìí ni kí n wo bí àwọn ẹ̀yán wọ̀nyí ṣe ń tò léra wọn nínú àpólà orúkọ tí wọ́n bá ti pé méjì tàbí jù béẹ̀ lọ.

(5) a. ajá **dúdú**
b. ajá **dúdú méjì**
d. ajá **dúdú kan ṣoṣo**
e. ajá **dúdú burúkú méjì**
ẹ. ajá **dúdú burúkú méjì náà**
f ajá **dúdú burúkú méjì yìí náà**
g. ajá **dúdú ńlá burúkú méjì yìí náà**
gb. ajá **dúdú ńlá burúkú méjì tí mo rà yìí náà**

### 3.2.2 Àpólà-ìṣe

Àpólà-ìṣe ni fọ́nrán tí àkóónú rẹ̀ máa ń jẹ́ àtòpọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe àti àwọn ọ̀rọ̀ mìíràn tó níí ṣe pẹ̀lú ọ̀rọ̀-ìṣe.

(5) a. wá owó
b. kí ọba

Gẹ́gẹ́ bí ti àpólà orúkọ, ohun tó ṣe pàtàkì jù lọ nínú àpólà ìṣe ni ọ̀rọ̀-ìṣe fúnra rẹ̀. Ohun tó kàn ni àfihàn oríṣiríṣi àpólà-ìṣe pẹ̀lú àpẹẹrẹ.

(6) a. Apólà ìṣe (ọ̀rọ̀-ìṣe + àbọ̀ tàárà)
**jẹ** iṣu
**ní** owó

b. Apólà ìṣe (ọ̀rọ̀-ìṣe + àbọ̀ pẹ́ẹ̀kí)
**wà** ní ìta
**sùn** sí ilé

d. Apólà ìṣe (ọ̀rọ̀-ìṣe + àbọ̀ tààrà + àbọ̀ pẹ́ẹ̀kí)
**jẹ** iṣu ní ilé
**wo** kòkòrò pẹ̀lú awò ojú

e. Apólà ìṣe (ọ̀rọ̀-ìṣe + òrọ̀ àpọ́nlé)
**rìn** jàùjàu
tètè **lọ** sí ọjà

ẹ Apólà ìṣe (ọ̀rọ̀-ìṣe + gbólóhùn arótì)
**sùn** ní ìgbà tí Dókítà ń ṣe iṣẹ́ abẹ
**kígbe** ní ìgbà tí mo gbọ́ ikú ẹ̀gbọ́n mi
**wà** ní ibi tí wọ́n ti ń dáná irọ́
**hùwà** bí ẹni pé òun nìkan ni ó lówó

### 3.2.3 Àpólà-atọ́kùn

Àpólà atọ́kùn ni àtòpọ̀ ọ̀rọ̀-atọ́kùn àti ọ̀rọ̀-orúkọ tàbí àpólà-orúkọ. Nínú àpólà atọ́kùn, ọ̀rọ̀-atọ́kùn ló máa ń ṣáájú, tí àpólà-orúkọ á wáá tẹ̀le.

(7) a. **ní** ilé ìtajà
b. **ní** ọjà òyìngbò
d. **sí** Gbàgádà
e. **sí** àwọ ará Èkó
ẹ. **pẹ̀lú** ọ̀bẹ olójú méjì
f. **ní** ẸgbáAláké
g. **ti** Èkó lọ sí Ìbàdàn

Tí o bá farabalẹ̀ wo àwọn ọ̀rọ̀-atọ́kù ninú àpẹẹrẹ òkè wà á ri wí pé, ṣe ni ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn jẹ yọ ṣáájú àpólà-orúkọ.

### 3.2.4 Àpòlà-ìyísódì

Àpòlà ọ̀rọ̀-ìyísódì gẹ́gẹ́ bí orúkọ rẹ̀ ni ọ̀rọ̀-ìyísódì àti àwọn ọ̀rọ̀ tàbí àpólà tó lè tẹ̀le.

(8) a. **kò** wá sí ilé
b. **kì** í wá sí ilé

### 3.2.5 Àpólà-àpọ́nlé

Àpólà àpọ́nlé jẹ́ àtòpọ̀ ọ̀rọ̀ tí ọ̀rọ̀-àpọ́nlé jẹ́ orí fún. Gẹ́gẹ́ bí ti àwọn àpólà tókù, ohun tó ṣe pàtàkì nínú àpólà yìí ni ọ̀rọ̀-àpọ́nlé. Àwọn ọ̀rọ̀-àpọ́nlé ni a sà lámí dúdú kiki nínú àpẹẹrẹ kọ̀ọ̀kan wọ̀nyẹn.

(9) a. **tètè** jẹ iṣu
b. **kúkú** wá sí ọjà

d. **pàpà** kú ikú òjijì
e. **wulẹ̀** na ọmọ pa

Mo fẹ́ kí o mọ̀ wí pé ọ̀rọ̀-àpọ́nlé lè ju ẹyọ kan lọ nínú àpólà àpọ́nlé.

(10) a. **tètè kúkú** gún iṣu **ní odó**
b. **pàpà kúkú** wá **sí ọjà**
d. **tilẹ̀** jẹ ilá **rí**
e. (kò) **wulẹ̀** na ọmọ **mọ́**
ẹ. kò lọ **mọ́ rárá**

Ní àpẹẹrẹ tó wà ní (10), oríṣiríṣi àpólà àpọ́nlé àti ọ̀rọ̀-ìṣe ló wà níbẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, ní (10a), "**tètè kúkú** gún" àti "gún**…ní odó"**; ní (10b), ẹyọ àpólà àpọ́nlé méjì, ìyẹn "**pàpà kúkú** wá" àti "wá **sí ọjà"** ló wà níbẹ̀. Ẹ̀wẹ̀ ní (10d), "**tilẹ̀** jẹ" àti "jẹ…**rí**" ni àpólà àpọ́nlé àti ọ̀rọ̀-ìṣe tí wọ́n pọ́n lé. Bẹ́ẹ̀ ni ọ̀rọ̀ rí ní ti àpẹẹrẹ kan tó kù.

## 4.0 ÌGÚNLẸ̀

A ti wo oríṣiríṣi àpólà tó wà lédè Yorùbá.

## 5.0 ISỌNÍSÓKÍ

Ohun tí mo ṣe ní ìpín yìí ni àyẹ̀wo ìhun gbólóhùn níbi tí mo ti ṣe àgbéyẹ̀wò àpólà márùn-ún pàtàkì: àpólà-orúkọ, àpólà-ìṣe, àpólà-atọ́kùn, àpólà-ìyísódì àti àpólà-àpọ́nlé tí mo sì ti fi ohun tó ṣe pàtàkì nínú àpólà kọ̀ọ̀kan hàn. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, mo jẹ́ kí ó yé ẹ wí pé ọ̀rọ̀-orúkọ ló ṣe pàtàkì nínú àpólà-orúkọ, nígbà tí ọ̀rọ̀-ìṣe jẹ́ kòṣeémánìí nínú àpólà-ìṣe abbl.

## 6.0 IṢẸ́ ÀYÀNṢE ONÍMÁÀKÌ OLÙKỌ́

1. Dárúkọ àpólà méjì pàtàkì tí a lè bá pàdé nínú gbólóhùn Yorùbá.
2. Dárúkọ oríṣi àpólà orúkọ márùn-ún pẹ̀lú àpẹẹrẹ.
3. Dárúkọ oríṣi àpólà ìṣe márùn-ún pẹ̀lú àpẹẹrẹ.
4. Kí ni o fi lè dá àpólà kan pàtó mọ̀? Fi àpẹẹrẹ tó jọjú ṣègbè lẹ́yìn ìdáhùn rẹ.
5. Kọ àrokọ kíkún lórí àpólà-ìṣe lédè Yorùbá kí o sì jẹ́ kí àròkọ rẹ kún fún ọ̀pọ̀ àpẹẹrẹ.

## 7.0 ÀWỌNÌWÉ FÚNKÍKÀ

Awobuluyi, Oladele (1978). *Essentials of Yoruba Grammar*. UPL. Oxford University Press, Ibadan.

Awobuluyi, Oladele (2013). *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá.* ATMAN Limited. Osogbo. Bámgbóṣé, Ayọ̀. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*.o.i. 118-130.

Yusuf, Ọrẹ. 1995. *Gírámà Yorùbá Àkọ̀tun*. (1995). o.i. 21-22.

# ÌPÍN 3 GBÓLÓHÙN ABỌ́DÉ

## Àkóónú

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
  3.1 Oríkì gbólóhùn abọ́dé
  3.2 Ìpinsísọ̀rí gbólóhùn abọ́dé
    3.2.1 Gbólóhùn abọ́dé kíkún
    3.2.2 Gbólóhùn abọ́dé aláìgbàbọ̀
    3.2.3 Gbólóhùn abọ́dé aláìlólùwà
    3.2.4 Gbólóhùn abọ́dé oníwóró ọ̀rọ̀-ìṣe
4.0 Ìgúnlẹ̀
5.0 Isọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Àyànṣe Onímáàkì Olùkọ́
7.0 Àwọn Ìwé Fún Kíkà

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ní ìpín yìí, a fẹ́ẹ̀ ṣe àgbéyẹ̀wò gbólóhùn abọ́dé gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan nínú ìhun gbólóhùn Yorùbá.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ

Èròǹgbà mi ni kí n̄ lè ṣe àlàyé tó jinlẹ̀ nípa gbólóhùn abọ́dé, àwọn àbùdá rẹ̀ àti bí akẹ́kọ̀ọ́ yóò ṣe lè da oríṣiríṣi wọn mọ̀.

## 3.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ iṣẹ́ mi ní ìpín módù yìí ni ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé lórí gbólóhùn abọ́dé.

### 3.1 Oríkì gbólóhùn abọ́dé

Gbólóhùn abọ́dé ni irúfẹ́ gbólóhùn tí a ti máa ń ṣe alábàpàdé ẹyọ ọ̀rọ̀-ìṣe kan péré. Ohun tí a pè ní gbólóhùn abọ́dé lè kéré, ó sì lè gùn. Kìkì ohun tó ṣe pàtàkì láti sọ niwí pé bó ti wù kó kéré tó tàbí gùn tó, ó gbọ́dọ̀ ni ọ̀rọ̀-ìṣe kan, kò sì gbọ́dọ̀ ní ju ọ̀rọ̀-ìṣe kan lọ.

### 3.2 Ìpinsísọ̀rí gbólóhùn abọ́dé

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé a ti fi hàn pé gbólóhùn abọ́dé kò gbọ́dọ̀ ní ju ọ̀rọ̀-ìṣe kan lọ, ìyẹn kò sọ pé oríṣi gbólóhùn abọ́dé kan náà ni ó wà. Ohun tó kàn ni kí a wo oríṣiríṣi ìsọ̀rí gbólóhùn abọ́dé tó wà.

### 3.2.1 Gbólóhùn abọ́dé kíkún

Ohun tí mo pè ní gbólóhùn abọ́dé kíkún ni èyí tó ní àpólà orúkọ olùwà àti àpólà orúkọ àbọ̀. Àpẹẹrẹ ni ó wà ní (1).

(1) a. Àgbẹ̀ gbin iṣu
b. Tíṣà kékeré na akẹ́kọ̀ọ́ gíga
d. Ewúrẹ́ dúdú ńlá jẹ iṣu tútù méjì kan
e. Ewúrẹ́ dúdú kékeré bọ̀lọ̀jọ̀ mẹ́ta péré jẹ iṣu ewùrà tútù méjì ńlá ńlá kan

Bí a bá fi (1a) wé (1d), ní ti iye ọ̀rọ̀, (1d) gùn ní ìlọ́po mẹ́ta àti àbọ̀, ṣùgbọ́n nípa àbùdá ìhun, gbólóhùn abọ́dé ni àwọn méjèèjì nítorí ẹyọ ọ̀rọ̀-ìṣe kọ̀ọ̀kan ni wọ́n ní.

### 3.2.2 Gbólóhùn abọ́dé aláìgbàbọ̀

Gbólóhùn abọ́dé aláìgbàbọ̀ ni èyí tó jẹ́ pé kìkì àpólà orúkọ olùwà àti ọ̀rọ̀-ìṣe nìkan ló wà nínú rẹ̀.

(2) a. Àgùtan bọ̀lọ̀ jọ̀ sùn
b. Akíntọ̀lá takú.
d. Mo wà.
e. Olú dúró

### 3.2.3 Gbólóhùn abọ́dé aláìlólùwà

Gbólóhùn abọ́dé aláìlólùwà ni ó jẹ́ pé kìkì ọ̀rọ̀-ìṣe àti àpólà orúkọ tó wà nípò àbọ̀ ló máa ń wà nínú rẹ̀.

(3) a. Jẹ iṣu
b. Mu omi
d. Wá sí ilé mi
e. Lọ pọn omi lódò

Àbùdá àdáni irúfẹ́ gbólóhùn yìí ni wí pé gbólóhùn ìpàṣẹ ni wọ́n.

### 3.2.4 Gbólóhùn abọ́dé oníwóró ọ̀rọ̀-ìṣe

Awọn gbólóhùn kan tún wà tó jẹ́ pé kìkì ọ̀rọ̀-ìṣe nìkan ni wọ́n máa ń ní. Wọ́n fi ohun kan jọ gbólóhùn abọ́dé aláìlólùwà ní ti pé àṣẹ ni wọ́n máa ń fi wọ́n pa.

(4) a. Jáde
b. Gbà
d. Padà
e. Wá

## 4.0 ÌGÚNLẸ̀

Mo ti ṣe àlàyé tó jinlẹ̀ lóri ọ̀kanòjọ̀kan gbólóhùn abọ́dé lédè Yorùbá.

## 5.0 ISỌNÍSÓKÍ

Ààyẹ̀wò fínní fínní lórí gbólóhùn abọ́dé bẹ̀rẹ̀ láti oríkì tító dé oríṣiríṣi gbólóhùn abọ́dé ni a ṣe ní ìpín yìí. Bákan náà ni a fi ọ̀kanòjọ̀kan àpẹẹrẹ ṣègbè lẹyìn àlàyé lórí ọ̀kọ̀kan wọn.

## 6.0 IṢẸ́ ÀYÀNṢE ONÍMÁÀKÌ OLÙKỌ́

1. Kí ni àbùdá gbólóhùn abọ́dé?
2. Kí ni ó ṣe pàtàkì nínú gbólóhùn abọ́dé?
3. Dárúkọ oríṣi gbólóhùn abọ́dé mẹ́ta kí o sì fún wa ní àpẹẹrẹ ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn.
4. Ìyàtọ̀ wo ló wà láàárín gbólóhùn wọ̀nyí:
   a. Olú gún iṣu lódó
   b. Ìyá bá mà kú o.
   d. Máa bọ̀.

## 7.0 ÀWỌN ÌWÉ FÚN KÍKÀ

Awobuluyi, Oladele (1978). *Essentials of Yoruba Grammar*. UPL. Oxford University Press, Ibadan. Chapter 3.

Awobuluyi, Oladele (2013). *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá.* ATMAN Limited. Osogbo.

Bámgbóṣé, Ayọ̀. 1990. Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá. o.i. 178-182.

Yusuf, Ọrẹ. 1995. *Gírámà Yorùbá Àkọ̀tun*. (1995). o.i. 21-22.

# ÌPÍN 4 GBÓLÓHÙN ALÁKÀNPỌ̀

**Àkóónú**

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
  3.1 Oríkì
  3.2 Ìpińsísọ̀rí Gbólóhùn alákànpọ̀
    3.2.1 Gbólóhùn alákànpọ̀ onísọ̀kan
    3.2.2 Gbólóhùn alákànpọ̀ onílòdìsí
    3.2.3 Gbólóhùn alákànpọ̀ apààrọ̀
4.0 Ìgúnlẹ̀
5.0 Isọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Àyànṣe Onímáàkì Olùkọ́
7.0 Àwọn Ìwé fún Kíkà

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ní ìpín kẹ́rin yìí ni mo ti máa ṣe àyẹ̀wò tó kún nípa gbólóhùn alákànpọ̀ lédè Yorùbá.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ

Èròǹgbà mi ni kí a lè ṣe àlàyé tó yéni yékéyéké nípa ohun tí a mọ̀ sí gbólóhùn alákànpọ̀, àwọn àbùdá rẹ̀ àti bí akẹ́kọ̀ọ́ yóò ṣe lè da wọn mọ̀ nínú afọ̀.

## 3.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ iṣẹ́ waní ìpín módù yìí ni gbólóhùn alákànpọ̀ ní ọ̀kanòjọ̀kan pẹ̀lú àwọn àpẹẹrẹ tó jọjú.

### 3.1 Oríkì

Gbólóhùn alákànpọ̀ ni gbólóhùn méjì tàbí mẹ́ta tí a pa pọ̀ ṣe odindi kan nípa lílo ọ̀rọ̀ àsopọ̀ tàbí àmì ìdánudúró díẹ̀ (kọmá) so wọ́n pọ̀. Àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ tí a máa ń bá pàdé nínú gbólóhùn alákànpọ̀ ni, tàbí, àbí, àmọ́, ṣùgbọ́n, yálà…tàbí, sì.

### 3.2 Ìpińsísọ̀rí Gbólóhùn alákànpọ̀

Ọ̀nà mẹ́ta pàtàkì ni a lè pín gbólóhùn alákànpọ̀ sí. Àwọn ni:

a. Gbólóhùn alákànpọ̀ adọ̀gba/onísọ̀kan
b. Gbólóhùn alákànpọ̀ onílòdìsí
d Gbólóhùn alákànpọ̀ apààrọ̀

Ẹ jẹ́ ká bẹ̀rẹ̀ síí wò wọ́n níkọ̀ọ̀kan

### 3.2.1 Gbólóhùn alákànpọ̀ onísọ̀kan

Gbólóhùn alákànpọ̀ adọ̀gba/onísọ̀kan ni gbólóhùn méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ tí a fi ọ̀rọ̀-àsopọ̀ "sì" so pọ̀ di ẹyọ kan.

(1) a. Bọ́lá fọ aṣọ; Kẹ́mi sì se oúnjẹ.
b. Bùnmi bínú; ó **sì** kúró nílé.
d. Mo rí òkun; mo **sì** rí ọ̀sà.
e. A jẹ iyán; a mu ọtí; a **sì** dì lọlé
ẹ. Bọ́lá àti Kúnlé ra aṣọ; wọ́n **sì** tún ra bàtà.

Gbólóhùn alákànpọ̀ onísọ̀kan lè jẹ́ ajàjọgún tàbí aláìjàjọgún. Gbólóhùn alákànpọ̀ onísọ̀kan ajàjọgún ni èyí tó jẹ́ wí pé kò sí àtò kànńpá fún gbólóhùn méjì ti a kàn pọ̀. Ìyẹn ni wí pé èyíkéyìí ló lè ṣáájú.

(2) a. Bọ́lá gbọ́n; Bọ́lá **sì** rẹwà
Bọ́á rẹwà; Bọ́lá **sì** gbọ́n

b. Ó tẹ́ẹ́rẹ́; ó **sì** ga
Ó ga; ó **sì** tẹ́ẹ́rẹ́

d. A ra mọ́tò, a **sì** kọ́lé
A kọ́lé, a **sì** ra mọ́tò

e. Adé wo òkè; Adé **sì** wo ilẹ̀
Adé wo ilẹ̀; Adé **sì** wo òkè

ẹ. Abíọ́dún àti Ẹ̀bùn ṣe ìgbéyàwó, Abíọ́dúnàti Ẹ̀bùnyege.
Abíọ́dún àti Ẹ̀bùn yege, Abíọ́dún àti Ẹ̀bùn ṣe ìgbéyàwó.

Ẹ̀wẹ̀, Gbólóhùn alákànpọ̀ onísọ̀kan aláìjàjọgún ni èyí tó jẹ́ wí pé àtò kànńpá wà fún gbólóhùn méjì ti a kàn pọ̀. Ìyẹn ni wí pé èyí tó bá ti ṣáájú kò lè kẹ́yìn. Pípa àtò irúfẹ́ gbólóhùn yìí dà lè fa pọ́nna tàbí kí ìpèdè náà má ṣeé gbà gẹ́gẹ́ bí ojúlówó gbólóhùn Yorùbá.

### 3.2.2 Gbólóhùn alákànpọ̀ onílòdìsí

Gbólóhùn alákànpọ̀ onílòdìsí ni gbólóhùn alákànpọ̀ méjì tí a fi ọ̀rọ̀-àsopọ̀ "ṣùgbọ́n", "bẹ́ẹ̀ ni", "àmọ́" so pọ̀ lọ́nà tó jẹ́ wí pé èrò wọnlòdì sí arawọn. Ìgbà púpọ̀ ni ó jẹ́ wí pé gbólóhùn àkọ́kọ́ máa ń jẹ́ ojú tí ìkejì máa ń jẹ́ òdì.

(4) a. Ọ̀síbàjò mọ òfin **àmọ́** ó kọ̀ láti lò ó fún àwọn ọ̀tá rẹ.
b. Ẹ̀bìtì pa ejò **ṣùgbọ́n** kò pa oró.

d. Ọ̀gá fẹ́ rí mi **ṣùgbọ́n** mo sá pamọ́.
e. Ọdẹ́wálé kọ́lé **bẹ́ẹ̀ ni** kò lówó.
ẹ. A kàwé **ṣùgbọ́n** a kò gba ìwé ẹ̀rí.

### 3.2.3 Gbólóhùn alákànpọ̀ apààrọ̀

Gẹ́gẹ́ bí orúkọ rẹ̀, gbólóhùn alákànpọ̀ apààrọ̀ ni gbólóhùn méjì tí a kàn pọ̀; ṣùgbọ́n tí èrò àwọn méjì jẹ́ apààrọ̀ sí ara wọn, àwọn gbólóhùn méjì náà tún lè gba ipò ara wọn nígbà mìíràn. Ìyẹn ni wí pé gbólóhùn alákànpọ̀ apààrọ̀ lè jẹ́ t ièrò tàbí ti ìhun. Lára àwọn ọ̀rọ̀ àsopọ̀ tí a máa ń bá pàdé nínú irúfẹ́ gbólóhùn bẹ́ẹ̀ ni, **yálà…tàbí**, **tàbí**, **àbí**. Ẹ jẹ́ kí a wo àwọn àpẹẹrẹ ìsálẹ̀ wọ̀nyí.

(5) a. Ẹ lè fẹsẹ̀ rìn tàbí kí ẹ gun ọkadà
Ẹ lè gun ọ̀kadà tàbí kí ẹ fẹsẹ̀ rìn.

b. Yálà kí ẹ fẹsẹ̀ rìn tàbí kí ẹ gun ọ̀kadà.
Yálà kí ẹ gun ọ̀kadà tàbí kí ẹ fẹsẹ̀ rìn.

d. O yá mi lówó tàbí o kò yá mi lówó, N ó ra aṣọ yẹn.
N ó ra aṣọ yẹn, o yá mi lówó tàbí o kò yá mi lówó.

## 4.0 ÌGÚNLẸ̀

Ní ṣókí, a ti wo ohun tí a mọ̀ sí gbólóhùn alákànpọ̀ lédè Yorùbá lọ́kanòjọ̀kan.

## 5.0 ISỌNÍSÓKÍ

Ní ìpín yìí, a ṣiṣẹ́ lórí ìsọ̀rí gbólóhùn tí a mọ̀ sí alákànpọ̀. A bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú oríkí gbólóhùn alákànpọ̀; a tẹ̀síwájú láti ṣe àyẹ̀wò oríṣiríṣi gbólóhùn alákànpọ̀ tó wà, a sì fi àpẹẹrẹ ṣe ègbè lẹ́yìn ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn.

## 6.0 IṢẸ́ ÀYÀNṢE ONÍMÁÀKÌ OLÙKỌ́

1. Kí ni gbólóhùn alákànpọ̀?
2. Dárúkọ ọ̀rọ̀-àsopọ̀ tí a lè fi so gbólóhùn pọ̀.
3. Kí ni gbólóhùn alákànpọ̀ apààrọ̀?
4. Kọ gbólóhùn alásopọ̀ mẹ́ta tí ọ̀rọ̀-àsopọ̀ wọn kò bára mu.

## 7.0 ÀWỌN ÌWÉ FÚN KÍKÀ

Bámgbóṣé, Ayọ̀. 1990. Fonọ́lọ́jì àtiGírámà Yorùbá.o.i. 189-191.

Yusuf, Ọrẹ. 1995. *Gírámà Yorùbá Àkọ̀tun*. (1995). o.i. 53-56.

# ÌPÍN 5 GBÓLÓHÙN ONÍBỌ̀ I

## Àkóónú

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
    3.1 Oríkì Gbólóhùn oníbọ̀
    3.2 Ìpinsísọ̀rí gbólóhùn oníbọ̀
        3.2.1 Gbólóhùn oníbọ̀ aṣàpọ́nlé
        3.2.2 Gbólóhùn oníbọ̀ aṣàpèjúwe
4.0 Ìgúnlẹ̀
5.0 Isọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Àyànṣe Onímáàkì Olùkọ́
7.0 ÀwọnÌwé FúnKíkà

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Abala àkọ̀kọ́ tó jẹ mọ́ gbólóhùn oníbọ̀ ni màá ṣiṣẹ́ lé lórí ni ìpín yìí.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ

Èròǹgbà mi ni pé ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìpín yìí wà á lè ṣe àlàyé tó yéni yékéyéké nípa ohun tí a mọ̀ sí gbólóhùn oníbọ̀, àwọn àbùdá rẹ̀ àti bí wàá ṣe lè da wọn mọ̀ nínú afọ̀.

## 3.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Ohun tí màá ṣiṣẹ lé lórí ni kí a ǹ fún ẹ ní oríkì ohun tí a mọ̀ sí gbólóhùn oníbọ̀, kí a sì wo àwọn ìsọ̀rí tí a lè pín gbólóhùn oníbọ̀ sí pẹ̀lú àlàyé lórí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn.

### 3.1 Oríkì Gbólóhùn oníbọ̀

Gbólóhùn oníbọ̀ ni ó ní gbólóhùn tó lè dá dúró kan àti awẹ́ gbólóhùn kan tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ tí kò lè dá dúró, àfi kó pẹ̀mọ́ lára èyí tó lè dá dúró yẹn. Irú gbólóhùn yẹn ni a mọ̀ si oníbọ̀.

### 3.2 Ìpinsísọ̀rí gbólóhùn oníbọ̀

Ní abala àkọ́kọ́, màá wo gbólóhùn oníbò aṣàpọ̀nlé àti gbólóhùn oníbọ̀ aṣàpèjúwe.

### 3.2.1 Gbólóhùn oníbọ̀ aṣàpọ́nlé

Ọ̀kan lára gbólóhùn oníbọ̀ nípa iṣẹ́ tí wọ́n ń ṣe ni èyí tó ń ṣe iṣẹ́ àpọ́nlé. Agbègbè tàbí sàkání ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó ń pọ́n lé ni a ti lè ṣe alábàápàdé gbólóhùn oníbò aṣàpọ́nlé yìí.

(1) a. Bọ́lá máa sùn **tí ó bá ti ibi iṣẹ́ dé**.
b. Màá kọ́lé **tí n bá lówó**.
d. **Tí ó bá dé**, Adé kò níí jẹun.
e. **Bí Adé bá gbọ́**, ó máa bínú.

### 3.2.2 Gbólóhùn oníbọ̀ aṣàpèjúwe

Gbólóhùn oníbọ̀ aṣàpèjúwe ni irúfẹ́ awẹ́ gbólóhùn tàbí gbólóhùn oníbọ̀ tó máa ń ṣe àpèjúwe ọ̀rọ̀-orúkọ tàbí àpólà orúkọ. Ẹ̀yìn ọ̀rọ̀-orúkọ tàbí àpólà orúkọ tó ń ṣe àpèjúwe.

(2) a. **Òṣìṣẹ́ tí ó kówó jẹ** ti rí ẹ̀wọ̀n he.
b. Mo rí **ọmọ ọba tí ó dẹrú**.
d. **Ìwé tí Adé kà**, yé ẹ yéké yéké.

Nínú àpẹẹrẹ (2a), àárín gbólóhùn kíkún ni gbólóhùn oníbọ̀ 'tí ó kówó jẹ' wà ṣùgbọ́n ní (2b), ìparí ni gbólóhùn oníbọ̀ 'tí ó dẹrú' wà. Ohun tó ṣe pàtàkì ni wí pé, gbólóhùn oníbọ̀ gbọ́dọ̀ jẹ tẹyọ tẹ̀lé ọ̀rọ̀-orúkọ tó ń ṣe àpèjúwe rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn nínú àpẹẹrẹ òkè.

## 4.0 ÌGÚNLẸ̀

Ohun tí iṣẹ́ ìpín yìí dálé ni àyẹ̀wò ọ̀kanòjọ̀kan gbólóhùn oníbọ̀ nínú èdè Yorùbá.

## 5.0 ISỌNÍSÓKÍ

A bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ ìpín yìí nípa fífún gbólóhùn oníbọ̀ ní oríkì. A tẹ̀síwájú láti wo oríṣi gbólóhùn oníbọ̀ méjì: gbólóhùn oníbọ̀ aṣàpèjúwe àti gbólóhùn oníbọ̀ aṣàpọ́nlé. A ṣe àlàyé ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn, a sì fi àpẹẹrẹ ṣe àtìlẹ́yìn àwọn àlàyé wa.

## 6.0 IṢẸ́ ÀYÀNṢE ONÍMÁÀKÌ OLÙKỌ́

1. Kọ àpẹẹre gbólóhùn oníbọ̀ aṣàpèjúwe márùn-ún sílẹ̀
2. Kí ni ìyàtọ̀ láàárín gbólóhùn oníbọ̀ aṣàpèjúwe àti gbólóhùn oníbọ̀ aṣàpọ́nlé?
3. Kí ni gbólóhùn oníbò aṣàpọ́nlé? Kọ àpẹẹrẹ márùn-ún irú gbólóhùn bẹ́ẹ̀ sílẹ̀.

## 7.0 ÀWỌNÌWÉ FÚNKÍKÀ

Awobuluyi, Oladele (2013). *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá.* ATMAN Limited. Osogbo.

Bámgbóṣé, Ayọ̀. 1990. Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá.

Yusuf, Ọrẹ. 1995. *Gírámà Yorùbá Àkọ̀tun*. (1995). o.i. 56-61.

## MÓDÙ 3

Ìpín 1 Gbólóhùn Oníbọ̀ II
Ìpín 2 Iṣẹ́ tí gbólóhùn ń ṣe: Ìròyìn àti Ìpàṣẹ
Ìpín 3 Ìṣèbéèrè I: Onídáhùn Àlàyé
Ìpín 4 Ìṣèbéèrè II: Onídáhùn bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́
Ìpín 5 Ìṣètẹnumọ́

## ÌPÍN 1 GBÓLÓHÙN ONÍBỌ̀ II

### Àkóónú

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
 3.1 Gbólóhùn oníbọ̀ Àsọdorúkọ
 3.2 Gbólóhùn oníbọ̀ Àfikún
4.0 Ìgúnlẹ̀
5.0 Isọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Àyànṣe Onímáàkì Olùkọ́
7.0 Àwọn Ìwé fún Kíkà

### 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ní ìpín yìí, a ó tẹ̀síwájú nínú iṣẹ́ lórí gbólóhùn oníbọ̀.

### 2.0 ÈRÒǸGBÀ

Èròǹgbà mi ni bí akẹ́kọ̀ọ́ yóò ṣe lè dá gbólóhùn oníbọ̀ mọ̀ nínú afọ̀ tí yóò sì lè fúnra rẹ̀ kọ ọ̀kanòjọ̀kan àpẹẹrẹ wọn sílẹ̀.

### 3.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

A fẹ́ẹ́ wo oríṣi gbólóhùn oníbọ̀ mìíràn tó yàtọ̀ sí àwọn tí a ti wò ṣáájú; ìyẹn ni pé, kí a tẹ̀síwájú nípa gbólóhùn oníbọ̀ àti àwọn àbùdá wọn.

### 3.1 Gbólóhùn oníbọ̀ Àsọdorúkọ

Gbólóhùn oníbọ̀ àsọdorúkọ ni awẹ́ gbólóhùn tó ń ṣe iṣẹ́ gẹ́gẹ́ bí orúkọ nítorí ó lè wà ní ipò olùwà tàbí àbọ̀ gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀-orúkọ pọ́ńbélé. Nítorí náà, a lè fi ọ̀rọ̀ orúkọ dípò wọn.

(1) a. **Pé n kò mọ ìwé** ba àwọn òbí mi nínú jẹ́
 b. **Mo** ba àwọn òbí mi nínú jẹ́.
 d. **Ó** ba àwọn òbí mi nínú jẹ́.

Àpẹ̀ẹrẹ gbólóhùn oníbọ̀ àsọdorúkọ ní ipò olùwà ni ó wà ní (1).

(2) a. Àkàndé mọ **pé ọmọ òun n ṣe ìṣekúṣe**.
b. Àkàndé mọ̀ **ọ́n**.
d. Ábúrámù mọ **aya rẹ̀**.

Àpẹ̀ẹrẹ gbólóhùn oníbọ̀ àsọdorúkọ ní ipò àbọ̀ ló wà ní (2). Ẹ ṣe àkíyèsí àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ tí a fàlà sí nínú àpẹ̀ẹrẹ (1b, dàti 2b, d) bí wọ́n ti fi hàn pé ipò kan náà ni wọ́n wà pẹ̀lú awẹ́ gbólóhùn àsọdorúkọ tó wà ní (1a) àti (2a).

### 3.2 Gbólóhùn oníbọ̀ Àfikún

Gbólóhùn oníbọ̀ àfikún fara pẹ́ gbólóhùn oníbọ̀ àsọdorúkọ nípa pé àwọn náà máa ń tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe.

(3) a. Mo gbà **pé ayé ni a bá ifá**.
b. Olú mọ̀ **pé òun ń purọ́**.

Kí wa ni ìyàtọ̀ tó wà láàárín oríṣi gbólóhùn méjèèjì: ìyẹn gbólóhùn oníbọ̀ àsọdorúkọ àti gbólóhùn oníbọ̀ àfikún? Ọ̀kan lára ìyàtọ̀ wọn ni wí pé gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ orúkọ tàbí àpólà orúkọ, ọ̀rọ̀-ìṣe olóhùn ìsàlẹ̀ tí gbólóhùn oníbọ̀ àsọdorúkọ bá tẹ̀lé máa ń yípadà láti ohùn ìsàlẹ̀ di ohùn àárín (4a). Ní ti gbólóhùn oníbọ̀ àfikún, kì í sí àyípadà kankan (4b).

(4) a. Ó gba **pé kí a pa àgọ́ mẹ́ta**. *Gbólóhùn oníbọ̀ àfikún*
b. Ó gbà **pé kí a pa àgọ́ mẹ́ta**. *Gbólóhùn oníbọ̀ àsọdorúkọ*

## 4.0 ÌGÚNLẸ̀

A ti ṣe iṣẹ́ tó jinlẹ̀ lórí àwọn gbólóhùn oníbọ̀ mìíràn tó yàtọ̀ sí èyí tí a wò sẹ́yìn.

## 5.0 ISỌNÍSÓKÍ

Ní ṣókí, a wo oríṣi gbólóhùn oníbọ̀ méjì mìíràn tí a mọ̀ sí gbólóhùn oníbọ̀ àsọdorúkọ àti gbólóhùn oníbọ̀ àfikún. A ṣe àlàyé ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn pẹ̀lú àpẹ̀ẹrẹ.

## 6.0 IṢẸ́ ÀYÀNṢE ONÍMÁÀKÌ OLÙKỌ́

1. Kí ni gbólóhùn oníbọ̀ àsọdorúkọ àti gbólóhùn oníbọ̀ àfikún?
2. Kọ àpẹ̀ẹrẹ gbólóhùn oníbọ̀ àsọdorúkọ márùn-ún àti gbólóhùn oníbọ̀ àfikún márùn-ún sílẹ̀.
3. Irú gbólóhùn wo ni a sàlámì dúdú nísàlẹ̀?
   a. Bọ́lá mọ **pé òun n ṣe ìṣekúṣe**
   b. **Pé n kò rí owó ìwé san** bà mi nínú jẹ́.

## 7.0 ÀWỌN ÌWÉ FÚN KÍKÀ

Awobuluyi, Oladele (1978). *Essentials of Yoruba Grammar*. UPL. Oxford University Press, Ibadan. Chapter 3

Awobuluyi, Oladele (2013). *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá.* ATMAN Limited. Osogbo. o.i. 176-190.

Bámgbóṣé, Ayọ̀. 1990. Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá.o.i. 192-204.

Yusuf, Ọrẹ. 1995. *Gírámà Yorùbá Àkọ̀tun*. (1995). o.i. 56-58.

## ÌPÍN 2 IṢẸ́ TÍ GBÓLÓHÙN Ń ṢE: ÌRÒYÌN ÀTI ÌPÀṢẸ

### Àkóónú

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
  3.1 Gbólóhùn ìròyìn
  3.2 Gbólóhùn ìpàṣẹ
4.0 Ìgúnlẹ̀
5.0 Isọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Àyànṣe Onímáàkì Olùkọ́
7.0 Àwọn Ìwé fún Kíkà

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Oríṣiríṣi iṣẹ́ ni a ṣe àkíyèsí wí pé gbólóhùn lè ṣe ní èdè Yorùbá bí ti èdè mìíràn. Ní ìpín (1) módù kẹta yìí, ni màá ó ti ṣe àfihàn àti àlàyé méjì nínú iṣẹ́ náà.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ

Èròǹgbà wa ni pé lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, wà á lé sọ oríṣiríṣi iṣẹ́ tí gbólóhùn lè ṣe, wọ́n á sì lè fúnra wọn ṣe àkọsílẹ̀ àpẹ́ẹrẹ ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn.

## 3.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ iṣẹ́ yìí máa mú wa wo méjì nínú oríṣi iṣẹ́ tí gbólóhùn lè ṣení Yorùbá. Màá ṣe àlàyé ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn, màá sì fi àpẹẹrẹ ti àgbékalẹ̀ mi lẹ́yìn.

### 3.1 Gbólóhùn ìròyìn

Gbólóhùn ìròyìn ni irúfẹ́ gbólóhùn tí ó máa ń ṣe ìròyìn tàbí àlàyé ìṣẹ̀lẹ̀ kan bóyá nípa ìrírí láti ọ̀dọ̀ ẹnití ó ń sọ̀rọ̀ tí a mọ̀ sí olùsọ̀rọ̀, ẹnití ó ń sọ̀rọ̀ sí tí a mọ̀ sí agbọ́rọ̀ tàbí ẹni/ohun tí a ń sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ tí a máa ń pè ní ẹnìkẹ́ta, ní ọ̀pọ̀ ìgbà.

(1) a. Buhari di ààrẹ lẹ́ẹ̀kejì.
  b. Olè fọ́ báǹkì mẹ́wàá ní Ìbàdàn lọ́jọ́ kanṣoṣo.
  d. Iṣẹ́ àgbẹ̀ kò rọrùn láti ṣe.
  e. Aṣọ àlòkù wà ní ọjà Yáàbá.
  ẹ. Ọyẹ́ ọdún yìí lé keñkà.
  f. Mo rí èèmọ̀ léréko

Ó ṣeé ṣe kí gbólóhùn ìròyìn wá nípa yíyí tàbí sísọ ọ̀rọ̀ ẹnìkan tí a mọ̀ sí ọ̀rọ̀ ọlórọ̀ di ọ̀rọ̀ àgbàsọ nígbà tí a bá fẹ́ ṣe ìròyìn ohun tí ẹni náà sọ.

(2) a. Adé jẹ iyán.
Adé sọ pé òun jẹ iyán.

b. Olè fọ́ báńkì mẹ́wàá ní Ìbàdàn lọ́jọ́ kanṣoṣo.
Olú sọ pé olè fọ́ báńkì mẹ́wàá ní Ìbàdàn lọ́jọ́ kanṣoṣo.

c. Mo rí èèmọ̀ léréko.
Mo sọ pé mo rí èèmọ̀ léréko.

Ohun kan tó tún gba kí a sọ nípa gbólóhùn ìròyìn tó jẹ mọ́ ti ẹnìkẹta ni ìyípadà ọ̀rọ̀-arọ́pò orúkọ ẹnìkẹta láti "ó" sí òun àti "wọ́n" sí àwọn".

(1) a. O sọ pé **ó** lọ sí Kanádà.
O sọ pé **òun** lọ sí Kánádà.

b. O ní **ó** gbà láti fi iṣẹ́ sílẹ̀
O ní **òun** gbà láti fi iṣẹ́ sílẹ̀

## 3.2 Gbólóhùn ìpàṣẹ

Gbólóhùn ìpàṣẹ ni gbólóhùn tí a fi ń sọ pé kí ẹnìkan ṣe ohun kan bóyá ó tẹ́ ẹni náà lọ́rùn tàbí kò tẹ́ ẹ lọ́rùn.

(2) a. Lọ gbá ilẹ̀ yẹn.
b. Dìde dúró.
d. Wá bá mi ṣeré.

Ní ọ̀pọ̀ ìgbà ni ẹni tí ó ń pàṣẹ, ìyẹn olùsọ̀rọ̀ máa ń ga ju ẹni tí a ń pàṣẹ fún lọ.

(3) a. Pọn omi sí bàlùwẹ̀ fún mi.
b. Bá mi gbé ọkọ̀ yẹn wọlé.
d. Jọ̀wọ́ dárí jì mí

Ó ṣeé ṣekí olùsọ̀rọ̀ tó jẹ́ apàṣẹ àtẹni tí a ń pàṣẹ fún jẹ́ irọ̀ kan lọ́jọ́ orí tàbí ní ipò.

(4) a. Wá bá mi ṣeré.
b. Yá mi ní ìwé rẹ.

Ìgbà mìíràn wà nígbà tí ẹni tó ń pàṣẹ fún ẹlòmíràn lè kéré sí ẹni tó ń pàsẹ fún. Irú àṣẹ yìí máa ń bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú "ẹ".

(5) a. Ẹ dárí jì mí.
b. Ẹ san owó tí ẹ jẹ.
d. Ẹ máa bọ̀ níbí.
e. Ẹ wobí.

Àṣẹ pípa lè jẹ́ ti èle tàbí ti túlàsì.

(6) a. Jáde kúró nílé mi.
b. Máa bọ̀ báyẹn.
d. Bọ́ síbí.
e. Fi mí sílẹ̀.

Àṣẹ sì tún lè jẹ́ ti ẹ̀lẹ̀, pàápàá tí a bá ń bá Ọlọ́run tàbí ẹni tó jù wá lọ sọ̀rọ̀; èyí máa ń wáyé gẹ́gẹ́ bí ẹ̀bẹ̀.

(7) a. Ẹ má fi wá sílẹ̀.
b. Ẹ ṣàánú mi.
d. Ẹ ràn mí lọ́wọ́.
e. Ẹ jọ̀ọ́, jàre.

Ìgbà mìíràn wà tí ọ̀rọ̀ ẹ̀bẹ̀ máa ń wà nínú àṣẹ ẹ̀lẹ̀.

(8) a. Dákun gbé rù mí
b. Jọ̀ọ́ jáde.
d. Ẹ jọ̀ọ́, jàre.

## 4.0 ÌGÚNLẸ̀

Ohun tí a ṣiṣẹ́ lé lórí ní ìpín yìí niiṣẹ́ gbólóhùn fún ṣíṣe ìròyìn àti pípàṣẹ.

## 5.0 ISỌNÍSÓKÍ

A ti wo oríṣi méjì nínú iṣẹ́ tí gbólóhùn lè ṣe. Àwọn iṣẹ́ méjì tí a yẹ̀wò náà ni ti ìròyìn àti ìpàṣẹ̀. A wo àbùdá iṣẹ́ kọ̀ọ̀kan, a sì fi àpẹẹrẹ ṣègbè lẹ́yìn wọn.

## 6.0 IṢẸ́ ÀYÀNṢE ONÍMÁÀKÌ OLÙKỌ́

1. Kí ni gbólóhùn ìròyìn?
2. Pẹ̀lú àpẹẹrẹ tó jọjú, ṣe àlàyé ohun tí o mọ̀ sí gbólóhùn ìpàṣẹ
3. Oríṣi gbólóhùn ìpàṣẹ mélòó ló wà? Dárúkọ wọn.
4. Kí ni ìyàtọ̀ láàárín àṣẹ èle àti àṣẹ ẹ̀lẹ̀?

## 7.0 ÀWỌN ÌWÉ FÚN KÍKÀ


Awobuluyi, Oladele (1978). *Essentials of Yoruba Grammar*. UPL. Oxford University Press, Ibadan. Chapter 3

Awobuluyi, Oladele (2013). *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá.* ATMAN Limited. Osogbo. o.i. 197-201.

Bámgbóṣé, Ayọ̀. 1990. Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá.o.i. 201tt.

Yusuf, Ọrẹ. 1995. *Gírámà Yorùbá Àkọ̀tun*. (1995). o.i. 29-32.

## ÌPÍN 3 ÌṢÈBÉÈRÈ I: ONÍDÁHÙN ÀLÀYÉ

**Àkóónú**


1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
3.1 Oríkì Gbólóhùn Ìṣèbéèrè onídáhùn àlàyé
3.2 Ìpinsísọ̀rí Gbólóhùn Ìṣèbéèrè Onídáhùn àlàyé
3.2.1 Ipò fọ́nrán tí a ṣe Ìbéèrè nípa rẹ̀
3.2.1.1 Ìṣèbéèrè Olùwà
3.2.1.2 Ìṣèbéèrè Àbọ̀ tààrà
3.2.1.3 Ìṣèbéèrè Àbọ̀ pẹ́ẹ̀kí
3.2.2 Fọ́nrán ìṣèbéèrè
4.0 Ìgúnlẹ̀
5.0 Isọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Àyànṣe Onímáàkì Olùkọ́
7.0 Àwọn Ìwé fún Kíkà


## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ní ìpín kẹta módù yìí, a fẹ́ẹ́ ṣe àyẹ̀wò oríṣi gbólóhùn ìbéèrè kan tí ìdáhùn rẹ̀ máa ń fún wa ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ

Èròǹgbà mi ni wí pé lẹ́yìn ẹ̀kọ́ náà, wàá lè dá gbólóhùn ìbéèrè onídàhùn àlàyé mọ̀, wà á sì lè mọ irú fọ́nrán tí a lè ṣe ìbéèrè nípa rẹ̀ àti ibi tí irú fọ́nrán náà ti lè jẹyọ. O sì tún gbọ́dọ̀ lè dá oríṣiríṣi wúnrẹ̀n tí a fi ń ṣe ìbéèrè onídáhùn àlàyé mọ̀.

## 3.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

Ní abala yìí mà á ṣe àyẹ̀wò fínnífínní nípa ìbéèrè onídáhùn àlàyé bẹ̀rẹ̀ láti oríkì tí a lè fún un àti ọ̀nà tí a ń gbà ṣe ìbéèrè tí ìdáhùn rẹ̀ máa jẹ́ ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé.

### 3.1 Oríkì Gbólóhùn Ìṣèbéèrè onídáhùn àlàyé

Ìbéèrè onídáhùn àlàyé ni ìbéèrè ti a bi ni tí ìdáhùn rẹ̀ jẹ́ ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ gbólóhùn.

### 3.2 Ìpinsísọ̀rí Gbólóhùn Ìṣèbéèrè Onídáhùn àlàyé

Ọ̀nà méjì gbógì ni a lè gbà pín ìbéèrè onídáhùn àlàyé sí. Ọ̀nà kìíní ni ipò fọ́nrán tí a ṣe ìbéèrè nípa rẹ̀. Ọ̀nà kéjì ni fọ́nrán ìṣèbéèrè fúnra rẹ̀.

### 3.2.1 Ipò fọ̀nrán tí a ṣe Ìbéèrè nípa rẹ̀

Ohun méjì to ṣe pàtàkì láti mẹ́nu bà nipa ìbéèrè ìsọ̀rí yìí ni pé ọ̀rọ̀-orúkọ, ọ̀rọ̀-arópò orúkọ, arọ́pò afarajorúkọ tàbí àpólà orúkọ ni a máa ń ṣe ìbéèrè nípa rẹ̀. Ohun èkéjì ni wí pé ohun tí kò yéni tàbí ohun tí a kò mọ̀ tàbí ohun tí a kò lóye nípa rẹ̀ tí a sì fẹ́ẹ̀ mọ̀ ló máa ń fa ìdí ìbéèrè wa.

Èyí tó wù kó jẹ́, kókó kan pàtàkì tún ni ipò tí ọ̀rọ̀-orúkọ tàbí àpólà orúkọ bá wà nínú gbólóhùn ti a ti fẹ́ẹ̀ ṣe ìbéèrè nípa rẹ̀.

#### 3.2.1.1 Ìṣèbéèrè Olùwà

Ọ̀rọ̀-orúkọ, ọ̀rọ̀-arópò orúkọ, arọ́pò afarajorúkọ tàbí àpólà orúkọ lè wà ní ipò olùwà, kí a ṣe ìbéèrè nípa rẹ̀. Tí èyí bá wáyé; àwọn ohun kan máa ṣẹlẹ̀.

a. A ó gbé fọ́nrán tí a bá fẹ́ẹ̀ ṣe ìbéèrè nípa rẹ̀ kúrò nínú gbólóhùn yẹn lọ sípò mìíràn lápá òsì.
b. A ó fi ọ̀rọ̀-arọ́pò aláìlẹ́ni “ó” tàbí “wọ́n” sí ipò tí fọ̀nrán yẹn wà ká tó ṣe ìbéèrè.
d. A ó fi fọ́nrán ìbéèrè tó bá tọ̀ dípò ọ̀rọ̀-orúkọ, ọ̀rọ̀-arópò orúkọ, arọ́pò afarajorúkọ tàbí àpólà orúkọ tí a ṣe ìbéèrè nípa rẹ̀.
e. A ó ṣe ìfibọ̀ atọ́ka ìbéèrè onídáhùn àlàyé “ni” lẹ́yìn fọ̀nrán ìṣèbéèrè.

(1) a. **Kíkẹ́** jẹ iṣu.
**Ta ni ó** jẹ iṣu?

b. Bísọ́lá àti Kíkẹ́ jà.
**Ta ni ó/wọ́n** jà?

d. **Omí** ya ilé
**Kí ni ó** ya ilé?

e. Àwọn jẹ iṣu
**Ta** ni **ó** jẹ iṣu?

Ohun mẹ́rin tí a mẹ́nu bà lókè ni a máa ṣe alábápàdé nínú ọ̀kọ̀ọ̀kan àpẹẹrẹ mẹ́ta wọ̀nyẹn. Tí a bá wo (1), a ó ri mọ̀ wí pé ẹni tó jẹ iṣu ni a fẹ́ mọ̀ nípa rẹ̀; ìyẹn, Kíkẹ́. Nítorí náà ni a ṣe gbe kúrò ní àyè rẹ̀ lọ sí apá òsì. Fọ̀nrán ìbéèrè tó ṣe déédé pẹ̀lú Kíkẹ́ ni “ta”. Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣáájú, tí a bá gbé olùwà kúrò láti ṣe ìbéèrè nípa rẹ̀, àyè olùwà kò gbọ́dọ̀ ṣòfo. Dandan ni kí a fi arọ́pò-orúkọ tó bá tọ̀nà dípò rẹ̀. Ìyẹn ló fa sábàbí “ó” tó súyọ ní ipò tí “Kíkẹ́” wà tẹ́lẹ̀. Ní ìparí, “ni” gbọ́dọ̀ tẹ̀lé fọ̀nrán ìbéèrè.

### 3.2.1.2 Ìṣèbéèrè Àbọ̀ tààrà

Ẹ̀wẹ̀, ọ̀rọ̀-orúkọ, ọ̀rọ̀-arópò orúkọ, arọ́pò afarajorúkọ tàbí àpólà orúkọ lè wà ní ipò àbọ̀ tààrà, kí a ṣe ìbéèrè nípa rẹ̀. Tí èyí bá wáyé; àwọnohunkannáà túnmáaṣẹlẹ̀.

a. A ó gbé fọ́nrántí a bá fẹ́ẹ́ ṣeìbéèrè nípa rẹ̀ kúrò ní ipò àbọ̀ nínú gbólóhùn jáde lọ sípò mìíràn lápá òsì.

b. A ó fi fọ́nrán ìbéèrè tó bá tọ́ dípò ọ̀rọ̀-orúkọ, ọ̀rọ̀-arópò orúkọ, arọ́pò afarajorúkọ tàbí àpólà orúkọ tí a ṣe ìbéèrè nípa rẹ̀.

d. A ó ṣe ìfibọ̀ atọ́ka ìbéèrè onídáhùn àlàyé "ni" lẹ́yìn fọ́nrán ìṣèbéèrè.

(2) a. Ẹkùn pa ọdẹ.
**Ta ni** Ẹkùn pa?

b. Kíkẹ́ jẹ iṣu.
**Kí ni** Kíkẹ́ jẹ?

d. Kíkẹ́ jẹ ẹ́.
**Kí ni** Kíkẹ jẹ?

Ohun mẹ́ta tí a mẹ́nu bà lókè náà ni a máa ṣe alábápàdé nínú ọ̀kọ̀ọ̀kan àpẹẹrẹ mẹ́ta wọ̀nyẹn. Tí a bá wo (2a), a ó rimọ̀ wí pé "ẹnití Ẹkùn pa"ni a fẹ́ mọ̀ nípa rẹ̀; ìyẹn, "ọdẹ". Nítorí náà ni a ṣe gbe kúrò ní àyè rẹ̀ lọ sí apá òsì. Fọ́nrán ìbéèrè tó ṣe déédé pẹ̀lú Ọdẹni "ta". Ní ìparí, "ni" gbọ́dọ̀ tẹ̀lé fọ́nrán ìbéèrè.

### 3.2.1.3 Ìṣèbéèrè Àbọ̀ pẹ́ẹ̀kí

Bákan náà, ó tún ṣe é ṣe kí ọ̀rọ̀-orúkọ, ọ̀rọ̀-arópò orúkọ, arọ́pò afarajorúkọ tàbí àpólà orúkọ wà ní ipò àbọ̀ pẹ́ẹ̀kí, kí a ṣe ìbéèrè nípa rẹ̀. Àbọ̀ pẹ́ẹ̀kí ni ọ̀rọ̀-orúkọ tàbí àpólà orúkọ tó bá tẹ̀lé ọ̀rọ̀-atọ́kùn bí "ni", "sí" abbl. Tí èyí bá wáyé; àwọn ohun kan náà tún máa ṣẹlẹ̀.

a. A ó gbé fọ́nrán tí a bá fẹ́ẹ́ ṣe ìbéèrè nípa rẹ̀ kúrò ní ipò àbọ̀ nínú gbólóhùn jáde lọ sípò mìíràn lápá òsì.

b. Tí ọ̀rọ̀-atọ́kùn bá jẹ́ "sí", a ó pá jẹ, ṣùgbọ́n tí ọ̀rọ̀-atọ́kùn bá jẹ́ "ní" ohun méjì ló lè ṣẹlẹ̀: nínú kí a gbe pẹ̀lú fọ́nrán tí a ṣe ìbéèrè nípa rẹ̀ tàbí kí a pá jẹ.

d. A ó fi fọ́nrán ìbéèrè tó bá tọ́ dípò ọ̀rọ̀-orúkọ, ọ̀rọ̀-arópò orúkọ, arọ́pò afarajorúkọ tàbí àpólà orúkọ tí a ṣe ìbéèrè nípa rẹ̀.

e. A ó ṣe ìfibọ̀ atọ́ka ìbéèrè onídáhùn àlàyé "ni" lẹ́yìn fọ́nrán ìṣèbéèrè.

(3) a. Kẹ́mi fi ìwé fúnTúndé.
**Tani** Kẹ́mi fi ìwé fún?

b. Bọ́lá ranọmọ rẹ̀ lọ **sí** Èkó
**Ibo ni** Bọ́lá ránọmọ rẹ̀ lọ?

d. Bùárí ṣe ọdún iléyá **ní** Dàùra
**Ní ibo ni** Bùárí ti ṣe ọdún iléyá?
**Ibo ni** Bùárí ti ṣe ọdún iléyá?

### 3.2.2 Fọ́nrán ìṣèbéèrè

Ohun tó kàn ni àfihàn fọ́nrán ìṣèbéèrè onídáhùn àlàyé. Ní wọ̀n bí o ti jẹ́ wí pé ọ̀rọ̀-orúkọ, ọ̀rọ̀-arọ́pò orúkọ, arọ́pò afarajorúkọ tàbí àpólà orúkọ ni a máa ń ṣe ìbéèrè nípa rẹ̀, àwọn fọ́nrán tó má dípò wọn lè jẹ́ ti ènìyàn, ẹranko, ohun abẹ̀mí tàbí aláìlẹ́mìí, ibi, àsìkò abbl. Àwọn fọ́nrán ìṣèbéèrè onídáhùn àlàyé ni a ṣe àfihàn wọn nísàlẹ̀ pẹ̀lú àpẹẹrẹ.

(1) a. Olú rí ọmọ rẹ̀.
**Ta ni** Olú rí? *Fọ́nrán ìbéèrè ẹni/ènìyàn*

b. Olú jẹ iṣu.
**Kí ni** Olú jẹ? *Fọ́nrán ìbéèrè ohun*

d. Olú lọ sí Ìbàdàn.
**Ibo** ni Olú lọ? *Fọ́nrán ìbéèrè ibi*

e. Olú dé ni agogo méje alẹ́.
**Ìgbà** wo ni Olú dé? *Fọ́nrán ìbéèrè àsìkò*

ẹ Gómìnà Ọ̀yọ́ dá òṣìṣẹ́ mẹ́fà dúró
Òsìṣẹ́ **mélòó** ni Gómìnà Ọ̀yọ́ dá dúró? *Fọ́nrán ìbéèrè iye*

f. Adé mú pupa, mo mú dúdú.
**Èwo** ni Adé mú? *Fọ́nrán ìbéèrè èwo*

## 4.0 ÌGÚNLẸ̀

Ohun tí a dojú kọ ní ìsọ̀rí yìí ni oríṣiríṣi ìbéèrè tí ìdáhùn rẹ̀ fún wa ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé.

## 5.0 ISỌNÍSÓKÍ

Ohun méjì pàtàkì ni a gbé ṣe ní ìpín yìí. Èkíní, a wo ìsọ̀rí tí ìbéèrè onídáhùn àlàyé pín sí. Èkejì a wo oríṣi fọ́nrán ìṣèbéèrè onídáhùn àlàyé. A fọ̀ ìsọ̀rí ìbéèrè onídáhùn àlàyé sí wẹ́wẹ́ nípa wíwo ipò tí ọ̀rọ̀-orúkọ, arópò-

orúkọ, arọ́pò afarajorúkọ tàbí àpólà orúkọ wà kí a tó ṣe ìbéèrè nípa rẹ. A sì tẹ̀ síwájú láti wo ìrísí fọ́nrán ìbéèrè onídáhùn àlàyé.

## 6.0 IṢẸ́ ÀYÀNṢE ONÍMÁÀKÌ OLÙKỌ́

1. Kí ni àwọn ohun pàtàkì tí a gbọ́dọ̀ mọ̀ tí a bá fẹ́ẹ́ ṣe ìbéèrè nípa olùwà?
2. Kì ni ìyàtọ̀ tó wà láàárín ìṣèbéèrè nípa àbọ̀ tààrà àti àbọ̀ pẹ́ẹ̀kí?
3. Dárúkọ fọ́nrán ìbéèrè onídáhùn àlàyé márùn-ún kí o sì sọ nípa ohun tí ìkọ̀ọ̀kan dúró fún.
4. Kí ni ó máa ṣẹlẹ̀ sí fọ́nrán tí a bá ṣe ìbéèrè?

## 7.0 ÀWỌN ÌWÉ FÚN KÍKÀ

Awobuluyi, Oladele (1978). *Essentials of Yoruba Grammar*. UPL. Oxford University Press, Ibadan. Ori kẹ́ta.

Awobuluyi, Oladele (2013). *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá.* ATMAN Limited. Osogbo. Chapter o.i. 214-216.

Bámgbóṣé, Ayọ̀. 1990. Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá. o.i.183-189.

Yusuf, Ọrẹ. 1995. *Gírámà Yorùbá Àkọ̀tun*. (1995). o.i. 34-35.

# ÌPÍN 4 ÌṢÈBÉÈRÈ II: ONÍDÁHÙN BẸ́Ẹ̀ NI-BẸ́Ẹ̀ KỌ́

**Àkóónú**

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
 3.1 Oríkì Gbólóhùn Ìṣèbéèrè onídáhùn bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́
 3.2 Ìpinsísọ̀rí gbólóhùn Ìṣèbéèrè onídáhùn bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́
  3.2.1 Ìṣèbéèrè onídáhùn bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́ alátọ́ka ìbẹ̀rẹ̀
  3.2.2 Ìṣèbéèrè onídáhùn bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́ alátọ́ka àárín
  3.2.3 Ìṣèbéèrè onídáhùn bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́ alátọ́ka ìparí
  3.2.4 Ìṣèbéèrè onídáhùn bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́ alátọ́ka ìbẹ̀rẹ̀ àti àárín
4.0 Ìgúnlẹ̀
5.0 Isọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Àyànṣe Onímáàkì Olùkọ́
7.0 Àwọn Ìwé Fún Kíkà

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Màá ṣe àyẹ̀wò fínnífínní nípa ìbéèrè onídàhùn "bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́"; bẹ̀rẹ̀ láti oríkì tí a lè fún un àti ọ̀nà tí a ń gbà ṣe ìbéèrè tí ìdáhùn rẹ̀ máa jẹ́ "bẹ́ẹ̀ ni" tàbí "bẹ́ẹ̀ kọ́".

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ

## 3.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 3.1 Oríkì Gbólóhùn Ìṣèbéèrè onídáhùn bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́

Gbólóhùn Ìṣèbéèrè onídáhùn bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́ ni oríṣi ìbéèrè tí ìdáhùn rẹ̀ kàn má jẹ́: "bẹ́ẹ̀ ni" tàbí "bẹ́ẹ̀ kọ́".

### 3.2 Ìpinsísọ̀rí gbólóhùn Ìṣèbéèrè onídáhùn bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́

Gbólóhùn Ìṣèbéèrè onídáhùn bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́ ṣeé pín sí oríṣríṣi ìsọ̀rí pàápàá tí a bá fi òdiwọ̀n ìjẹyọ atọ́ka tí fi ń ṣe irú ìbéèrè yìí.

#### 3.2.1 Ìṣèbéèrè onídáhùn bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́ alátọ́ka ìbẹ̀rẹ̀

Ìsọ̀rí gbólóhùn ìṣèbéèrè onídáhùn "bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́" kan wà tó jẹ́ pé ìbẹ̀rẹ̀ gbólóhùn ni atọ́ka ìṣèbéèrè náà máa ń wà. Méjì ni àwọn atọ́ka ìbéèrè yìí gẹ́gẹ́ bí wọ́n ti jẹyọ nísàlẹ̀.

(1) a. Ṣé ètò ìdìbò yóò wáyé lọ́dún tó ń bọ̀?
b. Ǹjẹ́ ètò ìdìbò yóò wáyé lọ́dún tó ń bọ̀?

Gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn nínú àpẹẹrẹ òkè, "ṣé" àti "ǹjẹ́" ni atọ́ka ìbéèrè tó máa ń jẹyọ ní bẹ̀rẹ̀.

### 3.2.2 Ìṣèbéèrè onídáhùn bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́ alátọ́ka ààrín

Ìṣèbéèrè onídáhùn bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́ alátọ́ka ààrín ni èyí tí atọ́ka rẹ̀ máa ń wà ní ààrín gbólóhùn. Ẹ̀yìn àpólà orúkọ tó wà ní ipò olùwà ni ó sábà máa ń wà. Atọ́ka náà ni "ha" ìṣèbéèrè onídáhùn bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́.

(2) a. Iná ètò ẹ̀kọ́ ha ń jó rẹ̀yìn?
b. O ha kí mi?
d. Ọkọ rẹ ha mọ pé o ń bínú?

### 3.2.3 Ìṣèbéèrè onídáhùn bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́ alátọ́ka ìparí

Ìsọ̀rí kẹ́ta ìṣèbéèrè onídáhùn "bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́" alátọ́ka ìparí ni èyí tí atọ́ka ìbéèrè rẹ̀ máa ń wà ní ìparí gbólóhùn. Méjì ni atọ́ka ìsọ̀rí yìí; àwọn ni: "bí" àti "ni".

(3) a. Aláìsàn náà jẹun bí?
b. Aláìsàn náà jẹun ni?

### 3.2.4 Ìṣèbéèrè onídáhùn bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́ alátọ́ka ìbẹ̀rẹ̀ àti ààrín

Ní ìparí, ó tún ṣeé ṣe kí ìṣèbéèrè onídáhùn "bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́" ní àkànpọ̀ atọ́ka ìbéèrè méjì tí ọ̀kan máa wà ní ààrín tí èkejì máa wà ní ìparí.

(4) a. Ìyá ha wá ọmọ rẹ̀ tó sọnù bí?
b. Bọ́lá ha mọ̀ ẹ́ mọ́ bí?

## 4.0 ÌGÚNLẸ̀

Ọ̀nà tí a ń gbà ṣe ìbéèrè tí ìdáhùn rẹ̀ máa jẹ́ "bẹ́ẹ̀ ni" tàbí "bẹ́ẹ̀ kọ́" ni ohun tí a ti wò ní ìpín yìí.

## 5.0 ISỌNÍSÓKÍ

A ti wo ìṣèbéèrè onídáhùn "bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́"; bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú oríkì irúfẹ́ ìbéèrè náà. A tẹsíwájú pẹ̀lú àyẹ̀wò oríṣi ìbéèrè nípa wíwo ipò atọ́ka wọn. A ṣe àfihàn oríṣi mẹ́rin ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀: ìṣèbéèrè onídáhùn "bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́" alátọ́ka ìbẹ̀rẹ̀, alátọ́ka ààrín, alátọ́ka ìparí àti àpapọ̀ alátọ́ka ààrín àti ìparí. A fi àpẹẹrẹ tó jọjú ṣe àtìlẹ́yìn àlàyé wa.

## 6.0 IṢẸ́ ÀYÀNṢE ONÍMÁÀKÌ OLÙKỌ́

1. Oríṣi ìṣèbéèrè onídáhùn "bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́" mélòó ló wà? Dárúkọ wọn.
2. Atọ́ka ìṣèbéèrè onídáhùn "bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́" mélòó ló wà ní ìbẹ̀rẹ̀ ní Yorùbá? Dárúkọ wọn
3. Àwọ atọ́ka ìṣèbéèrè onídáhùn "bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́" mélòó niwọn lè jẹyọ pọ̀? Dárúkọ wọnkí o sì lò wọ́n nínú gbólóhùn.

## 7.0 ÀWỌN ÌWÉ FÚN KÍKÀ

Awobuluyi, Oladele (1978). *Essentials of Yoruba Grammar*. UPL. Oxford University Press, Ibadan. Chapter 3

Awobuluyi, Oladele (2013). *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá.* ATMAN Limited. Osogbo.

Bámgbóṣé, Ayọ̀. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá.*

Yusuf, Ọrẹ. 1995.*Gírámà Yorùbá Àkọ̀tun.* o.i. 34-35.

# ÌPÍN 5 ÌṢÈTẸNUMỌ́

**Àkóónú**

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
3.1 Oríkì Gbólóhùn Ìṣètẹnumọ́
3.2 Ìpinsísọ̀rí gbólóhùn Ìṣètẹnumọ́
3.2.1 Ìṣètẹnumọ́ Olùwà
3.2.2 Ìṣètẹnumọ́ Àbọ̀
3.2.3 Ìṣètẹnumọ́ Ọ̀rọ̀-ìṣe
4.0 Ìgúnlẹ̀
5.0 Isọnísókí ohun tí kọ́ọ̀sì yìí dálé
6.0 Iṣẹ́ Àyànṣe Onímáàkì Olùkọ́
7.0 Àwọn Ìwé fún Kíkà

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ní ìpín yìí ni á ti se iṣẹ́ tó dá lórí fífi gbólóhùn ṣe ìtẹnumọ́ nínú èdè Yorùbá.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ

Èròǹgbà wa níbí ni kí ọmọ lè dá gbólóhùn ìtẹnumọ́ mọ̀ kí ó sì lè dá fọ́nrán tí a ṣe ìtẹnumọ́ rẹ̀ nínú gbólóhùn pẹ̀lú atọ́ka ìtẹnumọ́ mọ̀.

## 3.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

A ó fún gbólóhùn ìtẹnumọ́ ní oríkì, a ó sì wo oríṣríṣi fọ́nrán tí a lè ṣe ìtẹnumọ́ rẹ̀.

### 3.1 Oríkì Gbólóhùn Ìṣètẹnumọ́

Gbólóhùn Ìṣètẹnumọ́ ni gbólóhùn tí a fi máa ń pe àkíyèsí olùgbọ́ sí ohun tó ṣe pàtàkì nínú gbólóhùn.

### 3.2 Ìpinsísọ̀rí gbólóhùn Ìṣètẹnumọ́

Ohun tó jẹ wá lógún níbí ni kí a wo oríṣi gbólóhùn ìṣètẹnumọ́ tó wà àti àbùdá wọn.

#### 3.2.1 Ìṣètẹnumọ́ Olùwà

Ọ̀kan lára gbólóhùn ìtẹnumọ́ ni èyí tó fàyègba kí a ṣe ìtẹnumọ́ ọ̀rọ̀-orúkọ, ọ̀rọ̀-arọ́pò orúkọ tàbí àpólá orúkọ tó bá wà ní ipò olùwà.

Tí èyí bá wáyé; àwọn ohun tó máa ṣẹlẹ̀ nì wọ̀nyí.

a. Èkíní, a ó gbé fọ́nrán tí a bá fẹ́ẹ̀ ṣe ìtẹnumọ́ rẹ̀ kúrò nínú gbólóhùn yẹn lọ sípò mìíràn lápá òsì.

b. Èkejì, a ó fi ọ̀rọ̀-arọ́pò aláìlẹ́ni “ó” tàbí “wọ́n” sí ipò tí fọ́nrán yẹn wà ká tó ṣe ìtẹnumọ́.

d. A ó ṣe ìfibọ̀ atọ́ka ìtẹnumọ́ “ni” lẹ́yìn fọ́nrán tí a ṣe ìtẹnumọ́ rẹ̀.

(1) a. **Ọlọ́pàá** mú Adé.
**Ọlọ́pàá ni** ó mú Adé.

b. **Ọlọ́pàá àti ọ̀daràn** di ara wọn mú.
**Ọlọ́pàá àti ọ̀daràn ni ó/wọ́n** di ara wọn mú.

d. **Ilé èṣù** wó lulẹ̀.
**Ilé èṣù ni** ó wó lulẹ̀.

e. Àwọn jẹ iṣu.
**Àwọn** ni **ó/wọ́n** jẹ iṣu?

Ohun mẹ́ta tí a mẹ́nubà lókè ni a máa ṣe alábápàdé nínú ọ̀kọ̀ọ̀kan àpẹẹrẹ mẹ́ta wọ̀nyẹn. Tí a bá wo (1), a ó ri mọ̀ wí pé ẹni tó mú Adé ni a fẹ́ mọ̀ nípa rẹ̀; ìyẹn, Ọlópàá. Nítorí náà ni a ṣe gbe kúrò ní àyè rẹ̀ lọ sí apá òsì. Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣáájú, tí a bá gbé olùwà kúrò láti ṣe ìtẹnumọ́, àyè olùwà kò gbọ́dọ̀ ṣòfo. Dandan ni kí a fi arọ́pò-orúkọ tó bá tọ̀nà dípò rẹ̀. Ìyẹn ló fà á tí “ó” fi ṣúyọ ní ipò tí “Ọlọ́pàá” wà tẹ́lẹ̀. Ní ìparí, “ni” gbọ́dọ̀ tẹ̀lé fọ́nrán ìtẹnumọ́.

### 3.2.2 Ìṣètẹnumọ́ Àbọ̀

Ẹ̀wẹ̀, ó tún ṣeé ṣe kí a ṣe ìtẹnumọ́ ọ̀rọ̀-orúkọ, arópò-orúkọ, arọ́pò afarajorúkọ tàbí àpólà orúkọ tó wà ní ipò àbọ̀ tàárà. Tí èyí bá wáyé; àwọn ìgbésẹ̀ méjì máa wáyé:

a. A ó gbé fọ́nrán tí a bá fẹ́ẹ̀ ṣe ìtẹnumọ́ rẹ̀ kúrò ní ipò àbọ̀ nínú gbólóhùn jáde lọ sípò mìíràn lápá òsì.

b. A ó ṣe ìfibọ̀ atọ́ka ìtẹnumọ́ “ni” lẹ́yìn fọ́nrán ìṣètẹnumọ́.

(2) a. Ẹkùn pa **ọdẹ**.
**Ọdẹ ni** Ẹkùn pa.

b. Ẹlẹ́hà já **ìwé**.
**Ìwé ni** ẹlẹ́hà já.

Ohun méjì tí màá mẹ́nu bà lókè náà ni a máa ṣe alábápàdé nínú ọ̀kọ̀ọ̀kan àpẹẹrẹ mẹ́ta wọ̀nyẹn. Tí a bá wo (2a), a ó ri mọ̀ wí pé "ẹni tí Ẹkùn pa" ni a fẹ́ ṣe ìtẹnumọ́ rẹ̀; ìyẹn, "ọdẹ". Nítorí náà ni a ṣe gbe kúrò ní àyè rẹ̀ lọ sí apá òsì. Tí èyí bá sì ti wáyé, "ni" gbọ́dọ̀ tẹ̀lé fọ́nrán tí a ṣe ìtẹnumọ́ rẹ̀.

### 3.2.3 Ìṣètẹnumọ́ Ọ̀rọ̀-ìṣe

Fọ́nrán mìíràn tí a tún lè ṣe ìtẹnumọ́ rẹ̀ ni ọ̀rọ̀-ìṣe. Tí a bá ní láti ṣe ìtẹnumọ́ ọ̀rọ̀-ìṣe, àwọn ìgbésẹ̀ yìí gbọ́dọ̀ wáyé.

a. A ó gbé ọ̀rọ̀-ìṣekúró nínú gbólóhùn tó ti jẹ yọ sí apá òsì.
b. A ó fi ẹ̀dà ọ̀rọ̀-ìṣetí a fẹ́ ṣe ìtẹnumọ́ sí àyè rẹ̀.
d. A ó sọ ọ̀rọ̀-ìṣe tí a fẹ́ ṣe ìtẹnumọ́ rẹ̀ náà di ọ̀rọ̀-orúkọ Jìrọ́ǹdù.
e A ó ṣe ìfibọ̀ atọ́ka ìtẹnumọ́ "ni" lẹ́yìn fọ́nrán ọ̀rọ̀-orúkọ Jìrọ́ǹdù tí a ṣe ìtẹnumọ́ rẹ̀.

(3) a. Iná **jó** ọjà Oṣòdì.
**Jíjó** ni iná jó ọjà Oṣòdì.

b. Awakọ̀ náà **sùn** lórí eré.
**Sísùn** ni awakọ̀ náà **sùn** lórí eré.

## 4.0 ÌGÚNLẸ̀

A ti wo gbólóhùn alátẹnumọ́ àti àwọn ìgbésẹ̀ tó máa ń wáyé ní ṣíṣe ìtẹnumọ́ lédè Yorùbá.

Ìtẹnumọ́ ni iṣẹ́ ìpín yìí dálé. A wo orísì fọ́nrán mẹ́ta tí a lè ṣe ìtẹnumọ́ rẹ̀ àti àwọn ìgbésẹ̀ tó máa ń wáyé tí a bá ṣe ìtẹnumọ́ ọ̀kọ̀ọ̀kan. Èyí tó gba àkíyèsí ni wí pé tí a bá ṣe ìtẹnumọ́ ọ̀rọ̀-ìṣe, a gbọ́dọ̀ fi ẹ̀dà rẹ̀ sílẹ̀, níbi tí a ti gbe kúrò, a sì gbọ́dọ̀ sọ ọ̀rọ̀-ìṣe náà di ọ̀rọ̀-orúkọ Jìrọ́ǹdù.

## 5.0 ISỌNÍSÓKÍ OHUN TÍ KỌ́Ọ̀SÌ YÌÍ DÁLÉ

Ibi tí a ti bẹ̀rẹ̀ kọ́ọ̀sì yìí ni ṣíṣe àgbékalẹ̀ àwọn ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ lédè Yorùbá. A wo àwọn ojúlówó ọ̀rọ̀ tó lè dá dúró tí ó sì lè dá ìtumọ̀ ní fúnra wọn àti àwọn tí kò lè dá dúró kí wọn ní ìtumọ̀. Ní ti ọ̀wọ́ àkọ́kọ́, a wo ìsọ̀rí mẹ́rin, ìyẹn ìsọ̀rí ọ̀rọ̀-orúkọ, ọ̀rọ̀-ìṣe, ọ̀rọ̀-ẹ̀yán àti ọ̀rọ̀ àpọ́nlé. Fún ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn, a fún wọn lóríkì, a sì pín wọn sí ìsọ̀rí ìsọ̀rí pẹ̀lú àpẹẹrẹ. Abala kejì ni ti ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ tí kò lè dá dúró kó sì fún wa ní ìtumọ̀. Àwọn ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ ni a pè ní wúnrẹ̀n aṣegírámà. A wò wọ́n ní sàkání mẹ́ta: sàkání àpólà-orúkọ, àpólà ìṣe àt igbólóhùn oníbọ̀, a sì ṣe àkójọ àpẹẹrẹ tó bá ìsọ̀rí wúnrẹ̀n aṣegírámà kọ̀ọ̀kan mu.

Lẹ́yìn náà ni a tẹ̀síwájú láti wo oríṣiríṣi àpólà tó wà lédè Yorùbá. Ní pàtàkì, a wo àpólà-orúkọ, àpólà-ìṣe, àpólà-atọ́kùn, àpólà ìyísódì àti àpólà amúpé; a sì wo àkóónú àpólà kọ̀ọ̀kan pẹ̀lú àpẹẹrẹ tó jọjú.

Ní abala kejì kọ́ọ̀sì yìí ni a ti wo àtòpọ̀ ọ̀rọ̀ àti àpólà tó di gbólóhùn. Ohun méjì ni a dojúkọ. Èkíní, a wo gbólóhùn nípa ìhun wọn. Èkejì, a wo gbólóhùn àti oríṣríṣi ìlò tàbí iṣẹ́ ti wọ́n lè ṣe nínú afọ̀.

Níbẹ̀ ni a ti ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé nípa gbólóhùn:

a. abọ́dé
b. gbólóhùn alákànpọ̀
d. gbólóhùn oníbọ̀.

Fún ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn, a bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú oríkì, kí a tó tẹ̀síwájú láti wo àwọn fọ́nrán ìhun ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn pẹ̀lú àpẹẹrẹ tó fi wọ́n hàn.

Ní abala ìlò gbólóhùn tàbí iṣẹ́ tí gbólóhùn lè ṣe nínú ìpèdè, a fi yé akẹ́kọ̀ọ́ wí pé gbólóhùn lè ṣe iṣẹ́:
Ìròyìn
Ìpàṣẹ
Ìbéèrè
Ìtẹnumọ́

A wo ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn fínnífínní pẹ̀lú àlàyé kíkún àti àpẹẹrẹ tó pọ̀ fún ọ̀kọ̀kan wọn. Ní ti ìlò gbólóhùn gẹ́gẹ́ bí ìròyìn, a fi hàn pé a lè fi gbólóhùn ṣe àlàyé ohun kan tàbí kí a fi sọ nípa ìṣẹ̀lẹ̀ kan. A jẹ́ kí ó yé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ pé fífi gbólóhùn pàṣẹ lè jẹ́ àṣẹ líle tí a mọ̀ sí àṣẹ sánpọ́nná. Àṣẹ lè jẹ́ ti ẹ̀lẹ̀ tó máa ń wáyé bí ẹ̀bẹ̀. Wàyí o, ní ti lílo gbólóhùn gẹ́gẹ́ bí ìbéèrè, a wo oríṣi gbólóhùn ìbéèrè méjì pàtàkì. Èkíní ni ìbéèrè ti ìdáhùn rẹ̀ máa fún wa ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé. Ìyẹn ni a pè ní gbólóhùn onídáhùn àlàyé. Èkéjì ni a pè ní ìbéèrè "bẹ́ẹ̀ ni-bẹ́ẹ̀ kọ́". Oríṣi ìbéèrè yìí náà gba orúkọ rẹ̀ láti ara ìdáhùn tí a máa ń fún un. Ìyẹn ni pé púpọ̀ ìbéèrè yìí ni ìdáhùn rẹ̀ lè jẹ́ "bẹ́ẹ̀ ni" tàbí "bẹ́ẹ̀ kọ́". Ní ìparí ni a ti wo lílo gbólóhùn ṣe ìtẹnumọ́. Kókó ohun tí ó jẹ wá lógún níbẹ̀ ni irú fọ́nrán tí a lè ṣe ìtẹnumọ́ àti àyè tí irú fọ́nrán bẹ́ẹ̀ lè wà tí a bá fẹ́ẹ́ ṣe ìtẹnumọ́ rẹ̀. A sì fi ìyàtọ̀ tó wà láàrín ìtẹnumọ́ ọ̀rọ̀-orúkọ olùwà, àbọ̀ àti ọ̀rọ̀-ìṣe.

## 6.0 IṢẸ́ ÀYÀNṢE ONÍMÁÀKÌ OLÙKỌ́

1. Àwọn ìgbésẹ̀ wo ló máa wáyé tí a bá fẹ́ẹ́ ṣe ìtẹnumọ́ ọ̀rọ̀-ìṣe?
2. Kí ni ìjọrà láàárín ìṣèbéèrè onídáhùn àlàyé àti ìṣètẹnumọ́?
3. Kí ni ohun pàtàkì tí ó máa wáyé tí a bá ṣe ìtẹnumọ́ olùwà?
4. Kí ni ìyàtọ̀ tó wà láàárín ìṣètẹnumọ́ ọ̀rọ̀-ìṣe àti ọ̀rọ̀-orúkọ àbọ̀?
5. Wo gbólóhùn ìsàlẹ̀ yìí kí o ṣe ìbéèrè àti ìtẹnumọ́ àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ tó wà níbẹ̀: "Òsínbàjò wà nínú bàlúù ní àná".

## 7.0 ÀWỌN ÌWÉ FÚN KÍKÀ

Awobuluyi, Oladele (1978). *Essentials of Yoruba Grammar*. UPL. Oxford University Press, Ibadan.

Awobuluyi, Oladele (2013). *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá.* ATMAN Limited. Osogbo

Bámgbóṣé, Ayọ̀. 1990. Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá.o.i. 205

Yusuf, Ọrẹ. 1995. *Gírámà Yorùbá Àkọ̀tun*. (1995). o.i. 205-215.